# Kini Ìdí Tí A Ko Fi Jẹ Ọmọ Ijọ Ẹlẹkọ-Adamọ Kan?

Jeffersonville, Indiana, USA
Ọjọ Kẹtadinlọgbọn, Oṣu Kẹsan,1958

1 ...... anfani ni o jẹ fun mi lati pada wa sí ibi aga-iwaasu lẹẹkan si lẹhin bii, mo ro, bi i oṣù mẹta sẹyin ti emi ko fi wa si ibiyi. Awọn ọ̀kẹ́rẹ́ ti ni awọn akoko ti o nira, bẹẹni emi náà pẹ̀lú. Oo, o jẹ akoko isinmi, bi o tilẹ jẹ wipe, nisisiyi, mo ni ìfẹ́ bi i wipe, ki emi tun pada sinu ìsìn lẹẹkan si. Mo si ni ireti pe a o bẹrẹ nisisiyi ni aṣalẹ ọjọ Iṣẹgun ti o ń bọ̀, fun ìsọjí ninu gbọngan yi nibiyi. Ati ti Oluwa ba fẹ, mo ni bi i.... Oluwa ti ṣeleri iṣe iranṣẹ ti o yatọ ati iṣẹ iranṣẹ tuntun fun mi. Ti o ba si wù Ú lati ṣe èyí, mo nireti lati bẹrẹ iru ìsìn báyi ni ọ̀sẹ̀ ti o ń bọ̀, nibiyi ninu gbọngan yi, fun igba àkọ́kọ́.

Ati lẹhinnaa emi ko ni ìpàdé kankan ti a ti ṣeto rẹ silẹ, ayafi ni ilu Australia ati ni ilu Zealand tuntun nikan ni oṣù kin-in ti o ń bọ yi. Ati pe arakunrin Osborn ń pe fun ipade àpapọ eyiti mo ti ṣeleri fun nibiyi ni awọn ọjọ ti o kọja sẹyin, ni ilu Tulsa, ni igba diẹ si akoko yi, ṣugbọn a ko ti ni idaniloju eyi sibẹ.

2 O jẹ ohun ti o dara. Arakunrin Jeffries, lati le tun pada bọ ọwọ́ rẹ nibiyi, ki emi si gbọ ọmọkunrin rẹ kọrin yẹn pẹlu, ti iwọ si ń lu dùrù. Emi fẹran èyí, baba ati ọmọ. Ṣe iwọ fẹran rẹ pẹlu? “Kọ ọmọ rẹ ni ọ̀nà ti yoo rin” Eyi dara, Ọgbẹẹni Gnenther, o mọ pe ohun ti o dara ni, ẹyin mejeji. “Kọ ọmọ rẹ ni ọ̀nà ti yoo rin, ati nigbati o ba dagba, oun ko ni kuro ni ọna naa, ”Eyi si jẹ otitọ. Awọn igba miran le wà ti yoo kuro ninu rẹ̀, ṣugbọn awọn nkan wọnyi ko ni fi i silẹ, ṣe ẹ ri. Yoo wà pẹlu rẹ̀ nigba gbogbo. Awọn ikọni akọkọ ti a fi kọ ọmọ ati eyikeyi iṣẹsi ti a fi kọ́ dagba lati ṣe. Yo o wa pẹlu rẹ̀ nigba gbogbo. Nisisiyi eyi ni....

3 Mo pade arakunrin Jefferies nita, mo si sọ fun wipe, Arakunrin Jeffries....' mo ro wipe, “O mọ̀, inu mi maa ń dùn nigba gbogbo lati ri eyikeyi ninu awọn arakunrin mi ti wọn wa se`abẹ̀wo ni ipade yi, ṣugbọn iru alẹ̀ bi eleyi fun arakunrin ti o wá ṣe àbẹ̀wò lati wá!” Alẹ yi wà fun awọn ọmọ ijọ ti o njọsin ninu àgọ́-ijọsin nikan, ṣaaju isọji yi nikan. Alẹ yi ni, a fẹ mu alẹ yi ati owurọ ọ̀la ati alẹ ọ̀la, fun ohun ti a gbagbọ ninu àgọ́-ijọsin yi, lati tun wọn sọ lẹẹkan si. A ni awọn igbagbọ ti o yatọ kan, ti o ṣe ajeji, ṣugbọn ni ọna kan tabi ni ọna miran a ri wọn ninu Bibeli. Wọn wà nibẹ ni ọna ti o dara.

4 Ati nisisiyi ti arakunrin tabi arabinrin ti o jẹ alejo ba wa nibiyi, ti wọn jẹ ti ọmọ ijọ ẹlẹkọ adamọ kan, tabi ti wọn ko gbagbọ ninu ohun wọnyi, ti wọn kan joko nibiyi ni alẹ yi nikan, a fẹ ki ẹ mọ wipe a ki yin kaabọ. A ki yin kaabọ bi a tị se le ki yin tó. Ṣugbọn nisisiyi emi.... A jẹ ki eyi nira diẹ. Nitori ti o ba jẹ wipe ẹyin ko gbagbọ ninu rẹ, o dara, nisisiyi, ẹ ṣe bi emi ti ṣe maa n ṣe ti mo ba ń jẹ akara-oniyẹfun oni kóró. Nigbati mo ba ń jẹ ẹ (eyi si jẹ ohun ti mo fẹran); nigba gbogbo ti mo ba ń jẹ ẹ.... nigbati mo ba ǹ jẹ akara-oniyẹfun naa, ti mo ba kan koro ninu rẹ̀, emi ko ni sọ akara-oniyẹfun naa nù - emi a kàn sọ koro inu rẹ nù ni maa si tẹsiwaju lati maa jẹ akara-oniyẹfun naa. Tabi ti mo ba ń jẹ ẹran-adiyẹ. Nisisiyi, gbogbo yin ni ẹ fẹran ẹran-adiyẹ, ṣe ẹ ri. Nigbati ẹ ba kan egungun ninu rẹ̀, ẹ ko ni dánuduro lati jẹ ẹran-adiyẹ naa, ṣugbọn ẹ o yo egungun naa kúrò ẹ o si tẹsiwaju lati jẹ ẹran-adiyẹ naa. Nitorina, bẹẹ gẹlẹ ni ki ẹ ṣe ni aṣalẹ yi. Ohun ti mo ń sọ nibiyi ni wípé, ẹyin kan, nigbati ẹ ba kan ohun kan, ẹ sọ wipe, “Nisisiyi, emi kò.... mo kàn joko nibiyi gẹgẹ bi ẹkọ opomulero ijọ kekere kan fun awọn isin mẹta ti o ń bọ̀. Wọn kan ń tún awọn nkan ti wọn gbagbọ ninu rẹ sọ ni, wọn si tun ń kẹkọ ninu rẹ̀.”

5 Ati ọna kan ṣoṣo ti o fi le ṣe eyi, ti o fẹrẹ jẹ wipe, iwọ yoo mu ki ẹnikan gba a gbọ ni wipe, ki o tun sọ dada titi ti wọn yoo fi mọ̀ wipe ohun yi ni ohun ti o jẹ́ otitọ. Ọna kan ṣoṣo ti o le gbà lati le jẹ ki eleyi rinlẹ niyi. Gẹgẹ bi ọrẹ mi kan, Ọgbẹẹni Woods, mo ti wà pẹ̀lú rẹ̀. Ti o ba gba`isó wọle ni ilaji ọ̀nà, ti gbogbo awọn patako si yọ lẹyọ kọọkan, atẹgun yoo bi i lulẹ ni aipẹ́, ṣugbọn o ni lati gba ìṣó naa wọle daradara ki o si jẹ ki o mú ohun kan daada. Nitorina nisisiyi; ti mo ba ṣe alaibu-ọla fun awọn ohun kan nibiyi, si iwọ ti o jẹ alejọ ni aṣalẹ yi ti o wà ni ijoko, emi kò gbiyanju lati fi ojú kéré rẹ. Emi kán ń gbiyanju lati fi idi nkan wọnyi mulẹ fun ijọ yi ni awọn ohun ti a gbagbọ. Ti gbogbo wa ba ni oye eyi daradara, ẹ sọ pe “amin” O dara, eyi wa ni ibamu ni pìpe.

Mo fẹ mu eyi kuro ni ọwọ́ mi lẹhin naa.... Wọn ń gba ohùn wọnyi silẹ, ati bẹẹbẹẹ lọ, ni ọjọ́ iwaju ti wọn ba fẹ wadi ohun ti a gbagbọ ninu rẹ lẹhin naa, ati awọn òpómúléró ohun ti a duro le lóri, awọn ohun ti a gbà silẹ wọnyi yoo sọ wọn. A si maa ń ṣe eleyi nigba gbogbo, nitoripe awọn eniyan tuntun ń wọle wá, a si ń tẹ̀ siwaju. Ati nisisiyi, ako ni ni anfani lati le lọ ninu gbogbo ẹkọ-opomulero ijọ, ṣugbọn diẹ lara wọn ni a fẹ sọrọ lori rẹ̀. Ati nisisiyi ni alẹ Ọjọ́-rú, bi o tilẹ jẹ wipe, a o bẹrẹ̀....

6 Nisisiyi, ni ọjọ Ajé ati ni ọjọ Iṣẹgun emi fẹ lọ lati lọ gbadura, lati le pese ara mi silẹ fun isin-ìwòsàn. O si le wa si ori ẹrọ-abanisọrọ, tabi ohunkohun ti o ba fẹ́, ki o si mu ẹnikan wá ti o ba fẹ́ wa si ibi ipade-isọji ti o ń bọ. O si sọ fun wọn pe ki wọn maṣe kánju wá, nisisiyi kò ki ń ṣe pe wọn yoo wá, wọn yoo si sọ wipe, “O dara, emi yoo sare wọle a o si gbadura fun mi ni aṣalẹ yi, tabi ni alẹ-ọla gbogbo rẹ niyi....” Iwọ ko le ṣe eleyi. Iwọ yoo wọle wá, iwọ yoo si tẹti silẹ fun akoko diẹ, nitoripe a fẹ fi akoko silẹ lati waasu Ọrọ naa ni ìbámu ti yoo fi jẹ wipe èṣù ko ni rí aye kankan lati gbé ori rẹ sókè.

Ati lẹhin naa nigbati o ba jẹ ki igbagbọ rẹ wa ninu rẹ̀ titi de òpin Ọrọ naa. Titi ti iwọ yoo fi bẹrẹ si ni

gbagbọ, lẹhin naa jẹ ki ohun-imọlara aifojuri rẹ wá si oju-iṣe, lẹhin naa igbagbọ Ọlọrun yoo ti i lẹhin, lẹhin naa iwọ yoo tẹsiwaju lati maa lọ, ṣe o ri. Nitoripe igbagbọ rẹ ko le ṣe ohun pupọ. Awọn ohun-imọ-ara aifojùri rẹ ni lati gbéra lọ si ipá ọ̀nà ti igbagbọ rẹ ń lọ, ati lẹhin naa igbagbọ Ọlọrun yoo tẹle lẹhin yoo si fi idi gbogbo rẹ mulẹ. Ṣe o ri? Ṣugbọn ti o ba ṣe wipe igbagbọ rẹ ni, "Oo, bẹẹni, mo ni bayi," ati awọn ohun-imọ-ara aifojuri rẹ ń farahan nibiyi ti wọn si ń sọ wipe, "emi ń finú-gbero pé boya yoo ṣiṣẹ fun mi." Eyi ko ni ṣe e, lẹhin naa, ṣe o ri. Nitorina a fẹ ki eyi jẹ isin-iwosan tootọ. Ati ṣaaju ki a to mu ẹnikẹni wọ inu iyàrá ati fun awọn iwosan, tabi awọn isin tuntun wọnyi, mo fẹ ki wọn ni loye daada idi ti wọn fi wá si ibiyi. Nitorinaa kan rántì, ki o si wá ki o si bẹ wa wò, inu wa yoo si dùn lati ni ọ nibiyi.

7 Nisisiyi, ranti bayi, ni owurọ a o tẹsiwaju pẹlu ẹkọ-opomulero ijọ, ati ni ọ̀nà kannaa ni alẹ ọla. Nisisiyi, a ki yin kaabọ, ẹnikẹni ti o ba wù le wa. Inu wa maa ń dun nigba gbogbo lati ri ẹnikẹni. Ṣugbọn nisisiyi, ni aṣalẹ yi a ṣe akanṣe rẹ fun awọn ti o ń jọsin ni ibi agọ-ijọsin nibiyi, awọn ti a ti tọ́ dagba pẹlu ẹkọ-opomulero yi. Nitori, ni ita lọhun, ni ilẹ-ihinrere, a kan maa ń waasu awọn ẹkọ ibẹẹrẹ opomulero ihinrere ti inu Iwe-Mimọ. Ṣugbọn ni àgọ́-ijọsin nibiyi, a ni awọn èrò wa ati awọn ohun ti a gbagbọ, gẹgẹ bi ijọ, awọn ohun ti a si fẹ lọ ninu rẹ ni aṣalẹ yi niyi.

Ṣaaju ki a to ṣi Ọrọ ibukun Rẹ, ṣe a kan le tẹ ori wa ba fun iṣẹju kan lati gbadura.

8 Ọlọrun Olodumare ati alagbara, Iwọ ṣaaju ki ayé to bẹrẹ si ni-yipo lati ori ohun ti a fi da aye ti o kere julọ. Iwọ ni Ọlọrun. Iwọ ko si yipada rara. Ati nigbati ko si ohun ẹdá ti o kere julọ ti yoo di ayé mú, ti kò si ayé mọ́ ti a le di mu, Iwọ si jẹ Ọlọrun bakannaa. Iwọ wà fun ayeraye ati lati inu ayeraye, Iwọ ni Ọlọrun. Iwọ kò ni ibẹrẹ ọjọ tabi òpin aye.

Nigba gbogbo ni Iwọ wà. Ati, Baba, Iwọ jẹ ailopin awa si jẹ ẹni opin, nitorina a bere fun anu mimọ Rẹ, Ọlọrun, ti a si loye pe, ẹmi wa yi yoo dàpọ̀ mọ́ ti ayeraye - lati inu eroja ti akoko si inu ayeraye. Nitorina, Oluwa, a wà nibiyi lati ṣe àyẹ̀wo ìgbàlà ọkan wa, lati le ri bi a ṣe duro ni iwaju Ọrọ Rẹ, ati ki a si le ri bi awọn ìrírí wa ṣe dúró. Ṣe a ń gbe igbesi-aye, eyiti o tẹ Ọlọrun lọrun? Ṣe ẹmi wa ń ṣe ijẹri si Ẹmi Rẹ? Ati pe ṣe ẹkọ wa ri bakannaa pẹlu ti Bibeli? Ati Baba, jẹ ki a ṣe ayẹwo awọn nkan wọnyi fínífíni lapapọ ni awọǹ isin mẹta ti o ń bọ wọnyi. ṣe eyi Oluwa.

9 Bukun fun olusọ-agutan ti o wa nibiyi, awọn diakoni, awọn alamojuto ijọ, ati gbogbo awọn ọmọ-ijọ, gbogbo awọn ti wọn wá si ile-ijọsin. Lati igba ti mo ti wa nibiyi, Oluwa, awọn ọpọlọpọ, ọpọlọpọ wà ti emi kò mọ orukọ wọn paapa tabi ibi ti wọn ti wá, ṣugbọn o dami loju pe O mọ nipa gbogbo wọn. A si wà nibiyi nitori idi pataki yi ni aṣalẹ yi, Oluwa, lati ni ìdàpọ̀ pẹlu Ọrọ naa ti a kọ silẹ. Si fun wa ni Ẹmi-Mimọ naa ninu aye wa, ki a ba le joko pẹlu ifọkanbalẹ pẹlu irẹlẹ ati pẹlu ibẹru Ọlọrun, ki o si yẹ aye wa ẁo pẹlu Ọrọ Rẹ, ṣe èyí, Oluwa.

Ati ninu gbọngan yi ni aṣalẹ yi, Oluwa, awọn arakunrin mi ti wọn wa lati oriṣiriṣi ijọ, Ati pe, Oluwa, mo dupẹ pe wọn wa nibiyi fún idapọ. Boya a ko gbagbọ bakanna lori awọn igbagbọ ipinlẹ ẹkọ-òpómúléro diẹ, ṣugbọn ninu igbagbọ ipinlẹ nla kan ṣoṣo naa ti a duro le lori gẹgẹ bi arakunrin ti o wa ni isọkan, ti o wà niwaju, O Ọlọrun, jẹ ki eyi fun idapọ wa ni agbara ati àwa.... ati okùn ore-ọfẹ Ọlọrun ati ìfẹ́ ki o bà lé wa lórí lọpọlọpọ. Nisisiyi a loye, Oluwa, pe iṣẹ eleyi lagbara fún eniyan lati ṣe, nitoripe ni aṣalẹ yi nibiyi a ń finú-gbero nipa opin-irinajo awọn ọkàn ti o jẹ àkàyẹ fun ayeraye. Nitorina a gbadura pe ki Ẹmi-Mimọ ki o wọ inu Ọrọ naa lọ taara, ti yoo si gbe e kalẹ ti yoo ṣalaye rẹ ni ọna tiRẹ fun wa, awọn ohun ti O fẹ ki a mọ. Ṣe eyi, Oluwa. Ati nigbati .... ti isin naa ba pari, jẹ ki a lọ gẹgẹ bi ijọ ti a fun ni agbara, ki a si wà ni isọ̀kan ki a si mu ọkan wa ati èrò wa gbogbo papọ pẹlu arakunrin wa ti a jijọ jẹ ọmọ-ilu ijọba Ọlọrun ki a si tẹsiwaju si dara ju ti atẹyin wa lọ.

10 Mo si fẹ dupẹ lọwọ Rẹ, Oluwa, nibiyi niwaju ijọ ati niwaju gbogbo eniyan ti o wa nibiyi, ti Iwọ fi fun mi nisisiyi ọpọlọpọ ọ̀sẹ isinmi ti o dara! Ara mi le ni ọna iyanu ni aṣalẹ yi, nitoripe iwa-laaye Rẹ ati ibukun Rẹ. Ọlọrun, a gbadura fun Arakunrin wa ti o wa nibiyi, arakunrin wa ti o ń lọ si oke-òkun, ti o ń lọ si awọn ibi dúdú ni ibi awọn orilẹ-ede to ṣú dúdú nibiti igbesi-aye rẹ̀ ti wà ninu ewu. Oluwa, bukun fun Arakunrin wa Jeffries bi o ti ṣe ń lọ ati ọmọ rẹ ati iyawo rẹ, fun ni ọpọlọpọ ibukun. Jẹ ki o lọ sinu awọn ibi òkùnkùn titi imọlẹ ihinrere yoo tán kaakiri ni gbogbo orilẹ-ede. Gbọ wa, Baba, nitori a bere ẹbẹ yi ni orukọ Jesu Oluwa. Ọmọ Rẹ Amin.

11 Bayi, ni aṣalẹ yi, nigbati mo ń ka lati inu Bibeli Scofidi kekere mi. Mo ṣẹṣẹ kọja ọmọ-ọdun marun-un-le-logun ni aipẹ yi ni. Sibẹ mo si tun le ka a si, ṣugbọn n ko riran daradara, nitorina mo maa n lo awo-ojú ti a fi ń kawe nigbakugba ti mo ba fẹ kẹkọ. Emi yoo wa wo bi yoo ti se ṣiṣẹ ni aṣalẹ yi, fun igbà àkọ́kọ́. Bayi mo ni akori bi eleyi; eyiti o jẹ wipe, Ṣe o pọn dandan fún ijọ....? Oo, ọpọlọpọ awọn nkan ti a ba le de ibẹ̀. Ọkan ninu wọn; kini idi ti a fi ń pe wa ni ijọ naa? Kini idi ti a ko fi jẹ ijọ ẹlẹkọ adamọ? Kini idi ti a fi gbagbọ ninù abò ayeraye ti ọkàn onigbagbọ? Kini idi ti a fi ṣe lodi si awọn obinrin oniwaasu? Kini idi ti a fi ńṣe iribọmi pẹlu riri gbogbo ara eniyan sinu omi? Ati pe, ṣe ijọ yoo la ipọnjù nla kọja? Ati ọpọlọpọ awọn akori ti o jẹ kókó nibiyi. Mo ro pe mo ni bi i marun-un-din-logun tabi meji-din-logun ninu wọn fun awọn aṣalẹ diẹ ti o wà niwaju.

12 Nitorina emi ń rò ni aṣalẹ yi, ni àkọ́kọ́, lati bẹrẹ pẹlu, o dabi ẹnipe Oluwa fi sinu ọkan mi, fun akori yi nikan: “Idi ti a ko fi jẹ ijọ ẹlẹkọ adamọ kan?” Idi ni wipe.... Nisisiyi, a ko ni ohunkan lodi si awọn eniyan miran ti wọn jẹ ti ijọ ẹlẹkọ adamọ. A ko ni ohunkohun lodi si wọn, ṣugbọn mo fẹ ṣalaye kini idi ti a ko fi dapọ pẹlu ijọ ẹlẹkọ adamọ kankan. A gbe ọwọ le mi ninu ijọ Onitẹbọmi kekere kan, gẹgẹ bi ẹ ti se mọ̀. Ijọ Onitẹbọmi ko ki ń ṣe ijọ-ẹlẹkọ adamọ. Ayafi ni aipẹ yi, ati nisisiyi wọn ti ń di ijọ ẹlẹkọ-adamọ gẹgẹ bi awọn iyoku. Ṣugbọn, idi ti a ko fi di ijọ ẹlẹkọ adamọ kan....

13 Nisisiyi, a jẹ ẹgbẹ kan. A jẹ ẹgbẹ kan, eyiti a fi orukọ rẹ silẹ nibiyi ninu ile-ẹjọ ti ijọba gẹgẹ bi i ẹgbẹ kan, awọn ẹgbẹ eniyan kan ti wọn korajọ papọ bi ẹgbẹ́ lati jọsin fun Kristi, ṣugbọn a ko si ninu ijọ ẹlẹkọ adamọ. Ko si ẹnikẹni ti yoo jẹ adari lori wa, ṣe ẹ ri. Ko ki ń ṣe ijọ ẹlẹkọ adamọ kan. O kan jẹ ẹgbẹ kan ti o n ni idapọ papọ laarin awọn Kristẹni, onigbagbọ. Awọn eniyan wa si ile-ijọsin nibiyi, ibiyi si di ile-ijọsin wọn ti wọn yan laayo, ti wọn bá nifẹ́ lati wá niwọn igbati wọn ba wà laaye.

14 Wọn si lee wa si ibiyi ki wọn sị se lodi si gbogbo ohun ti a waasu. Eyi si dara gẹlẹ síbẹ̀. Iwọ, niwọn igbati o ba jẹ Kristẹni, o ni idapọ ati alabapin bakanna gẹgẹ bi awọn iyoku. Ṣe ẹ ri? Ti mo ba sọ wipe mo gbagbọ ninu iribọmi nipasẹ riri gbogbo ara bọmi, ti iwọ si gbagbọ ninu winwọ́n omi sori, ti o si duro lori rẹ, a si tún wà bakannaa gẹgẹ bi a tị se wà ti a ba gbagbọ bakannaa. O ṣe e ṣe ki a ma ri i bakannaa, ki o ri bakannaa, ṣugbọn ni wọn igbati o ba ti jẹ Kristẹni arakunrin tabi arabinrin, a ki ọ kaabọ gẹlẹ, ṣe ẹ ri. Gbogbo Eniyan.

15 Nitorina a kò ni ijọ ẹlẹkọ adamọ kankan, nitori mo ro wipe ijọ ẹlẹkọ adamọ maa ń pin okùn-ifẹ́ ara níyà ni. Awọn miran ninu wọn yoo sọ wipe, “O dara, a ko ni ohunkohun ṣe ninu isọji yẹn: Isọji ijọ eleto niyẹn.” “O dara, o jẹ ti ijọ-Onitẹbọmi, a ko ni ọkankan.... a jẹ ti ijọ-eleto, a ko ni ohunkohun ṣe pẹlu iyẹn.” Arakunrin, ti Kristi ba wa ninu rẹ A ni ohun gbogbo ṣe pẹlu rẹ. A ni lati fi ohun gbogbo ti a ni.... O jẹ ara Kristi ni o jiya. Mo si ri ọpọlọpọ eleyi lori ilẹ̀ ni oni yi, bi a ti ṣe ni oni niyi.... Nisisiyi, Kristi ko ṣe bẹ e, ni igba kankan ri, ko da ijọ, ẹlẹkọ adamọ kankan silẹ rí. Nisisiyi, jẹ ki eleyi ni idaniloju ninu ọkan rẹ.

16 Bayi, emi yoo beere ni ọwọ rẹ ni aṣalẹ ọla, ti ọkankan ba wà ninu awọn nkan wọnyi ti o fẹ mọ̀, bi i awọn ìtàn kan ti mo ǹ kà àyọkà lati inu rẹ̀, tabi ohun kan tabi ohun miran.... emi kò ni akoko tó lati lọ ninu rẹ̀, emi kò ni le e lọ sinu akori miran, nitoripe o le lo ọpọlọpọ ọ̀ṣẹ lori akori kannaa. Ṣugbọn ti o ba fẹ mọ ibiti a ti ka àyọka, tabi ohunkohun, iwọ kan beere ni ọwọ mi ki o si fi si ori tabili, emi yoo si ri, emi yoo dahun rẹ fun ọ.

17 Bayi, ijọ ẹlẹkọ adamọ ti o ti wà fun igba pípẹ́ julọ ti o si jẹ ijọ ẹlẹkọ adamọ akọkọ ti a le e ni, ni ijọ Àgùdà. A si fi ọgbọn eniyan gbe e kalẹ ni bii ọọdunrun ọdun ati diẹ sẹyin lẹhin iku ọmọ-ẹyin-Jesu ti o gbẹ̀yiǹ. Eyi jẹ otitọ. Iwọ yoo ri itan yi ninu itan awọn Baba Nikia, ati ninu akọsilẹ ti Josefusi kọ, ati, oo, ati ọpọlọpọ awọn akọwe-itan olokiki. Ṣe ẹ rii? Ati lati inu awọn.... eyikeyi igba ijọ, titi ti o fi di igba iku ọmọ-ẹyin-Jesu ti o gbẹyin ati lẹhin ọọdunrun ọdun si akoko iku Aposteli ti o gbẹyin, ko si awọn ijọ ẹlẹkọ adamọ kankan. Ijọ Aguda ni o jẹ akọkọ ti o jẹ ijo-ẹlẹkọ adamọ.

Ijọ awọn Alagba si jẹ ijọ ti o jade kuro lati ara ijọ ẹlẹkọ adamọ kan. Atunṣe akọkọ bẹrẹ lati ori Luther. Lẹhin Luther ni Zwingli. Lẹhin Zwingli, ni Calvin, ati bẹẹbẹẹ lọ titi lọ bi eleyi. Titi o fi de isọji awọn ara Wesley, ti o fi lọ si Alexander, Johanu Smith, ati awọn iyoku, ṣe ẹ ri, titi o fi lọ si isalẹ. Ati ẹgbẹ ti o kẹyin ti a ni, nisisiyi, o jẹ, ohun ni oriṣiriṣi ipele igba ijọ ẹlẹkọ adamọ.

18 Mo si gbagbọ pe Ọlọrun ti ṣe nkan wọnyi ninu igba iran kọọkan. Ṣugbọn ṣe o ṣe akiyesi pe ni gbogbo igba ti ijọ ba kùna.... ati ni kété ti wọn ba di ijọ ẹlẹkọ adamọ wọn yoo bẹrẹ si ni ṣubu lẹyin naa? Ati nigba-ku-gba ti wọn ba ṣubu, Ọlọrun ko ni gbe ijọ naa dide pada mọ? Yoo di ohun igbagbe taara ni? Wayi o iwọ kàn.... ti o ba fẹ mọ ìtàn lori eyi, a le fi fun ọ, pe ko si ijọ kankan - ko si ninu ìtàn awọn ìtàn ijọ kankan ti ijọ ẹlẹkọ adamọ kan ba ṣubu, ti yoo si tun dide pada. Ijọ Baptisti, ijọ Mẹtọdisti, ijọ Alagba, ijọ Luther, eyikeyi ti o le jẹ; nigbati wọn ba ṣubu, wọn ti lọ! Nisisiyi, eyi jẹ otitọ. Nisisiyi, eyi .... mo sọ fun yin nisisiyi, ẹ wọ aṣọ ìlékè, nitoripe a o jẹ ki o wọle daadaa, ṣe ẹ ri. Ko ti ṣẹlẹ ri, ni igba kan, nigbati eniyan kan ba jade gẹgẹ bi aaladori ẹnikan, ti o si da ijọ kan silẹ, ti o bẹrẹ....

19 Ọlọrun maa ń ba aaladori ẹnikan ṣoṣo sọrọ, ko ki ń ba ijọ ẹlẹkọ adamọ sọrọ. Ọlọrun ko si ni ìgbà ijọ kankan ti o ba ijọ ẹlẹkọ adamọ sọrọ. O maa ń ba aladori ẹnikan ṣoṣo sọrọ ni. Ninu iwe Majẹmu Titun, O ba aladori ẹnikọọkan sọrọ. Ninu gbogbo iran, O maa ń ba aladori ẹnikọọkan sọrọ nigbagbogbo, ko ki ń ṣe ijọ ẹlẹkọ adamọ. Nitorina, lẹhin naa, ti Ọlọrun kò ba si ninu ijọ ẹlẹkọ adamọ, anfani kini o jẹ fun mi ti emi bá ni ohunkohun ṣe pẹlu ijọ ẹlẹkọ adamọ? Nisisiyi, emi ko sọrọ nipa awọn eniyan ti o wa ninu ijọ ẹlẹkọ adamọ yẹn, emi ń sọrọ nipa ijọ ẹlẹkọ adamọ naa funrara rẹ, nitoripe awọn eniyan Ọlọrun wà ninu gbogbo awọn ijọ ẹlẹkọ adamọ naa.

20 Nisisiyi, Ọlọrun ko fi aye gba pe ki ohunkohun ṣẹlẹ ayafi ti o ba kọkọ ṣe ikilọ rẹ. emi ko gbagbọ pe ohunkohun yoo wà ti....

Nisisiyi, gẹgẹ bi ki a ni ohun kan ti o ṣẹlẹ lati inu awọn ijọ. Bi a ti ṣe ni ọkan ni aipẹ nipa ẹjẹ ati ororo ati

bẹẹbẹẹ lọ, ṣe ẹ si mọ̀ nipa "Arakunrin Branham`Ọwọ́n" awọn lẹta, ati bẹẹbẹẹ lọ. Ṣugbọn ìdí ti mo fi ṣe lodi si èyí nipe, nitori ko si ninu Ọ̀rọ̀. O si gbọdọ ni ohun ti a gbọdọ gbé igbagbọ wa le lori. Ti a ko bá si le gbe lori awọn ijọ ẹlẹkọ adamọ kan, a ni lati gbe lori Ọ̀rọ̀ Ọlọrun! Nitori eleyi nikan ni ipinlẹ, ohun ni Ọrọ Ọlọrun.

21 Ati lẹhinnaa ti Ọrọ Ọlọrun kò ba sọrọ nipa ijọ ẹlẹkọ adamọ, ṣugbọn ti o ba sọrọ lodi si i, lẹhin naa a gbọdọ sọrọ lati ipasẹ Ọ̀rọ̀ naa. Laibikita ohun ti Bisọbu, tabi ẹnikẹni sọ, ohunkohun ti ẹnikẹni le ro nipa rẹ̀, ohun ti ọkunrin ti o dara sọ, ohun ti ẹnikẹni sọ; ti kò ba Ọ̀rọ̀ Ọlọrun mu, lẹhin naa o kùnà. Ṣe ẹ ri, o gbọdọ jẹ, o ni lati jẹ Ọrọ naa, ohun ti o kẹhin. Ọrọ Ọlọrun gbọdọ jẹ paripari ohun gbogbo amin.

Wayi o ranti, emi ko sọ pe ẹnikẹni ko ki ń ṣe Kristẹni (ṣe o loye eyi) ni ijọ ẹlẹkọ adamọ. Ọpọlọpọ ẹgbẹrun lọna ẹgbẹgbẹrun lọna mẹwa ni ilọpo mẹwa ti ọkàn wọn ṣe iyebiye ni o wa ninu gbogbo awọn ijọ ẹlẹkọ adamọ wọnyi, ti wọn jẹ ọmọ Ọlọrun. Ṣugbọn lati ya wọn nipa ati lati pin wọn niya, emi ṣe lodi si eyi. Ọrọ Ọlọrun si ṣe lodi si eyi pẹ̀lú.

22 Mo si gbagbọ pe ko si eto iṣe-jọba ti a n pe ni ẹkọkẹkọ kankan ti o wa lori ílẹ̀ loni, tabi eyiti o ti wà tẹlẹ rí ṣugbọn ohun ti Ọrọ Ọlọrun ti sọ tẹlẹ pe yoo wá. Mo si gbagbọ pe Ọ̀rọ̀ Ọlọrun yoo pese gbogbo ohun ti a nílò, ninu ọrọ naa gan an. Lati ibẹrẹ wa titi ti yoo fi de opin, o wa ninu Ọrọ Ọlọrun. Ati lẹhin naa, mo gbagbọ pe ti o ba jẹ Ọrọ Ọlọrun, lẹhin naa a gbọdọ.... O sọ tẹlẹ. Ati pe Ọrọ Ọlọrun jẹ ikilọ.

23 Bayi, maṣe ka Ọrọ Ọlọrun gẹgẹ bi o tị se n ka iwe iroyin, iwọ ka Ọrọ Ọlọrun nipasẹ Ẹmi Mimọ, ṣe o ri. Nitoripe Ẹmi Mimọ funraraRẹ ǹ sọrọ nipasẹ Kristi - Kristi ń dupẹ lọwọ Ọlọrun pe o ti fi awọn nkan wọnyi pamọ́ kuro loju awọn ọlọgbọn ati awọn amoye, O si ti fi wọn hàn fun awọn ọmọ ti wọn nifẹ lati kẹkọ. Nitorina, ṣe o ri, ko si ọna kankan ti a le gba lati jẹ akẹkọ gba-iwe-ẹri, ko si ọna ti a le fi da ijọ ẹlẹkọ adamọ silẹ; ọna kan ṣoṣo ni o wa ti a le fi tọ́, eyi ni ti Ẹmi Ọlọrun ba n dari wa. Ati iriri ti o ba ni gbọdọ ba Ọrọ naa mu, ṣe o ri, lẹhin naa eyi wà ni ibamu. Ṣe ẹ ri?

24 Gẹgẹ bi igbati a de ibiyi ni iṣẹju diẹ nisisiyi, a n ba awọn eniyan sọrọ ti wọn jẹ awọn miran ninu wọn jẹ alakatakiti onigbagbọ Kalfini, awọn miran jẹ alakatakiti onigbagbọ Amini, ati oriṣiriṣi ọna miran. Nisisiyi, nigba gbogbo ni awọn, ko si bi o tị se le ge e si wẹ́lẹ́wẹ́lẹ́ ni fẹlẹfẹlẹ to, o ni oju meji. Eyi si jẹ otitọ gidigidi. Awọn mejeeji ni o si ni akori fun ariyanjiyan.

Ṣugbọn, ohun kan wipe, nibo ni otitọ Ọrọ naa wà? Ibiti a ń bọ niyi; ibiti a rò, nipa ore-ọfẹ Ọlọrun, a le fi otitọ rẹ hàn fun ọ. Nisisiyi, ẹ jẹ ki a kan mu.... ibiyi ni mo si ti mu awọn ẹkọ-òpómúléró awọn ijọ wọnyi jade wá ti mo si kọ wọn.

25 Ẹ jẹ ki a ṣi Bibeli wa fun iṣẹju diẹ, gbogbo yin nisisiyi, ẹ jẹ ki a lọ sinu Iwe Ifihan, ori kinni, tabi Iwe Ifihan, ori kẹta-din-logun, ki a fi eleyi bẹrẹ. Ẹ jẹ ki a bẹrẹ si ni kà ki a si wa bayi nibiti awọn ijọ wọnyi ti bẹrẹ, ati awọn ti o bẹrẹ rẹ̀. Wayi o, Bibeli ti ṣe ikilọ ohun gbogbo ṣaaju, o ti ṣe ikilọ ọjọ ti a ń gbe ninu rẹ yi. Ati nisisiyi, Iwe Ifihan, ori kẹta-din-logun, ti o ba fẹ́. Mo wipe ori kẹtala, emi ko ni eleyi lọ́kàn, o wa ni.... A o ri eleyi lẹhin igba diẹ si, pẹlu. Eyi wà ninu isọtẹlẹ orilẹ-ede Amẹrika. Ṣugbọn tẹti silẹ daada bayi.

ỌKAN ninu awọn angẹli meje naa ti o ni igo meje wọnni si wa, o si ba mi sọrọ, wipe,.... Wá nihin, emi o si fi.... idajọ, àgbèrè nla ni ti o joko lori omi pupọ hán ọ.

Wayi o ranti, eleyi dún leti bi ohun ti o ṣajeji, bayi, obinrin onibajẹ yi. Nisisiyi, ti a ba fẹ kẹkọ ninu eyi, o ni lati ṣe iwadi ni akọkọ ohun ti awọn àmì wọnyi tumọ si. Bayi, obinrin kan, ninu Bibeli, o duro fun "Ijọ." Awọn melo ni o mọ eleyi? A jẹ iyawo kan, ijọ jẹ iyawo kan.

26 "Wa nihin Emi yoo si fi idájọ́." Nisisiyi, idajọ kan yoo wà ti a o sọ sori agbere nla naa, obinrin alaimọ naa ti o joko lori omi pupọ. Nisisiyi, obinrin naa ti o duro fun ijọ, ati omi ti o duro fun awọn eniyan. Nisisiyi, ti o ba se akiyesi yi, wo ẹsẹ karun-din-logun pẹlu nigbati o si wa nibẹ. Ẹsẹ karun-din-logun, ori kannaa.

O si sọ fun mi wipe, omi naa ti iwọ ri, nibiti agbere naa joko le lori, oun ni awọn eniyan.... ọpọlọpọ eniyan.... awọn orile-ede, ati oniruru ede. [Ṣe ẹ ri?]

Nisisiyi, ijọ nla yi, obinrin nla yi, ranti o jẹ obinrin onibajẹ. Ti obinrin ba si duro fun ijọ naa, ti ijọ Kristi si jẹ iyawo, iyawo mimọ, lẹhin naa nibiyi ni obinrin alaimọ wa. Eleyi yoo jẹ alaimọ, ti o n díbọ́n pe iyawo ni oun jẹ. Ṣe ẹ ri? Bayi, ati kini ohun ti o ṣe? O joko lori, tabi, "O ga jù ú lọ." O tumọ si "O tẹ gàba lori rẹ" omi pupọ. Ni ọ̀rọ̀ miran, o ni agbara ni gbogbo orilẹ-ede ati oniruru ede ọpọlọpọ eniyan. O jẹ ẹni nla kan, ẹniti obinrin yi jẹ.

27 Wayi o, ẹniti gbogbo ọba aye ti bạ se àgbèrè....

Lati,.... gbogbo ọba aye ti ba ṣe àgbèrè.... awọn ọkunrin ọlọ́rọ̀, awọn ọkunrin olókìki, ti ba a ṣe. Bawo ni iwọ yoo ṣe.... bawo ni ọba kan yoo ṣe ba ijọ kan ṣe àgbèrè? O jẹ agbere ti ẹ̀mí. Ti ẹ̀mí..... kini agbere? O jẹ, o dara, o jẹ ki obinrin maa ṣe aláìṣòotọ́ si ọkọ rẹ. O n gbe pẹlu ọkunrin miran nigbati o si ni ọkọ kan. Ati ijọ yi,

lẹhin naa, ń dibọn pe iyawo Kristi ni oun jẹ, nigbati o ń ba awọn ọba aye ṣe agbere - pẹlu ìgbésí-ayé aimọ rẹ̀, ifẹnujẹwọ aimọ. Oo, eleyi jinlẹ o si ni ọrọ̀ nla. Mo kan nifẹ Ọ̀rọ̀ naa.

28 Bayi ṣe akiyesi.... Ẹniti awọn ọba aye ba ṣe agbere, ti a si ti fi ọti-waini àgbèrè rẹ pa awọn ti n gbe inu aye.

"Ọti waini," rẹ ohun ni ohun ti o fi sita, agbara ti-ń-pani ninu ọti waini rẹ. "Awa ni ijọ naa! Awa ni ẹniti o ni i i" Ṣe ẹ ri? Nisisiyi, kan ko eleyi sinu ọkàn rẹ bayi. Eyi dara.

Nitorina a gbe e.... Wayi o angẹli naa sọ fun Johanu, "Emi yoo fi idajọ ti o ń bọwa si ori ijọ nla naa hàn fun ọ." Nisisiyi ṣe akiyesi.

Nitorina o gbe mi ninu Ẹmi lọ si aginju: mo si ri obinrin kan o joko lori ẹranko alawọ ododo kan.... Awọ òdòdó ninu Bibeli tumọ si "Ohun ọ̀wọ̀. Aládé." Awọ ododo naa tumọ si "Pupa". Ati pe ẹranko duro fun "agbara." Ṣe ẹ ṣe akiyesi pe ẹranko naa jade latì inu òkun? Eyi jẹ.... Ninu Iwe Ifihan, ori kẹtala.... ati nigbati o ba ri ẹranko naa ti o ń ti inu òkun jade wa, o tumọ si pe agbara yi jade wa lati aarin awọn eniyan, ṣugbọn ninu Iwe Ifihan ori kẹlala, nigbati aguntan naa jade wa, o jade wa lati ori-ilẹ-aye - ko si eniyan nibẹ, orilẹ-ede Amẹrika. Ṣugbọn lẹhin ti o ti ni iwo kekere meji, agbara ti ijọba ati agbara ti ijọ. Ati lẹhin naa o gba agbara o si ń sọrọ bi i dragoni ti o wa ṣaaju rẹ ti ṣe. Nitorina o ni lati kọ eyi silẹ. A n bọ wa sinu inúnibíni tị esin gẹgẹ bi ohun kan naa ti wọn ṣe ni Romu alaigbagbọ ni ọpọlọpọ ọdun sẹyin, nitoripe o jẹ "Bayi ni Oluwa wi." Bayi kini.... "O joko lori ẹranko kan." Agbara kan.

29 Ṣe o ṣe akiyesi Rebeka? Nigbati Eliezari ri i o jẹ ni akoko aṣalẹ, o si fun ibakasiẹ ni omi. Nitoripe Eliesari sọ wipe, "Ti omidan naa ba wa ti o si fún awọn ibakasiẹ ni omi, oun ni yoo jẹ.... ti yoo si fun mi ni omi.... ẹni yi ni yoo jẹ ẹniti Iwọ ti yàn, Oluwa, lati jẹ iyawo fun iranṣẹ Rẹ Isaaki." Ati ki o to di pe o gbadura tan, Rebeka wa o si fa omi o si fun ni omi mu, o si fun awọn ibakasiẹ naa ni omi. Ṣe akiyesi, awọn ibakasiẹ naa jẹ ẹranko. Ati ẹranko kannaa yi ti o fun ni omi ni ẹranko naa ti o gbe e lọ si ọdọ ọkọ rẹ, Isaaki.

30 Ati ni oni yi, agbara ti Ẹmi Mimọ ti ijọ bu omi rin ti o si jọsin fun ni yoo gbe e kuro ni aye yi ti yoo si pade Ọkọ iyawo naa. Dajudaju Isaaki wa ni ori pápá ni irolẹ. A ko ni pade Oluwa lókè ninu Ògo. Efesu, ori karun-un, sọ wipe a o pade Rẹ ni oju ofurufu. Oo, eleyi jẹ ki awọn ara ijọ eleto ki o mura silẹ lati kigbe. Ẹ kan ronu nipa rẹ̀! Ṣe ẹ rii? Oluwa naa.... Isaaki ti jade wa lati ile baba rẹ, o si wà si ori pápá, nigbati o ri Rebeka ti o ń bọ lori ibakasiẹ, o si fẹran rẹ ni igba akọkọ ti o ri i. O si fò kuro ni ori ibakasiẹ o si sare lati lọ pade rẹ. Eyi jẹ otitọ ibiyi ni a ti pade Oluwa. Ati ibakasi naa ti o bomi rin ni o gbe lọ si ọdọ ọkọ rẹ. Ati agbara naa ti ijọ ń jọsin fun, eyiti aye n pe ni alakatakiti, eyiti ijọ n sin, oun ni agbara kannaa ti yoo gbe ijọ lọ pade Oluwa ninu afẹfẹ. Ẹmi Mimọ naa, ṣe ẹ ri. Ohun ni ....

Ati, wo o, Rebeka jẹ wundia kan.

31 Obinrin yi si jẹ asẹwo kan, ẹniti a n sọrọ nipa rẹ nibiyi.

Nisisiyi, ṣe o mọ ohun ti agbara naa jẹ bayi? Agbara naa, ohun ti o jẹ, pe ẹranko naa, o wa ni ori àwọ̀ ododo..... Nisisiyi, iru ẹranko wo ni yoo jẹ? Olododo, eyi yoo jẹ, ohun ti o ni agbara. Iru ijọ wo ni eyi yoo jẹ nisisiyi? O jẹ ijọ ti o lọ́rọ̀, ti o sit obi, ti o si lagbara. O jẹ ijọ ti o tobi ti o si jẹ ijọ ti o ni agbara, o ni.... o ni isapa lati gba ọ̀gọ̀rọ̀ èrò ati gbogbo eniyan. Ati awọn ọba aye tị se agbere tị emi pẹlu rẹ. Awọn ọkunrin alagbara aye niyi. Nisisiyi a o ri ẹni ti o jẹ ni iṣẹju kan, ki a sị se awari awọn ijọ ẹlẹkọ adamọ wọnyi.

A si wọ obinrin naa ni aṣọ elese-aluko [bi i Ọba], O wọ aṣọ elese-aluko ati aṣọ ododo.... a ṣe e lọsọ pẹlu wura ati okuta iyebiye.... ati peril, o ni ago wura kan ni ọwọ́ rẹ ti o kún fun irira ati fun ẹgbin agbere rẹ.

Kini ohun ti o wà ni ọwọ rẹ? Ẹkọ-opomulero rẹ, ohun ti o dimu fun awọn eniyan. "Awa ni ijọ naa! Awa ni eyi!" O si jẹ ki awọn Ọba ayé mu amupara pẹlu rẹ bi eleyi. "Awa ni niyi! Awa ni agbara nla naa! A n gba gbogbo orilẹ-ede! Awa ni ijọ nla julọ naa ti o wà. Ẹ jẹ ki a lọ, wa mu ninu wa.... Nibiyi (da diẹ lara rẹ silẹ) iwọ gbà á, iwọ gbà á" Ohun niyi, ṣe ẹ ri, "o si wà ni ọwọ rẹ̀ ago kan."

32 Wo o. A si wọ aṣọ alawọ elese-aluko ati alawọ ododo fun obinrin naa.... a ṣe é lọsọ pẹlu wura ati awọn okuta iyebiye ati awọn pearli, o si ni ago wura ni ọwọ́ rẹ ti o kun fun ẹgbin ati irira àgbèrè rẹ̀.

Bayi ẹ̀yin ọrẹ, a ko ka iwe-iroyin ojoojumọ, a n ka Ọrọ Ọlọrun ayeraye ati olubukun. Gbogbo ọrun ati ayé yoo kọja lọ, ṣugbọn ọrọ naa yoo wà titi! Eyi jẹ otitọ.

Ati ni ori rẹ̀ ni a kọ orukọ kan si.... [ni a kọ orukọ kan si, dipo], OHUN IJINLẸ, BABILONI NLA, IYA AWỌN PANṢAGA ATI AWỌN OHUN ÌRIRA AYE.

33 Wayi o, ni ibiyi ni ọjọ diẹ sẹyin, emi ko ro pe si ijọ yi nibiyi, ṣugbọn mo waasu lori akori kan, "Ọwọ naa lara ogiri." Mo si sọ itan nipa ibẹrẹ Babiloni, Nisisiyi, gbogbo eto iṣejọba ti o ba wa laye, gbogbo ẹ̀sin ati

gbogbo ètò-iṣejọba, ti o si wa ni aye ni oni, o bẹrẹ ni Gẹnẹsisi. Bayi, ti o ba mu iwe ti Hislop kọ nipa Awọn Babiloni Meji, ti o ba fẹ ṣe iwadi rẹ ninu itan, tabi lati inu awọn iwe ti a kọ wọnyi ti o dara, o le ri orisirisi eto iṣejọba ti o ba fẹ nibẹ. Emi yoo mu yin lọ sibẹ ni iṣẹju diẹ nipa awọn oniwaasu obinrin, ṣe ẹ ri, ki n si fi hàn fun yin ibiti o ti kọkọ bẹrẹ, ṣe ẹ ri, ni Jẹnẹsisi. Ati lori awọn oriṣiriṣi nkan, bi wọn tị se jade wa ni Jẹnẹsisi. Jẹnẹsisi tumọ si "ibẹrẹ naa". Awọn melo lo mọ pe eyi jẹ otitọ? Jẹnẹsisi jẹ ibẹrẹ. Nitorina, gbogbo ohun ti a ni ni o ni íbẹ́rẹ̀.

34 Nigbati mo ba wo igi kan. Mo ti wà ninu aginju fun bi i ẹẹmeji, ẹẹmẹta a fẹrẹ tó bi i oṣù meji. Mo ri igi kan, bi o tị se rẹwa tó. Mo ri i, o lọ si ilẹ, omiran lọ si oke, ni`ayè rẹ - iye ti ko lopin. Mo si rò nipa eleyi. Ṣugbọn ni ibikan igi yi ni ibẹrẹ. O ni lati ni ibẹrẹ. Ati ọna kan ṣoṣo ti o le e gba lati jẹ igi kan (tabi ki o jẹ igi óòkù kan, tabi igi bíìṣì kan tabi igi popúlà, tabi igi ọ̀pẹ, tabi eyikeji ti o le e jẹ), ọgbọn nla kan ni lati wà lẹhin èyí. Tabi ti o ba si jẹ wipe igi Ooku kan ni o wa, jẹ ki ohun gbogbo ti o wa ni aye jẹ igi ooku. Ṣugbọn ohun nla kan, ọgbọn nla kan, ni lati ṣètò gbogbo rẹ. Ogo ni fun orukọ Rẹ Mimọ!

Ohun ni o ṣeto oṣupa ati irawọ ninu awọn ẹda ina oju-ọrun. O ṣeto ohun gbogbo! Yoo maa yipo gẹgẹ bi o ti fẹ ki o yipo - si iha-oòrun, si ìwọ̀-oorun, si iha-ariwa, tabi si iha gúusù, tabi ohunkohun ti o wù ki o jẹ́ - Nigbati a ba mu gbogbo awọn èrò ijọ-ẹlẹkọ adamọ wọnyi kuro ninu ọkan wa ki a si sọ gbogbo ara wa patapata si Kalfari. Oun yoo ṣeto gbogbo rẹ, ti awa ba le jọwọ́ ara wa silẹ gẹgẹ bi awọn igi wọnyi ati awọn ẹda Rẹ miran. Iwọ ko ti ri òṣùpá ki o sọ wipe, "Emi ki yoo ràn ni aṣalẹ yi, ẹyin íràwọ̀ ẹ tàn dipo mi." Ṣugbọn awa-rara, a yatọ, ṣe ẹ ri.

35 Wayi o, Babiloni, wo bi Babiloni ṣe farahan. O farahan ni ibi àkọ́kọ́ ninu Bibeli. O fi ara han ni aarin Bibeli. O si fara han ni igbẹyin Bibeli. Nisisiyi ohun kan wa.... Bayi, o bẹrẹ pẹlu Nimurọdu. Nimurọdu ni o da Babiloni silẹ ni afonifoji Shinar, o sunmọ aarin odo meji odo Tigrisi ati odo Efarate, odo Efarate si sàn kọja. Ati bi gbogbo ọna ni ilu naa ṣe lọ si Babiloni. Ati ọkọọkan ninu awọn ilẹkun ibode ti o wà jẹ bi i ẹsẹ-bata igba ni fifẹ, a ṣe awọn ilẹkun ibode naa pẹlu idẹ. Ati nigbati o ba wọ inu ilu Babiloni, gbogbo òpópónà ni o lọ taara si ibi ìtẹ́ naa.

36 Bayi, o le lọ si ilu Romu loni, gbogbo ọna ni o lọ si ilu Romu. Ati ni gbogbo awọn igun ti o wa ni oju ọna ni a gbe Maria kekere joko si, ni igun a ti yà si oju-ọna, pẹlu Kristi ọmọ-ọwọ ni, ọwọ rẹ ti o n tọka si ọna ti o lọ si Romu. Ṣe ẹ ri? O farahan ni ibi akọkọ ninu Bibeli. O farahan ni aarin Bibeli, ati ni ibiyi ni ibi ti o gbẹyin ninu Bibeli. Nisisiyi mo fẹ ka siwaju fun iṣẹju diẹ, ki ẹ le loye ipinlẹ eyi, ṣe ẹ ri. Eyi dara.

Mo si ri obinrin naa [nisisiyi ṣe akiyesi ijọ, nigbati o ba ri obinrin, iwọ kan ronu nipa "ijọ". Ṣe ẹ ri].... Mo ri obinrin naa ti o mu ẹjẹ awọn ẹni mimọ yó....

Bayi, nibo ni ọrọ naa ti a n pe ni Ẹni-Mimọ ti jade wá? Ọrọ naa ti a n pe ni Ẹni Mimọ jade wa lati inu ọ̀rọ̀ "Eniyan Mimọ" tabi "Eniyan ti a sọ di Mimọ" - Ẹni Mimọ. Eyi dara.

37 Mo si ri obinrin naa mu ẹjẹ awọn ẹni mimọ ni àmuyó....

Nisisiyi, ti obinrin yi ba jẹ ijọ, o ṣe inunibini si awọn ẹni mimọ. O si jẹ ijọ ti o ga julọ, o ni gbogbo agbara lori aye. O joko lori omi pupọ, oun si ni awọn ọba aye ti bạ se agbere. O dara, tani ẹniti obinrin yi jẹ? O jẹ ijinlẹ kan. Bayi Ẹmi yoo.... Ṣe o mọ, o yẹ ki ẹbun ẹmi mẹsan wa ninu ijọ: fun ọkan ọgbọn, fun ẹlomiran oye, ati fun ọkan iwosan, ati fun ọkan ati bẹẹbẹẹ lọ.

..... ati pẹlu ẹjẹ awọn ajẹriku Jesu....

O dabi pe wọn ko bikita pupọ fun ohun ti Jesu sọ, o jẹ ohun ti ijọ sọ. Eyi jẹ otitọ. Bayi o si ti ri, pẹlu.

38 ..... ati nigbati mo ri i. O jẹ iyalẹnu nla fun mi.

"Ẹnu ya mi gidigidi. O jẹ ohun iyalẹnu nipa rẹ, o yami lẹnu gidigidi bi o tị se...." Bayi jẹ ki emi kan gba ipò Johanu ki n si ṣi eyi fun igba diẹ, ṣe ẹ ri. Johanu sọ wipe, ibiyi ni o joko si. O ń dibọn pe ijọ Kristẹni ni oun jẹ. O ni agbara si gbogbo owo agbaye. O ni gbogbo awọn ọba aye ni abẹ ẹsẹ rẹ. O jẹ ọlọ́rọ̀, o si ni orisirisi àwọ̀ ti o dara. Bawo ni yoo ti ṣe mu awọn ajẹriku Jesu ni amuyo? Bawo ni yoo ṣe ṣe inunibini si awọn ẹni mimọ? Bawo ni yoo ṣe pa awọn ajẹriku Kristi, ati sibẹ ti yoo si maa jẹwọ pe Kristẹni ni oun jẹ, Ijọ Kristẹni kan?"

39 Bayi ṣe akiyesi.

Angẹli naa si sọ fun mi pe, kilode tị enu fi ya ọ? Emi yoo sọ ti ijinlẹ obinrin naa fun ọ, ati ti ẹranko ti o gùn, ti o ni.... ori meje ati iwo mẹwa.

Wayi o, eleyi kan jẹ kika lasan nibiyi nisisiyi. Ṣe oye eyi ye yin, eleyi yoo rọrun pupọ.

Ẹranko ti iwọ ri ni, o ti wa, ko si si mọ́: yoo si ti inu ọgbun goke wa, yoo si lọ sinu ègbé: ẹnu yoo si ya

awọn ti n gbe ori-ilẹ-aye, orukọ awọn ẹniti a ko ti kọ sinu iwe ìyè lati ipilẹṣẹ aye;.... nigbati nwọn n wo ẹranko ti o ti wa, ti ko si si mọ, ti o si n bọ wa.

Wayi o, eleyi yoo gùn wa lara nisisiyi, nitorina ohun niyi. O wipe, ṣe akiyesi bayi, pe nigbati gbogbo, ko ki n ṣe awọn diẹ, ṣugbọn gbogbo awọn ti o wa lori ilẹ aye ni yoo yà lẹnu, gbogbo wọn ni yoo jẹ iyalẹnu fun, ẹnu yoo si ya gbogbo awọn ti o wa ni ori-ilẹ-aye nipa obinrin yi. Ṣugbọn ẹgbẹ́ kan yoo wa tị enu ko ni ya wọn nipa rẹ, awọn si ni awọn ti orukọ wọn wa ninu Iwe Iye ti Ọdọ aguntan.

40 Bayi, ẹ jẹ ki emi sọ eleyi pẹlu bi mo tị se n sọrọ nipa rẹ nisisiyi, nitoripe a de ibẹ ni iṣẹju diẹ si. Ṣe ẹ ri? Nigba wo ni a kọ orukọ wọn sinu Iwe Iye Ọdọ-Aguntan? Nigba wo ni a kọ ọ? Ni igba isọji ti o kọja ti wọn lọ. Ni alẹ ọjọ ti wọn lọ si ori-pẹpẹ. Ni alẹ ọjọ ti wọn darapọ mọ ijọ. Emi ko fẹ mu yin binu, ṣugbọn, emi ń sọ fun yin, Bibeli sọ wipe a kọ orukọ wọn sinu Iwe Iye Ọdọ Aguntan “lati ipilẹṣẹ aye.” Bẹẹ gẹlẹ ni o ri! Nigbati Ọlọrun, ni ibẹrẹ ri wipe Oun yoo rán Ọmọ Rẹ, ti yoo si gba ipo ẹlẹṣẹ, nigbati a ta ẹjẹ Ọmọ Ọlọrun silẹ, Bibeli sọ wipe a ta ẹjẹ Rẹ silẹ ṣaaju ipilẹṣẹ aye. Ẹni melo ni o mọ wipe Bibeli sọ eyi, pe a ta Ẹjẹ Kristi silẹ ṣaaju ipilẹṣẹ aye? Nigbati a ta ẹjẹ yi silẹ, gbogbo ẹya ara ti ara yi, ni a kọ orukọ wọn pẹlu ẹjẹ naa sinu Iwe Iye ti Ọdọ Aguntan ṣaaju ipilẹṣẹ aye. Kini ohun ti o n ba ọ lẹru? Oo, arakunrin! Eleyi ṣi ilẹkun naa, ṣe ko ha ri bẹẹ bi?

41 O dara, nisisiyi, ẹ jẹ ki a ka eyi nibiyi, boya ohun ti a sọ yi jẹ otitọ, ṣe ẹ ri. “Angẹli naa si sọ fun mi, kilode ti....?” Mo gbagbọ pe ẹsẹ kẹjọ. “Ati ẹranko naa ti iwọ ri....” Gbogbo rẹ dara, ohun niyi.

Ẹranko naa ti iwọ ri, wipe o wa, ti ko si si mọ ti yoo si ti inu ọ̀gbun goke wa [bayi, a o pada wa si eleyi, ṣugbọn mo fẹ mu omiran, nitoripe a n lọ lori rẹ], yoo si lọ sinu ègbé: ẹnu yoo si ya awọn ti o n gbe ori-ilẹ-aye, orukọ awọn ẹniti a ko kọ sinu Iwe Iye lati ipilẹṣẹ aye.

Ọpọlọpọ ni yoo wa ni aye, ni ọrọ miran, ti a o tán jẹ, nitoripe yoo tàn wọn jẹ. Ẹgbẹ kan ṣoṣo ni yoo wa ti a ko ni tàn jẹ, awọn si ni awọn ti a kọ orukọ wọn sinu Iwe Iye lati ipilẹṣẹ aye. A o de ibẹ̀ laipẹ yi.

42 Wayi o, ṣe akiyesi, obinrin naa, ijọ naa, o jẹ Babiloni Ijinlẹ. A ri wipe o farahan lati ipasẹ Nimurọdu. Kini ohun ti Nimurọdu fẹ ṣe? Nimurọdu dá ilu kan silẹ o si fipá mu pe ki gbogbo awọn ilu miran ti o wa ni ayika san ìṣákọ́lẹ̀ fun ilu naa. Ṣe a le ri ohun kanna ni oni? Ṣe ko ha si iru ibi bayi ni oni yi? Ṣe ijọ kan kò ha wà ti o ni ìsapá lori gbogbo orilẹ èdè àgbáyé? Dajudaju. Ṣe ibikan wà loni ti o mu ki gbogbo orilẹ-ede san ìṣákọ́lẹ̀ fún un? Ṣe iru ibi bayi wà bi? Ẹ jẹ ki a tẹsiwaju ki a si kà gbogbo awọn ayọka ti o sẹ́kù ninu rẹ, niwọ̀nba, ki ẹ ba lee ni oye bi gbogbo re ṣe yẹ ki o rí. O dara.

..... ẹranko naa ti iwọ ri eyiti o ti wà.... ti kò si sí mọ́, ti o si tun wà síbẹ̀.

Ọkàn naa ti o ni ọgbọ́n niyi.

Nisisiyi, awọn melo ni o mọ̀ pe ọgbọ́n jẹ ọ̀kan ninu ẹbun ẹ̀mí? Bayi, iru ẹgbẹ eniyan wo ni o n ba sọrọ nigba naa? O ni lati maa ba ẹgbẹ awọn eniyan kan sọrọ ti awọn ẹbùn ẹmi n ṣiṣẹ ninu ijọ naa.

..... eleyi wa fun awọn ọkán ti o ni ọgbọ́n.

43 Wayi o, a ri wipe ninu gbogbo awọn ìgbà ijọ wọnyi nibiyi, ti a n fa a jade, Ẹmi-Mimọ n sọrọ sita bi gbogbo awọn ẹ̀bùn wọnyi yoo ṣe maa ṣiṣẹ ni awọn òpin ọjọ. Nisisiyi, ati ni awọn ẹ̀bùn íwosán ti o n siṣẹ. Oo, o n siṣẹ daradara. O dara, arakunrin, awọn ẹ̀bùn miran wa. Eyi kan jẹ ohun kekere kan. O dara, ẹ̀bùn kan ti o dara ju gbogbo rẹ lọwọlọwọ. Eyiti yoo jẹ ohun ti o dara julọ, ẹbun ti ọgbọn Ẹmi Mimọ ti o ni ipa lati mu gbogbo Ọ̀rọ̀ Ọlọrun papọ ki o si fi han ijọ nibiti a duro si, eyiti o ju pe a kan mu ẹnikan lara dá? Gbogbo wa ni a nifẹ lati gba iwosan; ṣugbọn o san ki a mu ọkàn mi larada ju pe ki ara mi gba iwosan lọ, nigbakugba. Oo, akiika! Gbọ́ bi Ẹmi Mimọ tị se n sọrọ lati ẹnu Johanu ni Patmọsi, o wipe, “Eyi wa fun awọn ọlọgbọn! Ẹ jẹ ki o gbọ eyi.” Bayi a n ri aworan naa fà jade bayi nibiyi.

44 Ati nibiyi ni ọkan ti o ni ọgbọn wà. Awọn ori meje naa jẹ awọn oke meje, eyiti obinrin naa joko le lori.

Ilu kan ṣoṣo ti mo mọ̀ ni aye niyi, ilu meji kan wa ti mo mọ̀, ti o ni oke meje tabi ju bẹẹ lọ ninu rẹ. Ilu Cincinnati jẹ ọkan ninu wọn, eyiti o yẹ ki o jẹ, itan asan ti ilu Cincinnati, itan ti awọn agbọnrin miran, ṣe ẹ mọ ati bẹẹbẹ lọ. Ṣugbọn o ni ju eleyi lọ ninu rẹ. Ṣugbọn ko si ijọ kan ṣoṣo ti o jẹ gaba lori Cincinnati. Ibi kan ṣoṣo ni o wa ni gbogbo agbaye ti o ni ijọ kan ti, o joko lori òkè meje, ti o si jẹ gaba lori gbogbo agbaye. Bayi, mo ṣẹṣẹ dé lati ìbẹ̀ ni, gbogbo awọn nkan wọnyi. Mo si ri nibẹ nibiti o ti sọ wipe, “Ẹniti o ba ni ọgbọn.” Iwe Ifihan ori kẹtala, “Nihin ni ọgbọn gbe wà. Ẹniti o ba ni oye, ki o ṣiro òǹkà ti mbẹ lara ẹranko naa: nitori òǹkà eniyan ni.” Ko ki n ṣe ọpọlọpọ ẹgbẹ awọn ọkunrin kan, tabi ẹgbẹ awọn ọkunrin kan, ṣugbọn ọkunrin kan. “òǹkà rẹ naa si jẹ ọtaleleẹgbẹta-o-le-mẹfa. (666).”

45 Mo ti maa n gbọ pe ni ori itẹ Popu ti Romu ni a kọ akọsilẹ yi wipe “Vicarius Filii Dei.” Mo wá ronú nipa rẹ pe ṣe eyi jẹ otitọ. Mo fa ila kan, mo si kọọ silẹ ni ti òǹkà ni òǹkà ti`edè ilu Romu, ki n si ri ni rẹ́gí. Mo sunmọ

Popu, ninu dígí. Ibi àkóso ọrun apadi, ọrun-apadi, ati ibi ìfọ̀mọ́, ṣe ẹ ri. Nitorina, awọn nkan wọnyi - mo ṣẹṣẹ dé lati ibẹ ni, mo ṣẹṣẹ dé lati ilu Romu ni mo si mọ pe eyi jẹ otitọ. Nisisiyi, a mọ bi a ti ya aworan eleyi jade.

Ati nibiyi awọn Ọba meje, awọn marun-un ti ṣubu [eyiti o wa nigba naa] ọkan si tún wa [oun si ni o wa nisisiyi.... eyiti o jẹ Kesari], omiran si tun yẹ ki o wà [eyiti o jẹ Hẹrọdu, ẹniti o buru];....

Bayi ṣe akiyesi, wo bi o tị se ri rẹgi.

..... ati nigbati o ba wá, yoo wa fun bi akoko kukuru.

Ṣe ẹnikẹni mọ akoko ti Hẹrọdu fi jọba? oṣù mẹfa. Ó wọ́ iya rẹ kaakiri ojúpópó lori igi ẹṣin kan; o si jó ilu naa, o si fi sọ ori awọn Kristẹni. O si bẹrẹ si ni sọrọ pẹlu ariwo ni ori oke kan bi wọn ti ṣe n jo ilu naa. Oṣu mẹfa. Ati pe ṣe ẹ ri, "Ati ẹranko naa...." Nisisiyi ṣe akiyesi, wo iru ọmọ buburu ti o jẹ. Ṣe ẹ ri?

46 Ṣe akiyesi.

Ati ẹranko naa ti o wa, ti ko si si mọ, paapa.... oun ni ẹkẹjọ, o si jẹ ara ekeje [iwa ẹda ti ekeje o si lọ si iparun.]

Ṣe ẹnikẹni mọ ohun ti iparun jẹ́ "Ọrun apadi." Si ṣe akiyesi ibiti o ti jade wá. Ọrun apadi. Kini ohun ti o jẹ? Ọgbun ainisalẹ. Ko si ipinlẹ fun ẹkọ opomulero ti ijọ Aguda. Ko si ayọka Bibeli fun ẹkọ opomulero ijọ Aguda, ko si rara. Wọn ko jẹwọ eyi. Alufa naa sọ ni ọjọ kan nibẹ, alufa kekere nibẹ ni ile-ijọsin ti a n pe ni Ọkàn Mimọ o wa sibẹ, O wipe, "Oo, Oun.... ." Mo n sọ fun nipa iribọmi ti Maria Elizabeth Frazer. O wipe, Oo, o ṣe iribọmi fun gẹgẹ bi ọna ti awọn ijọ Aguda akọkọ ti ṣe iribọmi."

Mo wipe, "Nigbawo ni eyi?"

O wipe, "Ninu Bibeli, Bibeli rẹ."

Mo wipe, "Ṣe ijọ Aguda ṣe iribọmi yi? Ṣe eyi jẹ ẹ̀kọ́ ti ijọ Aguda?"

"Bẹẹni."

Mo wipe, "Ninu aikuna ijọ Aguda, kini idi ti o fi yipada tó bayi?" Ṣe ẹ ri?

O wipe, "O dara, ṣe ẹ ri, gbogbo yin ni ẹ gba Bibeli gbọ́. A gba ijọ gbọ́." Ṣe ẹ ri? A ko bikita ohun ti Bibeli sọ, ohun ti ijọ sọ." Eyi jẹ otitọ. Ti iwọ bạ se ìfaga-gbága pẹlu rẹ, gbiyanju rẹ lẹẹkan, ṣe o ri. Wọn ko bikita ohun ti Bibeli sọ. Eyi ko ni ohunkohun ṣe pẹlu rẹ, wọn bikita lori ohun ti ijọ sọ. Ṣe ẹ ri?

Ṣugbọn a ko bikita ohun ti ijọ sọ, a gba ohun ti Ọlọrun sọ! Nitoripe Bibeli, a ti kọ ọ wipe, "Jẹ ki gbogbo ọrọ eniyan jẹ asán, jẹ ki ọrọ Temi jẹ otitọ." Idi niyi ti a ko fi jẹ ijọ ẹlẹkọ adamọ.

47 Nisisiyi ṣe akiyesi, tẹti si eleyi fun iṣẹju kan. "Awọn ọba marun-un, eyiti wọn ti subú, ọba marun-un." Ti o ba fẹ eleyi lati inu itan, emi yoo fi hàn fun ọ. "Ọkan si wa, ọkan si tun bọ wá." Nisisiyi, ṣe akiyesi, "ẹranko naa." Bayi, ẹranko naa ko ki n ṣe ọba kan. O jẹ ọkan to wà, ti ko si tun si mọ́, ati sibẹ o wa, ko si tun si mọ̀. Kini ohun ti o jẹ́? Awọn Popu ti wọn n gba ijọba lọwọ ara wọn, agbara kan, ẹranko kan ti o n jọba. Eyi ni nigbati a yi Romu alaigbagbọ pada si Romu ẹlẹsin. A yi si Romu alaigbagbọ pada, ati lẹhin naa o si di ijọba ẹlẹsin, eyiti o jẹ, wọn ni popu dipo ọba kan, Popu si jẹ ọba ẹmi. Idi niyi ti a fi ade de ni ori gẹgẹ bi ọba nipa ti ẹmí, o jẹwọ pe oun wà dipo Jesu Kristi. Oun niyi.

48 Wayi o ṣe akiyesi.

A o si mu ẹkọ opomulero ijọba Aguda naa jade wa lati ibẹ a o si fi han fun yin bi o ti ṣe wọ inu ijọ awọn Alagba, ṣe ẹ ri, bi o si tị se duro sinu ijọ awọn Alagba, ọpọlọpọ rẹ. Eyiti o ṣe lodi, bẹ gẹlẹ ni ori, si Bibeli - o ṣe lodi patapata. Nisisiyi, "ẹranko kan ti o ti wà, ti ko si si mọ́. Bayi ranti, gbogbo awọn ti o wa ni ori-ilẹ aye ni a o tanjẹ awọn ti a ko kọ orukọ wọn silẹ lati ipilẹṣẹ aye.

49 Ẹ jẹ ki a ri.

Ẹranko naa ti o ti wa, ti ko si si mọ [ẹsẹ kọnkọnla], ohun naa si ni ẹkẹjọ, ati.... o si ti inu awọn meje naa wa, o si lọ si iparun. [Oun yoo si tẹsiwaju titi ti yoo fi kan ọ̀gbun ainiopin ni opin irin ajo....]

Ati iwo mẹwa naa ti iwọ ri jẹ awọn ọba mẹwa, (wayi o ṣe akiyesi ni ibiyi. Ti o ba fẹ ri ohunkan ti o ṣe kókó, ṣe akiyesi eyi].... Ọba mẹwa ni o wà, ti wọn ko ti gba ijọba síbẹ̀; ṣugbọn ti wọn ti gba agbara gẹgẹ bi ọba ni wakati kan pẹlu ẹranko naa.

Wọn ko ti gba ade gẹgẹ bi i ọba, wọn jẹ apaṣẹ. Ṣe ẹ ri, wọn ko fi igba kankan gba ade gẹgẹ bi ọba,

ṣugbọn wọn gba agbara gẹgẹ bi awọn ọba, wakati kan ni ijọba ẹranko naa.

Eleyi jẹ igba apẹẹrẹ kekere ni akoko yi nisisiyi nibiti awọn apasẹ ti n dide. Ṣe ẹ ri, "Wọn gba agbara gẹgẹ bi ọba wakati kan pẹlu ẹranko naa."

Bayi o dara.

50 Wọn ni ọkàn kan, wọn yoo si fi agbara wọn ati okun wọn fún ẹranko naa.

Awọn wọnyi yoo jagun pẹlu Ọdọ-Aguntan naa, Ọdọ-Aguntan yoo si ṣẹgun wọn. [Ogo!] nitori Oun ni Oluwa awọn oluwa, ati Ọba awọn ọba: a si pe awọn ti o wa pẹlu Rè ni Àyànfẹ́ ati Olootọ. O mu mi pe ki emi bẹrẹ si ni waasu nisisiyi lori rẹ: Awọn ti a ti yàn ṣaaju ipilẹṣẹ aye, ti wọn si duro gẹgẹ bi olootọ ninu ìpè wọn. A n pè wọn ni "ayanfẹ" ati "Olootọ". Ọrọ (ati) jẹ ọrọ asopọ, ṣe ẹ ri: "ayanfẹ ati Olootọ." Wọn yoo ṣẹgun rẹ, bi wọn ti ṣe le jẹ alagbara to.

51 Ati eto iṣejọba ti a n pe ni Kọmmunisimu (gbogbo dukia jẹ ti ara ilu) ti o n lọ lọwọ loni, ẹ maṣe daamu ọkàn yin lori eyi. Eyi n ṣiṣẹ gẹlẹ lati ọwọ Ọlọrun, mo le fi idi eyi mulẹ pẹlu Bibeli yi. Yoo jẹ ki o jiya fun gbogbo awọn ajẹriku Jesu kọọkan ti o ti pa. Bẹẹni, sa. Ẹ wo gbogbo awọn ọba yi ti wọn fimọ-sọ̀kan, gbogbo wọn yoo si korira rẹ̀. Ati gbogbo awọn orilẹ-ede, gbogbo agbaye, ti wọn n lọ ninu eto iṣejọba Kọmmunisimu. Kini idi, o ni lati jẹ ọwọ Ọlọrun, lati ṣe ijiya fun u. Iwọ yoo sọ wipe, "Duro fun iṣẹju kan, Arakunrin Branham. Kọmmunisimu jẹ Ọwọ Ọlọrun kẹ̀? Bẹẹ gẹlẹ. Dajudaju, o jẹ ọwọ Ọlọrun. Bibeli sọ bẹẹ. Ṣugbọn o wà lati mù idajọ wà si ori awọn alaigbagbọ eniyan ati awọn eniyan adojutini ati ọmọ-àlè.

Kini o ku ninu aye yi? Kini ohun ti a ni?

52 Nibiyi ni ọjọ kan (Emi yoo danu-duro lori akori mi ti o ba ṣe e ṣe), mo n ka lati inu Iwe-Mimọ nibiti o ti sọ wipe Ọmọ-ale kankan kò le wọ apejọpọ ijọ eniyan Oluwa fun ìran mẹ́rìǹlá. Awọn melo ni o mọ eleyi? Eyi jẹ otitọ, Iwe Deutaronomi ori kẹta-le-logun, ọmọ àlè. Ti a ba ri obinrin kan n ìgbè (nibiti ko si àbò awọn ọkunrin nibẹ), ti ọkunrin yi si fi ipá mu obinrin naa, ọkunrin naa gbọdọ fẹ ẹ. Bi o ti wù ki o ri ti o ba pada di aṣẹ́wó, o ni lati maa gbe pẹlu rẹ titi yoo fi kú. Ti obinrin yi i ba fẹ, ti o dìbọ̀n pe wundia ni oun jẹ ti oun ko si ki n ṣe wundia, nigba naa a le pa a nitori eyi. Ti ọkunrin ati obinrin ti wọn ṣe igbeyawo ti wọn ba si bi ọmọ-àlè, oun ko le wọ ijọ eniyan Oluwa fun iran mẹrinla. Ati pe ogoji ọdun ni iran kan, yoo gba irinwo ọdun ki irú ẹni bẹẹ to le jade kuro ni Israẹli.

53 Ọlọrun korira ẹṣẹ! Bawo ni o ṣe gbero pe iwọ yoo ré ẹjẹ mimọ Jesu Oluwa kọja, nitoripe o kan jẹ ọmọ ẹgbẹ ijọ ẹlẹkọ adamọ kan, o si nireti pe iwọ yoo wọle? O gbọdọ gba ilana Ọlọrun kọja tabi ki iwọ maṣe wa rárá. Ni otitọ, Diakoni, oniwaasu, ohunkohun ti a le e jẹ, ko ni ohunkohun ṣe pẹlu rẹ. O ni lati gba ilana Ọlọrun kọja.

Iran mẹrinla. Ẹni naa ti a jijọ ṣe ijomitoro-ọrọ lori rẹ wa ni ijoko nibiyi nisisiyi. O wipe, "Bawo ni a o ṣe mọ ẹniti yoo ri igbala nigba naa?"

Mo wipe, "Nibiyi ni o yẹ ki o ti jẹ ara Kalvanisiti ni tootọ." A fi orukọ rẹ silẹ sinu ìwè ṣaaju ipilẹṣẹ ayè. Ọlọrun mu ila ẹ̀jẹ̀ naa, eyi wa kù fun Ọlọrun. Ṣe ẹ ri?

"O dara, kini ohun ti eleyi ni...."

54 Tẹti silẹ, ẹyin`ọdọ́ òní. Emi ko mọ boya o wa si ile ijọsin yi, tabi ibikibi ti o ti wa, ẹyin ọdọmọ-kunrin ati ọdọmọbinrin. Ṣe ẹ loye ohun ti ẹ n ṣe. Ti iran miran ba wa, a o da awọn ọmọ rẹ lẹjọ fun ohunkohun ti o ba se? Ṣe ẹyin ko ni ibọwọ ni tabi iwa mimọ? Ẹyin ọdọmọ-binrin ti ẹ n wọ awọn aṣọ pénpé nita nibiyi ati awọn nkan wọnyi ni ayika, ṣe ẹ mọ pe eleyi n hàn lára awọn ọmọbinrin yin? Ṣe o mọ wipe iya-iya yin jẹ ọmọ-ita, ati iya rẹ jẹ oníjó, idi niyi ti iwọ naa fi jẹ aṣẹ́wo loni? Dajudaju! Kini ohun ti awọn ọmọ rẹ yoo jẹ? Bẹẹni, sa! Ọlọrun sọ wipe oun yoo bẹ ẹṣẹ awọn obi wò lati ara awọn ọmọ, titi yoo fi dé iran kẹta ati iran kẹrin.

55 Njẹ o ni oye eyi, arakunrin mi, nigbakugba ti o ba ṣe ohun ti o dara a o bẹ̀ẹ̀wó lati ara awọn ọmọ rẹ.

Wo ibiyi, ẹ jẹ ki a wo inu Iwe Heberu, ori keje. Bibeli sọ wipe, nigbati Melkisedẹki pade Abrahamu nigbati o n padabọ lati ibi ti o ti pa awọn ọba ti o si bukun fún un ti o si sọ wipe "Nisisiyi Lefi (o n sọrọ nipa sisan idamẹwa.)" O wipe, "Lefi gba aṣẹ lati ọdọ Oluwa pe ki o gba idamẹwa lọwọ arakunrin rẹ. Ati Lefi, ẹniti o gba idamẹwa, o san idamẹwa; nitori o ṣi wà ninu Abrahamu nigbati o pade Melkisẹdẹki." Abrahamu si jẹ baba-baba-baba rẹ. Abrahamu si bi Isaaki, Isaaki si bi Jakọbu, Jakọbu si bi Lefi. Lefi, baba, baba baba, baba baba baba. Nigbati Lefi si wa ni ìhá Abrahamu, Bibeli sọ wipe, o san idamẹwa fun Melkisẹdẹki! Hallelujah!

Maṣe jẹ ki ẹnikẹni sọ fun ọ pe ètò kankan yoo wa ninu aye ti o ṣe ìdíwọ́ fun kẹkẹ Ọlọrun nla naa. O n tẹsiwaju! A ti seto rẹ sẹyin lati ibẹrẹ. Ko si èṣù kankan tabi eyikeyi èṣù bi wọn ti ṣe le pọ to ti o le ṣe idiwọ fun eto Ọlọrun.

56 Bayi, Bibeli ko sọ wipe “ni ipamọ” o san an, Bibeli sọ wipe, “O san idamẹwa” nigbati o wà ni inu baba baba baba rẹ. Ogo! Eyi ni Oluwa mi. Oo, O mọ eyi ṣaaju ki a to da aye paapa. O mọ ohun gbogbo. Ati ninu Abrahamu o san idamẹwa.

Ati arabinrin, arakunrin, bawo ni iwọ yoo ṣe sare nihin, ti awọn eniyan si n gbé ti wọn si n lọ kaakiri pẹlu iyawo ọkunrin miran, ti awọn iyawo si n tu ile wọn ká, ti wọn si n gbé bi iwọ tị se n ṣe? Kini o nireti pe iran miran yoo jẹ? Ohun ti o jẹ niyi: O ti wa di wipe ko já mọ ohunkohun mọ ayàfi ẹgbẹ́ ọmọ-àlè ti a bi pẹlu ibajẹ ti wọn si ti di ibajẹ! Ohun kan ni o ṣẹku fun un! - eyi ni ọjọ àdó-olóró ti a n gbe ninu rẹ yi. Eyi jẹ otitọ. A ti wa ni igba ikẹyin.

57 Mo joko ni owurọ yi ni ibi ori oke ilu Kentucky lọhun, ọmọkunrin kekere kan, o nira lati ri iwọn ẹsẹ bata mẹwa lati ara rẹ, o n ṣe oyin inu ìrèké, boya o fẹrẹ le ma mọ ọwọ ọtun yatọ si òsì, nigbati o gbọ́.... mo ti ronú lọ. Emi ko mọ ibiti emi wà mọ́. Mo wa ni ibi awọn ori oke ti ko ga pupọ. Mo si n lọ sibẹ lati lọ sọdẹ ọkẹrẹ. Ati nigbati mo joko ni ibi òkè nibẹ, mo bẹrẹ si ni ba a sọrọ, ọdọmọkunrin naa si sọ wipe oun fẹ lọ darapọ mọ ẹgbẹ awọn ọmọ-ogun. O si wa ri i wipe, a bẹrẹ si ni sọrọ nipa Oluwa o si sọ wipe, “Oniwaasu ṣe iwọ ko gbagbọ pe a ti wa ni ìgbà ikẹyin?” Ni ibi awọn ori-oke ni aginju!

Mo wipe, “dajudaju a ti wa ni igba ikẹyin. Dajudaju, ọmọ, a ti wa ni igba ikẹyin.”

58 Ibiyi ni a wà. Akoko ti a n gbe ninu rẹ niyi, arakunrin. A ti wa nibẹ. Ṣe iwọ ko ri bi awọn iya nigba naa, ati awọn baba, bi wọn ti ṣe gbe igbesi-aye wọn, ati awọn baba baba ati awọn mama mama? Ṣe iwọ ko ri bi baba ati mama ṣe gbé igbesi aye wọn? Abajọ ti a fi wa ninu ibajẹ loni yi! Abajọ ti o fi jẹ wipe o le waasu pẹlu gbogbo agbara rẹ wọn yoo si tun wọ aṣọ péńpé bakanna - wọn yoo si tutọ si oju rẹ. Wọn yoo si mu siga wọn yoo si tu eefin rẹ si ọ lára, wọn yoo si sọ wipe, “Koju si iṣẹ rẹ.” Kini idi? Nitoripe inu ẹ̀yà ti wọn ti wá niyi! Emi yoo de ibẹ ni taara, ninu “Iru ti Ejo.” A o ṣayẹwo ibiti o ti wọle, ṣe ẹ ri idi ti wọn fi n hùwà bi eleyi. Wọn jẹ ọmọ èṣù lati ibẹrẹ ipilẹṣẹ ayé. Eyi jẹ otitọ.

Ko si ohun miran ti a ni ti o sẹkun paapa fun u, bikoṣe idajọ nikan ni ohunkan ti o sẹkun. Ko le ni ohun miran bikoṣe idajọ. Ọlọrun yoo kan pa gbogbo rẹ̀ rẹ́, eniyan si ti ṣe eyi fun - rararẹ. Ọlọrun ko pinu pe yoo ri bayi ni ọna yi, ṣugbọn O mọ pe yoo ri bayi ni ọna yẹn. Idi niyi ti o fi sọ wipe Yoo tan gbogbo awọn ti o n gbé ni ori-ilẹ-aye jẹ, ayafi awọn ti a kọ orukọ wọn sinu iwe Iye ti Ọdọ Aguntan ṣaaju ipilẹṣẹ aye.

59 Ẹ jẹ ki a ṣe akiyesi, ẹ jẹ ki a ka siwaju diẹ si bayi. Bayi, nisisiyi mo gbagbọ pe a ti wa ni ẹsẹ̀ kejila.

Iwo mẹwa ti iwọ si ri ni ọba mẹwa ni nwọn ti n wọn ko iti gba ijọba; ṣugbọn nwọn gba ọlá bi ọba pẹlu ẹranko naa fun wakati kan.

Awọn wọnyi ni inú kan, nwọn o si fi agbara ati ọ́lá wọn fun ẹranko naa.

Awọn wọnyi ni yoo si ma aba Ọdọ-Aguntan jagun, Ọdọ-Aguntan naa yoo si ṣẹgun wọn: nitori Oun ni Oluwa awọn oluwa, ati Ọba awọn ọba; awọn ti o si wà pẹlu rẹ̀, ti a pè, ti a yán, ti nwọn si jẹ olooto yoo si ṣẹgun pẹlu.

O si wi fun mi pe, Awọn omi ti iwọ ri ni, nibiti agbere ni joko, awọn eniyan,.... ati ẹ̀yà.... ati orilẹ ati oniruru èdè ni wọ́n.

Ati ìwo mẹwa ti iwọ ri, ati ẹranko naa, awọn wọnyi ni yoo korira agbere naa....

60 Ṣe akiyesi bayi, awọn iwo mẹwa wọnyi, awọn ijọba mẹwa wọnyi. Ṣe ẹ ri, gbogbo wọn ni wọn n wọlé, ohun ti awọn apaṣẹ wọnyi jẹ́. Wo ọ̀nà ti awọn apaṣẹ wọnyi gbé ara le. Wo ohun ti wọ́n gbe ara lé? Kan sọ apaṣẹ kan fun mi ti ko gbe ara le eto iṣejọba Kọmmunisimu (gbogbo dukia ijọba jẹ ti ara ilu). Ṣe e ri? Kini ohun ti wọn yoo sị se? “Wọn yoo korira Agbere naa, obinrin naa, ijọ naa. Ṣugbọn ṣe akiyesi. Wo ibiti o n lọ. [Apapọ ọrọ ti kò jágara a].

..... awọn wọnyi ni yoo korira agbere naa, nwọn o si sọ ọ di ahoro ati ẹni ihoho, nwọn o si jẹ ẹran ara rẹ, nwọn o si fi ina sun ú patapata.

61 Wọn yoo pa ohun yi rẹ kuro ninu àwòrán aye, o daju gẹgẹ bi mo tị se duro nibiyi. Yoo gba wa ni akoko lati mu àkòrí yi nibẹ nipa ti ijọ naa, ki a si gbeyẹ̀wo ninu Iwe-Mimọ nibiti o ti sọ wipe, jẹ ki a kà á, “Gbogbo awọn ọba ayé, ati gbogbo awọn ti o jẹ ọ̀gá ọkọ̀ oju omi, gbogbo wọn ni wọn si sọ́fọ; nitori Babiloni ilu alagbara ni nitori ni wakati kan ni ìdájọ́ rẹ dé. Ati, Oo, bi o ti sọ wipe, ”Ẹ fò fun ayọ, ẹyin eniyan mimọ ati gbogbo awọn wolii mimọ, nitori Ọlọrun ti gbẹsan ẹ̀jẹ̀ awọn eniyan mimọ ati awọn arakunrin yin lara rẹ̀.“ Ṣe ẹ ri, eyi jẹ otitọ. Dajudaju, eto iṣejọba kọmmunisimu n lọ ni ibamu pẹlu ọwọ Ọlọrun; gẹgẹ bi ọba Nebukadnessari tị se mu ifẹ Ọlọrun ṣe, nigbati o wa lati mu awọn Juu, nigbati wọn rin lọ ni ìhòhò.

62 Ati ẹṣẹ le maa tẹsiwaju lati ṣe ibajẹ, ìrú olododo yoo si wa nibẹ, ati irú yi yoo ma dibajẹ si, yoo si dibajẹ,

yoo si tun dibajẹ, titi yoo fi bajẹ patapata lẹhin igba diẹ. Yoo de ibikan nitoripe awọn mama wa ati awọn baba wa ati bẹẹbẹẹ lọ ti gbe igbesi aye wọn bakanna ṣaaju wa ati [apapọ ọ̀rọ̀ ti ko jágaraa]. Ko si ohun ti o ṣẹ́kù fun wa mọ́. Ṣe ẹyin si mọ ohun ti Jesu sọ? Ti Oun ko ba ge iṣẹ rẹ kuru, kò si eniyan kankan ti a o gbala.

63 Njẹ ẹ le ri. Njẹ ẹ le ri idi ti a fi ni nkan wọnyi? Emi ko sọ afikun ọrọ. Ọgbẹẹni Arthur Godfrey ati gbogbo eniyan, ṣe ẹ mọ̀, ẹniti o jẹ Elvis Presleys, ati ti o wọ aṣọ awọleke ti a fi n sisẹ eyiti o tobi pẹlu irun ori rẹ ti o dà silẹ ni ọrùn rẹ ati awọn ọdọ ti wọn hùwà ni gbogbo ọ̀nà wọnyi - kini ohun ti o ṣe yi? Kini ohun naa? Nitori wipe o n jade wa lati ọdọ awọn ẹgbẹ ọmọ-àlè eniyan, 'ti wọn ti gbé saajù wa,“ Ko si ohunkohun to kù mọ́. Oo, wọn yoo dide, wọn yoo si kọ ”N o sún mọ Ọ Ọlọrun,“ gẹgẹ bi Ọgbẹẹni ti o maa n ṣa ẹ̀wa naa Ernie ati gbogbo iru awọn eniyan bi eleyi, wọn yoo kọ iru orin mimọ kan, ati bẹẹbẹẹ lọ bi iru eleyi. Arakunrin, ṣe o mọ ohunkan? Eyi jẹ àgàbàgebe pọ́nbélé! Bẹẹni sa.

64 Awọn ọkunrin ti o maa n kọ orin taka-sufe nita ati ijọ aye ati iru nkan wọnyi ko ni ohunkohun ṣe lẹhin aga iwaasu. Wọn ko ni ohunkohun ṣe rara bi o ti wu ki o kere to ni ẹyin ibiyi. Eleyi wa fun awọn alufa, awọn ti Ọlọrun ti pe. Awọn ojiṣe Ọlọrun ti a pè ni o yẹ ki wọn wà ni ẹyin ibiyi. Ẹyin ibiyi ko si fun iru nkan bi eleyi.

Ohun ti o ṣẹlẹ pẹlu rẹ ni oni niyi, wọn ti sọ ijọ di ẹgbẹ kan. Ẹgbẹ kan dara. Ti iwọ ba fẹ ṣe bẹẹ, eyi kù si ọ lọwọ. Ṣugbọn jẹ ki n sọ fun ọ, iyatọ nla ni o wa laarin ẹgbẹ kan ati ijọ jan. Bẹẹni, sa. O fẹ ṣe awọn nkan wọnyi ninu ẹgbẹ kan, ki o si ni oriṣiriṣi awọn àsè ati bẹẹbẹẹ lọ, èyí ku si ọ lọwọ. Ṣugbọn, arakunrin, o yẹ ki a gbá ijọ lati ori ibi aga iwaasu, titi dé ibi àjà ilẹ̀ ilé. Eyi jẹ otitọ! Emi ko sọ wipe ki a gba oju ferese tuntun ati bẹẹbẹẹ lọ, ohun ti mo n sọ ni isọji ti atijọ ti Ọlọrun rán wá ti yoo fọ ọ lati odi kan si odi keji. Bẹẹni, sa. Gẹgẹ bi igba ti a ba tan iná, iná ẹlẹtriki, sí ọpọlọpọ kokoro, aayan ti wọn wa yika eso apulu. Bẹẹni, sa, wọn yoo tuka nigbati ina ba tàn.

65 Nisisiyi ṣe akiyesi, “Wọn ni ọkan kan, wọn fi agbara wọn fún.... Mo wa ni isalẹ rẹ bayi, ”Awọn iwo mẹwa.“ Bẹẹni, nisisiyi.

Nitori Ọlọrun ti fi si inú ọkan wọn lati mu ifẹ Rẹ ṣẹ. [Ati bẹrẹ si ni lọ bayi], ati lati wà ni isọkan ki wọn ki wọn si fi ijọba wọn fun ẹranko naa, titi yoo fi di igba ti awọn Ọ̀rọ̀ Ọlọrun yoo fi wa si imuṣẹ.

Wayi o, ati obinrin naa ti iwọ ri ni ilu nla naa, eyiti o jọba lori gbogbo awọn ọba ayé.

Bayi, ko si ìdí ti o yẹ ki a fi maa rin kaakiri mọ́, a mọ wipe awọn ipo ijọ Aguda ni o jẹ́. Ko nilo ẹnikẹni.... Mo gba eyi gbọ gẹgẹ bi emi tị se gbagbọ ni tootọ pe mo ti gba Ẹmi Mimọ, mo gba eyi gbọ́, ni otitọ gẹgẹ bi mo ti gbagbọ gẹlẹ pe mo jẹ Kristiani ti o duro nibiyi ni oni, pe awọn ipò ijọ Aguda ni.... Ilu Vatican naa ohun ni ilu naa ti o joko si ori awọn oke meje. Awọn ipo ijọ ni ẹranko naa ti o ti wa tẹlẹ, ti ko sí sí mọ́. Oun ni Babiloni. Gbogbo rẹ ni a ṣe apẹẹrẹ rẹ patapata, ninu gbogbo awọn Iwe Mimọ - O jẹ ijọ Aguda.

66 Wayi o, ohun ti yoo yà yin lẹnu niyi bayi. Iwọ sọ wipe, “O dara, iwọ ko sọrọ nipa mi, Arakunrin Branham,” ṣugbọn jẹ ki emi kàn bere ohunkan ni ọwọ rẹ. Ẹ jẹ ki a lọ si ẹsẹ̀ karun-un taaara.

Ati ni ori rẹ.... ni a kọ ọ si wipe, OHUN IJINLẸ BABILONI NLA, IYA AWỌN PANṢAGA ATI AWỌN OHUN IRIRA.... AYE.

Kini ohun ti o jẹ? A-g-b-e-r-e. O si jẹ I-y -a. Kini? I-Y-A, o ti bi ohun kan. Iya awọn ọmọ ọkunrin? Ṣe ti agbere naa! Kini agbere tumọ si? O ri bakanna pẹlu irira, obinrin onibajẹ. Kini ohun ti o sọ ọ di ohun irira? Ẹkọ òpómúléró rẹ̀. O n dibọn pe ijọ Kristẹni ni oun jẹ, ṣugbọn o n kọni ni ẹkọ atọwọda eniyan. Ati nibiyi O sọ wipe Oun ni.... ti o ba jẹ wipe oun ni ẹgbẹ ti a fi ọgbọn eniyan gbe kalẹ̀ àkọ́kọ́, lẹhin naa yoo dabi pe awọn ẹgbẹ ti a fi ọgbọn eniyan gbe kalẹ miran jade lati inu rẹ̀. Oun ni ìyá awọn agbere gbogbo. Ṣe eyi jẹ otitọ? Iya awọn agbere gbogbo. Ṣe ko ha jẹ iya, nisisiyi, iya awọn ọmọ ọkunrin. Ṣe ko ha jẹ iya awọn.... O ni lati jẹ ìyá awọn obinrin. Ti wọn ba si jẹ awọn obinrin wọn yoo jẹ awọn ijọ. Nisisiyi ẹ jẹ ki a ṣe iwadi. Ohun ti o jade lati inu....

67 Ẹgbẹ wo ni ẹgbẹ akọkọ ti a fi ọgbọn eniyan gbé kalẹ? Ijọ Aguda. Ẹgbẹ wo ni ẹgbẹ ti a fi ọgbọn eniyan gbé kalẹ ekeji? Ijọ Luther. Ẹgbẹ wo ni ẹkẹta? Ẹgbẹ Zwingli. Kini ohun ti o wá parada si? Ijọ Calvin, o si wa parada si ijọ Angliikani, ati ijọ Angilikani si parada si ijọ Mẹtọdisiti. Ijọ Mẹtọdisiti naa, kini ijọ mẹtọdisiti mú jade? Lati ibẹ ni Alexander Campbell ti jade wá. Lati ara Alexander Campbell ni John Smith ti jade wá. Lati ara.... Alexander Campbell ni ijọ ti a n pe ni Ijọ Kristẹni ti jade wa, lẹhin naa wọn ni bi i mẹrin tabi marun-un, ijọ ti a n pe ni ijọ Kristi ati lẹhin rẹ ni a ti ni gbogbo awọn eto iṣejọba kekere ti o jẹ ẹkọkẹkọ ti jade wá. Lẹhin eyi ni a wa ni ijọ Onitẹbọmi, ohun tun ni oriṣiriṣi awọn ti o jade lati inu rẹ kékèké. Lati inu ijọ Mẹtọdisiti ni ìjáde.... lati inu ijọ Mẹtọdisiti ni ijáde, akọkọ, ni awọn ti o gbagbọ ninu ojiṣẹ Ọlọrun Wesley ti wọn si jẹ ọmọ ijọ Mẹtọdisiti (Wesleyan Mehodist) ti jade wa, ati lẹhin naa wọn pinya ni bi i igba mẹrin tabi igba marun-un. Lẹhin naa wọn tun da ijọ Mẹtọdisiti miran silẹ, ati lẹhin naa wọn tun pinya, lẹhin naa wọn tun da ijọ Mẹtọdisiti miran silẹ ti a n pe ni ijọ Mẹtọdisiti Ominira. Ati lẹhin naa wọn da ijọ Nazerene silẹ lati inu rẹ. Lati Nazarene wọn da ijọ Àtìpó

Mimọ titi lọ. Gẹgẹ bi i awọn ẹkọkẹkọ ti ṣe n lọ bakanna, o n tẹsiwaju lọ, ọkọọkan ninu wọn jẹ oludasilẹ àkọ́kọ́ kekere nibẹ lọhun titi ti o fi n tẹsiwaju. Ati kini ẹnikọọkan wọn ṣe? Gbogbo rẹ si wá yọri si ijọ Pentikọsiti.

68 Ati kini Pentikọsti ṣe? Ohun kannaa ti iya rẹ ṣe. Wọn lọ wọn si da ẹgbẹ ti a fi ọgbọ́n eniyan gbe kalẹ. Kini ohun ti wọn wa parada si? Ijọ ẹlẹkọ adamọ kan. Lọ sinu ọkan, ohun akọkọ ni. “Kini ẹkọ opomulero rẹ?” Ọrẹ, wọn yoo fi ìyàrí ti o dara ya ọ, ṣe ẹ ri, lati le wadi ohun ti o jẹ, ati ohun ti o gbagbọ. Ati ti ohun ti o ba ni ti ko ba wa ni ibamu pẹlu tiwọn, arakunrin, a o yọ ọ kuro ni aarin wọn ni kiakia. Eyi jẹ otitọ.

Ma sị se ro pe nitoripe iwọ sọ wipe o jẹ ọmọ ijọ afi-ede-ajeji-ṣeri Ẹmi Mimọ pe o ni aabo ti o daju. Arakunrin, ọpọlọpọ awọn ọmọ ijọ Pentikọsiti ni o ti kuro ni oju ọna ti yoo si dabi pe wọn ṣi wa ni oju ọnà. Eyi dami loju. Ṣe ẹ ri?

69 Bayi, gbogbo ẹgbẹ ti a fi ọgbọn eniyan gbe kalẹ, ti wọn ba le fi aye gba ki ibukun Pentikọsiti ko sọkalẹ nikan. Ko ki n ṣe pe ki wọn da ẹgbẹ kan silẹ lati inu rẹ, ki wọn kan fi silẹ ni ipo idapọ ti ará, ki wọn si gba Ẹmi-Mimọ laaye ki o ṣe iyapa naa. Ẹmi Mimọ ni o ṣe iyapa fun

Anania, Safira wọle ni ọjọ kan, o sọ ohun kan ati ohun kan; ati Ẹmi Mimọ si sọ wipe, “Kini idi ti o fi parọ?”

Ṣugbọn a sọ wipe, “Nisisiyi, Arakunrin Jones niyi. Maṣe sọ ohun buburu nipa rẹ bayi, oun ni ẹni ti o maa n san owo julọ ti a ni ninu ijọ. Mo mọ pe o ni Ẹmi Mimọ. Mo gbọ ti o n fi ede ajeji sọ̀rọ̀ mo si ti ri ti o kigbe ninu Ẹmi rí.” Eyi ko ṣe pataki pupọ bi ìgbà ti eniyan ba da ẹ̀wà si ẹyin awọ maalu gbigbẹ ni. Ṣe ẹ ri. Ko ni ohunkohun ṣe pẹlu rẹ! Ọlọrun nikan ni O ni ohun lati sọ. Oun nikan ni o ni aṣẹ lati sọ pe, oun ni tabi oun kọ. Bẹẹ ni.

“Ṣugbọn a maa n lọ sinu ijọ ẹlẹkọ adamọ wa. Ó dára, a le jade kuro nnu ijọ Asẹmbili.” Ijọ isọkan gba a. Awọn ijọ isọkan gbé E fun igba diẹ, lẹhin naa wọn le E jade nitoripe.... Wọn gbe E lọ sibẹ, ijọ Jesu Nikan si gbé E dide. Ijọ Jesu Nikan gba A fun igba diẹ, ati lẹhin naa ohun miran ti o tún gbe E died, Ijọ Ọlọrun ti wọn tun gbe E dide. Ijọ Ọlọrun ti Isọtẹlẹ tún gbe E dide, ati isọji Tomlinson tún gbe E. Oo, akiika! Arakunrin, ṣe awa naa ko ti le E jade! Eyi wa ninu ijọ Pẹntikọsiti, isọji ti o gbẹyin.

Ati nisisiyi, wọn ni okiki, wọn si ni awọn ti o n bọ epo, wọn si ni ẹjẹ ni oju wọn. Ati, Oluwo, ṣaanu, emi ko mọ ibiti wọn tun lọ bayi. Ohun kan lẹhin eyi....

70 Gbogbo rẹ ti di ohun ibàjẹ́.

Njẹ o mọ pe Bibeli sọ wipe yoo di ibajẹ? Njẹ o mọ wipe Bibeli sọrọ nipa ọjọ oni pe yoo wa nibi, nigbati o jẹ wipe gbogbo tabili Oluwa ni o kún fun èébì? O si wipe, “Tani Emi yoo kọ ni ìmọ̀? Tani Emi yo fi òye ẹ̀kọ́ yé? Nitori aṣẹ le aṣẹ, aṣẹ le aṣẹ, ẹsẹ le ẹsẹ, ẹsẹ le ẹsẹ.” Tani Oun yoo kọ ni ẹ̀kọ́? “Awọn ẹniti a wọn ni ẹnu-omú [iya].” Ṣe ẹ ri?

71 Wayi o, ko si obinrin kan, obinrin buburu kan, ni ilu yi ṣugbọn eyiti yoo mu ọmọbinrin wundia kan jade. Bayi ni o ṣe ri nigbati a bi i. Nisisiyi o le ṣe ohun ti o dara. Ṣugbọn ti o kò ba ṣe akiyesi, pe iya rẹ ti ni iru ẹ̀da bayi tẹlẹ, ọmọbinrin naa, mẹsan ninu mẹwa, ni yoo huwa gẹgẹ bi iyá rẹ ti ri. Wayi o, o mọ pe eyi jẹ otitọ. Obinrin arugbo kan ti o kan ti o kọ́ ile rẹ pẹlu iwa-ibajẹ le bi ọmọbinrin kekere kan, o si lee jẹ ọmọ ọdun mẹrin-din-logun, ki o si jẹ mimọ ati oniwarere gẹgẹbi ẹnikẹni ninu ayé ti ṣe le jẹ, ṣugbọn - ti o ba duro ni ọna yi. Ṣugbọn ohun ti o wà nibẹ ni wipe, oun yoo lọ, yoo si hùwa gẹgẹ bi i iya rẹ.

72 Bayi, ijọ Aguda ni agbere akọkọ ti o jẹ arugbo ti o jade wa pẹlu ẹkọ opomulero ti o ṣe fun ara rẹ, igbagbọ asán - eyiti Bibeli sọ wipe, “o jade wá lati ogbun ainisalẹ eyiti yoo si pada si iparun.” Bibeli sọ eyi.

Bayi, wọn kọni pe eleyi kúnà. O kuna gẹgẹ bi Ọrọ Ọlọrun ti sọ. Ati lẹhin naa ni ijọ Mẹtọdisi de eyiti a bi lati inu rẹ, omidan binrin kekere ti o lẹ́wà, ṣugbọn kini ohun ti o ṣe? O yipada o sị se ohun kannaa ti iya rẹ ṣe. O gba ijọ rẹ laaye lati maa wọ aṣọ péńpé, o gbà wọn laaye lati maa mu siga, ki wọn maa ṣe ohun ti o wù wọn, ki wọn si maa ṣe ìfẹ́ ọkàn wọn.... Wọn ko si sọ ohunkohun nipa rẹ. Olusọ-aguntan arugbo kekere naa ti ko gba ìtọ́ni ti o duro sibẹ, ni ẹyin àga iwaasu nibẹ, ẹ̀rù n ba pé wọn ko ni san owo oṣù fun oun ni ọjọ kan - abọ akara oniyẹfun kan.

Jẹ ki n sọ fun ọ, arakunrin, o tẹ mi lọrun ki n waasu Ihinrere, ki n si jẹ akara oniyẹfun ti o ni soda ninu ki n si mu omi lasan, ki n si sọ otitọ nipa rẹ. Ti gbogbo awọn ọmọ ijọ mi ba dide ti wọn si rin jade lọ, Emi yoo sọ otitọ fun wọn. Bẹẹni, ni tootọ.

73 Kini ohun ti o ṣẹlẹ? Oo, o jẹ iwe pélébé ti a n lo lati fi gba ounjẹ. “O dara, ṣe o mọ, mo jẹ olusọ-aguntan ijọ ti o tobi julọ ti o wa ni ilu yi.” Ẹyin ara ijọ Onitẹbọmi ati ẹyin ara ijọ Metodisi, ti ẹ n tẹti si wolii èké. Bayi, eleyi le koro si eti, ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba sọ ohun ti o lodi si Bibeli yi jẹ wolii èké. Emi ko bikita bi o ti dán mọ́rán to, o jẹ asọtẹlẹ èké. Ṣe ẹ ri....

"Oo, ohun gbogbo ni o dara niwọn igbati a ba ti kọ orukọ rẹ silẹ ninu ìwé." A le kọ orukọ rẹ silẹ sinu iwe-ijọsin, ti ko ba si ninu iwe Iye, o ti ṣegbe! O le jẹ ẹniti o dara to bẹẹ gẹ́, o le jẹ olootọ ati mimọ ati ọmọluwabi bi o ti le jẹ to, eleyi ko ni ohunkohun ṣe pẹlu rẹ!

74 Esau jẹ ọkunrin ni ilọpo méji ju Jakọbu lọ, ti a ba n sọ nipa pe ki eniyan jẹ ọkunrin, o n sẹtọju baba rẹ arugbo ti oju rẹ ti fọ́ ati gbogbo nkan iyoku. Jakọbu si jẹ ọmọ-àyọ̀ kekere ni ẹ̀gbẹ́ eti aṣọ-iṣẹ iya rẹ, ọdọmọkunrin kekere ti ko loye. Ọlọrun sọ wipe, "Mo fẹran Jakọbu mo si kọ Esau." Ṣaaju ki a to bi ọkọọkan ninu awọn ọdọmọkunrin naa! Iwe Romu ori kẹjọ sọ bẹ ẹ. Eyi jẹ otitọ.

Ọlọrun mọ ohun ti o wa ninu eniyan. O si mọ ohun ti o wa ninu ijọ, pẹlu. A n gbe nipasẹ akara Iye, akara ti Ọrọ Ọlọrun. Nisisiyi, idi niyi ti a ko fi jẹ ijọ ẹlẹkọ adamọ.

75 Bayi mo fẹ fun ọ ni ohun kekere miran.... Mo fẹ fun ọ ni àpèjúwe kekere kan ti mo kọ silẹ nibiyi. "Ohun nla naa...." Ninu Iwe ifihan, ninu ori kọkan-din-logun ẹsẹ keji, mo ni ohun kan ti mo kọ silẹ nibiyi. Mo fẹ wo ki n si ri ohun ti o jẹ nisisiyi.

Nitori otitọ ati ododo ni idajọ Rẹ: nitori o ti ṣe idajọ agbere nla ni, ti o fi agbere rẹ ba ilẹ aye jẹ, O si ti gbẹsan ẹjẹ awọn iranṣẹ Rẹ lọwọ rẹ. [Eyi ni opin ijọ Aguda.]

76 Wayi o, a fẹ ki ẹ ṣe akiyesi pẹlu, nibiyi pẹlu, pe ijọ ẹlẹkọ adamọ, pe a tun ri ijọ ẹlẹkọ adamọ kan nibiyi ninu Iwe-Mimọ, pe nkan.... . . Ati pe Bibeli ko sọ ohunkohun nipa ijọ ẹlẹkọ adamọ. Ijọ ẹlẹkọ adamọ wa lati ijọ Aguda. Oun ni ìyá akọkọ ti ijọ ẹlẹkọ adamọ ati gbogbo ijọ ẹlẹkọ adamọ kọọkan jade wa lati ibẹ. Nisisiyi, eleyi yoo gún wa lara diẹ. Yoo maa gún wa lara nigba gbogbo, ṣe ẹ ri. Ṣugbọn mo fẹ ki ẹ ri wipe a ko bí ijọ ẹlẹkọ adamọ tabi pe ko ki ń ṣe eto ti Ọlọrun lọwọ si, èṣù ni o da eleyi silẹ!

Ijọ Ọlọrun ni....

"A wa ni isọkan,

Ara kan ni a jẹ́.

Ọ̀kan ninu ifẹ!"

Eyi ni ijọ Ọlọrun alaaye. Laibikita ohun ti wọn jẹ.... . . awọn nkan wọnyi, a jijọ jẹ ọkan. Eyi jẹ otitọ. Boya o jẹ ọmọ ijọ Mẹtọdisi tabi ijọ Onitẹbọmi, arakunrin, ti o ba di atunbi ti a si fi Ẹmi Mimọ kún ọ, o jẹ arakunrin mi, a jijọ n ṣiṣẹ papọ. Otitọ. Bẹẹni, Sà. Eleyi ko ṣe iyatọ kankan.

77 Mose, nigba miran le wo yika ki o si sọ wipe, "Ṣe o mọ ẹgbẹ awọn alakatakiti ijọ Pentikọsti? Arakunrin Branham, kini idi ti o fi lọ si ọ̀dọ̀ iru awọn eniyan bi eleyi?" Njẹ o mọ ohun kan? Mose wo awọn ọmọ Israẹli, oju ferese kanna ti Farao ti wo wọn ni Mose naa lò. Farao wo wọn bii ẹgbẹ awọn ti o n mọ amọ̀, ṣugbọn Mose wo wọn gẹgẹ bi ayanfẹ Ọlọrun. O mọ pe wọn ni ileri naa! Kini idi? O mọ eyi nipasẹ Ọrọ naa.

Ati nipa igbagbọ, pẹlu ẹsẹ kan si ori ìtẹ́ Farao, pẹlu gbogbo ayé ni abẹ ẹsẹ̀ rẹ (O joko nibẹ o si da ọti-waini si ẹnu rẹ, ati awọn obinrin ti o rẹwa n fẹ́ ẹ ni afẹ́fẹ́, gẹgẹ bi ọba, tabi apaṣẹ, tabi ọba gbogbo aye). Mose kekere ni ọmọ ọdun ogoji o ni eyi ni ọwọ rẹ nigbati o wo ita ti o si ri ẹgbẹ awọn ti o n mọ amọ, ṣugbọn o mọ pe oun jẹ ọkan ninu wọn. Hallelujah! Ohun niyi. O mọ pe oun jẹ ọ̀kan ninu wọn.

Ati nipa igbagbọ, ohun nikan fun rara rẹ, o yan!

78 Onikaluku ni lati ṣe iyan funrararẹ. O ni lati ṣe iyan naa bayi. Iwọ yoo ṣe iyan ni owurọ. Iwọ yoo ṣe iyan ni aṣalẹ ọla. Ti iwọ ba wa ni aaye. Iwọ yoo ni lati ṣe iyan nigba miran. Arakunrin, mo ti yan Bibeli yi gẹgẹ bi Olutumọ̀ Ọrọ mi fun igba pipẹ. Bibeli yi jẹ Iwe Ìyè mi, Bibeli yi jẹ Ọrọ Ọlọrun. Nipasẹ Rẹ ni mo fi n gbe aye. Bibeli yi ni emi yoo ṣe atilẹyin fún.

79 Nitorina Mose wo awọn ọmọ Israẹli, ko ki nṣe pe o sọ eleyi nikan, "Oo, wọn jẹ awọn eniyan ti o dara. Emi ko ni ohunkohun ṣe lodi si wọn. Oo, rara, Emi ko ni sọ ọrọ kankan lodi si wọn".... Bi ọpọlọpọ ti ṣe maa nṣe ni oni niyi. "Oo, ẹyin ara ijọ a fi-ede-ajeji ṣe-ẹri-Ẹmi Mimọ ati awọn ti o ni Ẹmi Mimọ, ati awọn ti o gbagbọ ninu iwosan lati oke-wa- - oo, emi-emi-emi ko ni ohunkohun lodi si eyi." Ṣugbọn ko ki n ṣe Mose. O kọ Egypiti silẹ O si di ọ̀kan ninu wọn! O rin laarin awọn arakunrin rẹ! O jẹ ọ̀kan ninu wọn.

80 Arakunrin, ibiti emi duro si niyi. Emi yoo duro ti awọn eniyan Oluwa ti a kẹ́gàn, bi wọn tilẹ kere tabi ohunkohun to wu ki wọn jẹ. Wọn ni ileri kan, mo si ri orukọ wọn ninu Iwe Iye Ọdọ-Aguntan. Wọn jẹ arakunrin mi. Eyi jẹ otitọ. Ṣe ìyàn rẹ ki o si duro ti wọn. O dara tabi ko dara, duro sibẹ lọnakọna. Ti wọn ba kuna, ran wọn lọwọ si ipa otitọ. Eyi jẹ otitọ. O ko ṣe wọn ni anfani nipa titi wọn sita. Ṣe ẹ ri. Gbiyanju lati fa wọn soke.

81 Charlie, gẹgẹ bi wọn ti ṣe sọ nipa Arakunrin Allen nipa ọwọ rẹ. Mo wipe, "Rara, rara ko ki n ṣe pe emi ko

bu ọla fun oniwaasu A.A. Allen.” Mo wipe, “Ti emi ba le e waasu bi oniwaasu A.A. Allen, emi ko ni ṣe isin iwosan kankan rara.” Nisisiyi, nigbati a ko ri baknanna pẹ̀ejẹ̀ lori ọwọ rẹ duro fun ìjẹ́rigbe ti Ẹmi Mimọ, Mo ṣe lodi si eyi. Sugbọn nipa ti arakunrin, o jẹ arakunrin mi. Mo duro fẹ̀gbẹ́kẹ̀gbẹ́ pẹlu rẹ ninu ogun. Eyi je otitọ. Ti o ba kúná, ṣe ri, temi ba kuna, mo fẹ ki o ran mi lọ́wọ́. Bi a si ti ṣe le tẹsiwaju niyi.

82 Bayi ṣe akiyesi nibiyi. O jẹ “BABILONI, IJINLẸ.... . IYA AWỌN AGBERE.” Bayi ṣe o ri bi awọn ijọ ti ṣe ri loni, ẹyin ọ̀rẹ́.... Ṣe ẹ ri bi awọn ijọ ode oni ti ṣe n gbe igbesi aye ti o wù wọn? “O jẹ otitọ gẹlẹ, ẹ maa tẹsiwaju,” ẹlẹdẹ n jẹ ẹlẹdẹ, maṣe gbe ọkàn rẹ sibẹ. “Kni idi, ko si ewu ti a ba ṣe eyi. Kilode, o kan gbiyanju lati jẹ ẹni àtijọ́.” Bayi ṣe akiyesi ẹ̀kọ́ wọn. Ṣe akiyesi bayi. Eyi ni iṣe wọn. Ṣe o ṣe akiyesi pe ni awọn ọdun diẹ sẹyin ijọ Aguda nikan ni o fi àyè gbà pe ki a lọ si àwòrán sinimá? Ijọ Mẹtọdisi ko ni ronu iru nkan bayi, ati gbogbo ijọ ẹlẹkọ adamọ. “Rara, eyi jẹ iṣẹ èṣù.” O dara, o jẹ ohun iyalẹnu fun mi pe kini ohun ti o ṣẹlẹ. Bẹẹni, sa.

83 Ati pe ṣe o mọ, ti ẹ ba mu awọn ọmọbirin ijọ Aguda kekere, ti wọn jade wa pẹlu awọn nkan kekere (Bayi, lara ẹyin ọmọkunrin ti ẹ ti dagba, bi mo tị se dagba tó) ẹ jade wa ki ẹ si lọ si ibi ohun kekere yi nibiti wọn ti n ṣe igbafẹ ti a n pe ni O-ga-dórókún . Ọgbẹẹni naa, mo ro, o wa ni ọ̀run apadi ni aṣalẹ yi. Emi ko mọ, Emi ko ki n ṣe onidajọ rẹ. Ṣugbọn nigbati o kọ́kọ́ kọrin ibajẹ rẹ eyiti o lọ si inu ẹrọ redio, eyiti a ko yẹ̀wò finifini ki a si mu ohun ibajẹ ibẹ kuro - pe “ẹ maa yi lọ 'em, ẹyin ọmọbinrin, ẹyí lọ 'em; ẹ yi lọ 'em lọ si isalẹ ki o si fi orokun rẹ ti o lẹwa han.” Ẹni melo ni o ranti nigbati eyi kọkọ jade ni ọpọlọpọ ọdun sẹyin? Ohun ibajẹ akọkọ ti o kọkọ jade nibiyi niyi. Eyi jẹ otitọ. Ati nigbati wọn mu ọkunrin yi lati ilu Texas, ti wọn si mu awọn obinrin wọnyẹn sita ti wọn si mu awọn aṣọ iwọtẹlẹ wọn ti o si jẹ ki wọn dabi enipe wọn jẹ ohun kan ti wọn ko si ri bẹẹ, ati iru ohun bayi - ti wọn ko si sọ ohunkohun nipa rẹ. Ati nisisiyi kini ohun ti wọn ṣe? O n yọ wọle. O jẹ ẹ̀mi.

84 Ọkunrin kan n ba mi sọrọ ni ọjọ kan, o wipe, “Emi ko mọ ohún ti emi yoo ṣe. Mo ni ọmọkunrin kan ti o jẹ olootọ ọmọkunrin naa n dagba, nitorina o maa n mu ohunkohun ti o ba wa ni ikawọ rẹ yoo si fi si ọwọ rẹ.

Mo wipe “Kini idi?”

“O ti n ba ole rin niyẹn.”

Ti o ba n ba ẹnikan ti o jẹ olè rin, iwọ naa yo di ole. Mama mi ti o jẹ ara ilu Kentucky maa n sọ wipe, “Ti o ba sun pẹlu aja ti o ni kokoro, iwọ yoo dide pẹlu kokoro, pẹlu.” (Aguntan ti o ba aja rin yoo jẹ igbẹ). Ti o ba mu obinrin kan ti ko ni iwa ti o dara ki o si.... ọmọbinrin kan, ki o si mu u pẹlu ọmọkunrin ti o ni iwa ti o mọ́, ati ohun akọkọ ti iwọ yoo ṣe akiyesi nipe yoo wa di ẹni buburu bii ọmọ aja. Ti o ba si woo ni idakeji. A da ọ mọ pẹlu iru ẹgbẹ́ ti o n ba rin! Ya ara rẹ sọtọ! “jade kuro ninu wọn!” Eyi ni ohun ti Bibeli sọ. “Ya ara rẹ sọtọ.” Eyi jẹ otitọ.

85 Ti awọn ijọ ẹlẹkọ adamọ wọn bá pada sinu iru ibajẹ bayi nipa gbigba awọn eniyan wọn laaye.... O dara, nibiyi ni ọjọ kan ninu ile ijọsin Onitẹbọmi nla kan ti o dara, wọn ni lati mu isin wa si opin. Wọn kan le waasu fun ogún iṣẹju, ọkunrin naa le, nitoripe Olusọ-Agutan ni lati mu siga. Gbogbo apejọpọ ni wọn bọ sita. Gbogbo wọn ni o duro sita ti wọn si n mu ọpọlọpọ siga, ti wọn si pada wọle - Olusọ-aguntan ati gbogbo wọn.

Mo lọ si ijọ kan ti o ni ọpọlọpọ èrò, nibẹ ni ọkunrin kan joko pẹlu aṣọ ti o ni ìgbàjá gigun ni ara, o duro sibẹ o wipe.... o fi ara ti àga-iwaasu bi eleyi, o n sọrọ nipa ododo kan ti o ri ni ibi ori-òkè. Gbogbo ohun ti o fẹrẹ sọ niyi. O si jade lọ pada, awọn ìka ọwọ rẹ ti pọn pẹlu èéfín sigá. Bẹẹni. O si n sọrọ wipe awọn obinrin ati awọn ọkunrin yoo lọ ṣerè.... kini orukọ ere ti awọn ará Jamani maa n ṣe yẹn pẹlu eyi.... eyiti wọn maa n pin awọn iwe-pélébé sita, ṣe o mọ̀? O ni.... oo, mo ro wipe mo ranti rẹ. A n pe orukọ rẹ ni Pinochle! Wọn yoo ni eré pinochle kan. Mo ro wipe.... o jẹ ohun ti o n ṣe, o jẹ tita kaadi nigba gbogbo. Ayò pinochle kan ni abẹ isalẹ ile! Akiika, o yani-lẹnu. Ibiti ipinlẹ rẹ wa niyi - a-ba-jọ!

Kini idi ti wọn fi ṣe eleyi, ti wọn si n kigbe lodi si ijọ Aguda ti o wa nita lọhun nibi apejọpọ ẹgbẹ ti a n pe ni Rotari wọnyi ti wọn si n ta tẹ́tẹ́. Kini idi, ẹyin ara ijọ Protesitanti wọn jẹ onibajẹ bi wọn ti ṣele jẹ onibajẹ tó, nitorinaa kini ohun ti iwọ yoo sọ nipa rẹ? Ikòkò dúdú ko le sọ fun àgé dúdú pe o “dọti.” Ni dajudaju ko le ri bẹ. Ati iwọ ti o n ṣe eyi lẹhin naa sọ wipe “O dara, emi jẹ ọmọ ijọ Alagba.” “Emi jẹ ọmọ ijọ Mẹtọdisi.” Iwọ kò jẹ nkankan, titi di igba ti iwọ yoo fi di atunbi. Eyi jẹ otitọ. Ati nigbati o ba ṣe eyi, iwọ yoo mọ pe ohun kan wa ninu rẹ ti o n sọ fun ọ wipe awọn ohun wọnyi ko dara; ati pe iwọ yoo jade kuro ninu rẹ - O si da ọ loju gẹgẹ bi orúkún rẹ ti ṣe ga ju pẹ́pẹ́yẹ lọ. O mọ̀ pe eyi jẹ otitọ. Ni dajudaju. Bẹẹni, sa. Eleyi maa n ṣiṣẹ papọ ni ọna yi, kini idi?

“Iya awọn agbere.”

86 Ni ọjọ kan ninu awọn ọjọ wọnyi iya arugbo naa yoo sọ wipe, “Ṣe o mọ ohunkan? Lẹhin gbogbo rẹ olufẹ, a jẹ bakanna.” O simọ ohun ti yoo jẹ lẹhin naa? Gbogbo agbarijọ papọ awọn ijọ wọn yoo ko ara wọn jọ papọ gẹgẹ bi wọn ti ṣe ri ni oni yi. Ati pe ṣe iwọ mọ ohun ti yoo ṣẹlẹ si ẹgbẹ kekere bi eleyi? Wọn yoo jiya rẹ̀, ẹyin

ọmọkunrin. Eleyi jẹ otitọ.

Ṣugbọn maṣe da ọkàn rẹ laamu, ọdọ-aguntan naa yoo bori rẹ! Nitori ohun ni Oluwa awọn oluwa ati Ọba awọn ọba; Ọlọrun yoo si dari ijọ Rẹ, dipo ijọ ẹlẹkọ adamọ. Oun yoo da ororo wúra ti Ẹmi Mimọ si ori ijọ naa, arakunrin ina yoo rọ lati ọ̀run, iṣẹ àmì ati iṣẹ iyanu yoo si ṣẹlẹ gegẹ bi i pe ko ṣẹlẹ ri. Bẹẹni sà? “Maṣe bẹru agbo kekere, o jẹ ifẹ inu Baba rẹ lati fun ọ ni ijọba naa.” Bẹẹni, sa. “Ẹniti o ba fi ori ti i titi de opin!” Ibiyi ni o ti bẹrẹ. Maa tẹsiwaju lọ ni ọna naa, gbé ori rẹ tààrà si Kalfari. Bibeli yi jẹ otitọ. Maṣe dàamu ọkàn rẹ.

87 Bayi ṣe akiyesi. Awọn ìwà kan wa ti wọn ni, awọn ̀iẁa kan ti wọn nì. A le maa tẹsiwaju si i. Ohun akọkọ ti iwọ yoo kiyesi ni, yoo wa jasi awọn ijọ Protestanti. Lẹhin naa awọn obinrin ijọ Aguda yoo bẹrẹ lati ṣe.... “Kini idi, ko ki n ṣe ohun ìrira lati wọ awọn aṣọ penpe niwọn-igbati o ba lọ si ile ijọsin, ti o si fi aṣọ ilewọ si ori rẹ.” Bi i àṣà kan. “Maṣe jẹ ẹran kankan ni ọjọ Ẹti.”

Ati, Oo, nibo ni ẹ ti ri wipe ki a fi aṣọ ìlẹ́wọ́ si ori ki a to wọ ile-ijọsin? Mo fẹ ki o fi ayọka Iwe-Mimọ yi han fun mi! Isọtẹlẹ eke! Nibo ni o wa ninu ijọ pe o yẹ ki o wọ fila si ori rẹ ninu ile-ijọsin? Nigbati o ba wọ fila si ori rẹ, iwọ ko bọwọ fun Kristi, eyi jẹ otitọ - awọn ọkunrin, ni emi n sọrọ nipa rẹ. Awọn obinrin, ẹ ti ni ibori, ṣugbọn emi yoo pe ẹnikẹni nija lati fi han mi nibiti o ti jẹ ate kan tabi aṣọ ilewọ kan. O jẹ irun ori rẹ. O si ti ge gbogbo ori rẹ kuro. Bayi kini iwọ yoo ṣe nipa eyi? “Oo,” wọn wipe, “eyi jẹ ohun atijọ.” Ti o ba jẹ bẹ́ ẹ̀, o jẹ Bibeli! Ọ̀rọ̀ Ọlọrun jẹ otitọ.

88 Mo n sọrọ nibiyi ni aipẹ nipa obinrin ti o fọ ẹsẹ̀ Jesu, ti o si mu irun ori rẹ, ṣe ẹ mọ, o si fi nu U. Mo wipe, “Ọna kan ṣoṣo ti obinrin le gba lati fi ṣe eyi ni wipe ki o duro ti ori rẹ lati le ni irun ti o maa gùn tó lati fi fọ ẹsẹ Rẹ, lati fi nu U.” Eyi jẹ otitọ. Oo, o jẹ ohun itiju lati ri ọna yi.... Nibiyi, ìgba ti òtútù mu pupọ, ti wọn yoo maa rin kaakiri pẹlu aṣọ otutu penpen bi eleyi, ti ihòhò ara wọn si farahàn.

Kini idi, iwọ yoo sọ wi pe, “Kini idi ti iwọ fi n sọrọ nipa obinrin?” O yẹ ki a sọrọ nipa rẹ pẹlu. Ati ẹyin ọkunrin ti ẹ fi aye gba pe ki awọn obinrin yin ṣe nkan wọnyi, arakunrin, emi ko mọ ohun ti emi yoo ro nipa rẹ. Bayi eyi jẹ otitọ.

Ati ẹyin Olusọ-aguntan! Ẹmi ko mọ boya o wa nibiyi. Ṣugbọn ti ẹ ba ri ọkunrin naa, ẹ sọ fun wipe ki o wá ẹ sọ fun.... pe ki o ri mi, ṣe ẹ ri. Ti ko ba ni ibọwọ fun Kristi mọ ti o fi fi aye gba ki awọn ọmọ ijọ rẹ ṣe bi eleyi lai ma sọ ohunkohun nipa rẹ.... Bayi o.... wọn le ṣe eleyi nita lọhun lẹyin rẹ, ṣugbọn ti ko ba sọ fun wọn nipa rẹ, ko yẹ fun ojiṣẹ Jesu Kristi. Eyi jẹ otitọ. Ko yẹ fun ojiṣẹ Kristi. Ojiṣẹ Kristi gbọdọ jẹ ẹniti ko bẹ̀rù, ti o ba ni ohunkohun ṣe pẹlu Bibeli. Dajudaju. Ṣugbọn nibiyi ni wọn wa. Wọn jade lọ awọn sị se e ni ọnakọna.

89 Ati lẹhin igba naa, ohun àkọ́kọ́ ti iwọ yoo ṣe akiyesi ni wipe, awọn ijọ protestanti yoo gbà á! Iwọ ara ijọ Metọdisti daradara, ati iwọ ara ijọ Onitẹbọmi, ati iwọ ara ijọ Presibiteriani ati ara ijọ Nazarẹni, ara ijọ Atipọ Mimọ, ati gbogbo yi patapata - bakanna ni. Wọn bọ sita, mẹfa ninu wọn ati ìlàjì dọsini ni ibọ miran. Gbogbo rẹ̀ niyi, “iya awọn agbere.” Ijọ ẹlẹkọ adamọ yin. “Niwọn igbati wọn ba ti bẹrẹ lati olú-ile-ẹgbẹ́. O le bẹrẹ lati olu-ile-ẹgbẹ rẹ nibiyi, ṣugbọn ko ki n ṣe iyẹn ti o wa nibẹ. O da lori ibiti o ti wa. Eyi jẹ otitọ.

90 Bayi, mo ro pe ko si akoko to lati lọ ninu omiran to sẹkù. Boya o sàn ki emi fi i silẹ fun owurọ. O dara, ẹ jẹ ki a kan mu eyiti o kere yi. A ni ibiyi “iribọmi sinu omi,” a si ni “iyantẹlẹ.” Ati, Oo, ọpọlọpọ nkan. Nitorina ẹ jẹ ki a kan mu eleyi, eyiti o kere yi ti o sọ nipa “Awọn obinrin oniwaasu.” Ki a si mu eleyi.

Nisisiyi, bayi, obinrin oniwaasu, emi ko nifẹ lati ba ayọ yin jẹ, ṣugbọn mo fẹ sọ ohun kan fun yin. Ko si Iwe Mimọ kankan, ko si ẹyọkan ninu Bibeli. Bẹẹni, mo mọ ibiti ẹ n lọ, mo si ti gbọ gbogbo yin..... Bẹẹni, “Ati awọn ọmọkunrin yin ati ọmọbinrin yin yoo sọ asọtẹlẹ.” Bayi, ti Olusọaguntan yin ko ba mọ ohun ti isọtẹlẹ jẹ, ti ko ba mọ.... nigba naa ko ni ohunkohun ṣe lẹyin aga-iwaasu, ti o n gbiyanju lati sọ fun ọ pe ki o di oniwaasu, ṣe ẹ ri. Nitori o jẹ dajudaju, a da a lẹbi lati Jẹnẹsisi titi o fi de Ifihan! Bayi jẹ ki emi fi hàn fun ọ nibiyi.

91 Nisisiyi mo fẹ ki ẹ ṣi pẹlu mi si inu Iwe Timotiu ori keji ẹsẹ kọkanla. Ẹ ṣi ibiyi a o si ri i nisisiyi; a o si ri i nibiyi, pẹlu, Iwe Iṣe Awọn Aposteli ori keji. Ki ẹ kan tẹti silẹ nibiyi si ohun ti Iwe Mimọ ni lati sọ nipa kókó ọrọ naa.

Bayi, ẹnikan n ṣe atẹnumọ nipa ọrọ kan, “O dara, Arakunrin Branham, o kan jẹ ẹniti o n kórira awọn obinrin atijọ kan.” Emi ko ki n ṣe akorira obinrin. Mo jẹ.... Emi ko nifẹ lati maa ri awọn obinrin ki wọn maa gbiyanju lati gba ipo ti ko tọ si wọn. Ṣe o ranti ni ibi ìgbé-ọkọ-oju-omi si ni ibiyi ti a n pe ni ibudokọ Howard, ọkan ninu awọn ibudó-ọkọ oju-omi ti o ni aṣeyọri julọ ni Odò Ohio, wọn fi obinrin ṣe adari rẹ? Ẹ wo ohun ti o ṣẹlẹ. Wọn fun obinrin ni aṣẹ lati dibo, ẹ wo ohun ti o ṣẹlẹ.

92 Ẹ jẹ ki n sọ fun yin bayi. Ko ki n ṣe lati ṣe ikorò si awọn obinrin, mo fẹ ki awọn ọkunrin naa loye pe awọn pẹlu wa ninu eyi. Ṣugbọn jẹ ki n sọ ohun kan fun ọ, arakunrin, orilẹ-ede yi jẹ orilẹ-ede obinrin. Emi yoo fi idi eyi mulẹ fun yin lati inu Iwe Mimọ, pẹlu ohunkohun ti ẹ ba fẹ lo lati le fi idi rẹ múlẹ̀. Eleyi ni.... kini ohun ti o farahan ninu owo wa? Obinrin kan. Nibo a ti ri i ninu Iwe Ifihan nibiyi? Ṣe o ri obinrin naa. O jẹ onka mẹtala,

pẹlu, ohun gbogbo ti o bẹrẹ. Irawọ mẹtala, ila mẹtala, agbègbè mẹtala, mẹtala - gbogbo rẹ jẹ mẹtala lati ibẹrẹ. O farahan ninu Iwe Ifihan ori kẹtala. Obinrin kan, mẹtala.

93 Ati ni ọdun 1933 nigbati Oluwa.... Nigbati a n ṣe ipade nibiyi nibiti ijọ Kristi duro si bayi, ibiti a ti n ṣetọju awọn eniyan atijọ naa ti a n pe ni ile Masoniki, iran Oluwa tọ mi wá nibẹ, O si sọtẹlẹ pe ilu Jamani yoo dide wọn yoo si kọ́ ila Magnoti sibẹ. Ọpọlọpọ ninu yin ni o ranti. Ati bi a si ti fi agbara kún wọn nibẹ, ti a si lu awọn ọmọ-ogun Amẹrika nibẹ ni ibi ila naa.

Ati pẹlu ti mo si sọ ohun ti yoo ṣẹlẹ, ati nipa Ọgbẹẹni Rossevelt ati awọn nkan miran, bi yoo tị se gbe apoti ìdìbò ti yoo si wọle lẹẹkẹrin. Bẹẹ ge, o si wa si imusẹ gẹ́lẹ́. Ati pẹlu mo sọ nipa awọn ọkọ ayọkẹlẹ ti irisi wọn yoo maa dabi ẹyin, titi yoo fi di igbà ikẹyin irisi wọn yoo wa dabi ẹyin nitootọ. Ati nisisiyi o sọ wipe, “yoo si wa si imusẹ pe a ko ni fi ọpa itukọ wa awọn ọkọ̀ naa, ohun-ilẹ́wọ́ miran ni yoo maa wa wọn.” Iru awọn ọkọ wọnyi ni wọn ṣe jade bayi - Ohun miran ni a fi n dari rẹ, fun aabo. Eyi jẹ otitọ. Iwọ ko ni le wọ ilu kan, ilu kan ti ayika rẹ jẹ ogún ibusọ maili, o kan le lọ si ogun ibusọ maili. Ko le fi ara kọ́ ọkọ̀ miran, nitoripe ohun miran ni a fi n dari rẹ. Ṣe ẹ ri, o ti n lọ bi eleyi nisisiyi.

Mo si sọ wipe, “Ranti ni ọjọ naa, ṣaaju ki opin ko to de, pe obinrin kan.... Bayi, ẹ jẹ ki gbogbo wa kọ eleyi pamọ silẹ. Obinrin alagbara kan yoo dide, boya yoo jẹ Aàrẹ, tabi apasẹ, tabi obinrin Alagbara kan ni orilẹ-ede Amẹrika yi, Yoo si wa labẹ idari ati isapa obinrin. Bayi, ṣe ẹ ranti, eyi jẹ Bayi ni Oluwa wi.”

94 Ṣe ẹ ri, o si kuna! Kini ohun ti o ti fi silẹ fun? Jẹ ki emi ko o sọ fun ọ. Jẹ ẹni ẹmi, jẹ ki.... ṣi ọkan rẹ silẹ, wo o. Kini idi ti o fi n ṣe eyi? Lati le fun ijọ Aguda ni aye lati wọle. Ṣe ẹ ri? Ẹ n bọ awọn oṣere wọnyi ati orisirisi awọn nkan wọnyi ti o wa nita. Ranti iwaasu ti mo ṣe? Margie, ṣe ẹ ranti ọpọlọpọ ọdun sẹyin, lori gbigba-akoso orilẹ-ede Amẹrika ati gbigba-ijọba orilẹ-ede Amẹrika. Ati bi mo ti ṣe sọ wipe yoo dide ni ilu Parisi lẹhin igbati a ti gbà wọn nibẹ lati ọwọ “obinrin naa, waini ati akoko nla,” o si lọ si Hollywood. Bayi dipo ki wọn ranṣẹ lọ si ilu Parisi lati le ri awokọṣe. Kini ohun ti o ṣe? O lọ.... O ko gba awọn ọmọ rẹ laaye lati lọ si ìwòran aworan, ṣugbọn o lọ sinu ẹ̀rọ amohun-maworan, o tẹsiwaju si i o jade o si ba gbogbo rẹ̀ jẹ́, o fi aye gbà á.

Ati nibiyi ni a wa ni oni yi, awọn ọmọbinrin kekeke ati awọn ọmọkunrin kekeke gbogbo wọn dabi.... bi i awọn oṣere inu ẹrọ tẹlifisan. Kini ohun naa? O jẹ lila ọ̀nà. Ọ̀rẹ́, obinrin onibajẹ kan le ran ọpọlọpọ eniyan lọ si ọrun apadi ju gbogbo awọn ile-ọti ti o le gbé kalẹ ni ìlú lọ. Eyi jẹ otitọ. Ṣe akiyesi rẹ bi o tị se n lọ ni oju pópó pẹlu bi o tị se fẹrẹ bọ aṣọ rẹ si ìhòhò. Emi kò bikita ẹniti ọkunrin naa jẹ, ti o ba jẹ ọkunrin pipe, nigbati o ba wo obinrin naa ohunkan gbọdọ ṣẹlẹ ni àgọ́ ara rẹ. Nisisiyi jẹ olootọ.

95 Emi ko bikita.... Mo ti ni Ẹmi Mimọ fun ọpọlọpọ ọdun. O ko le wo obinrin kan ti aṣọ rẹ fi ihoho ara rẹ hàn.... Mo gbe agbelebu si iwaju ọkọ̀ mi, ọpọlọpọ ninu yin ni o ti ri. Ẹnikan sọ fun mi pe, “Ṣe ọmọ ijọ Aguda ni ọ ni?” Nibo ni ijọ Aguda ti ni ipo ninu agbelebu? Agbelebu tumọ si “Kristẹni.”

Awọn ẹni mimọ kekere atijọ Cecilia mimọ ati awọn nkan bawọnyi ni amin igbagbọ ninu ẹsin ijọ Aguda. A ko gbagbọ ninu iru nkan wọnyi. A gbagbọ ninu Kristi. Wọn ni oriṣirisi awọn ti o ti kú ti wọn n bọ. O jẹ ipele ẹsin abọriṣa ti o ga julọ. Ohun ti o jẹ niyi, bibọ awọn ti o ti ku. Ko si iru nkan bayi, rara.

96 Mo bere lọwọ alufa naa, mo wipe, “Kini ìdí ti wọn fi.... Ti Peteru ba jẹ Popu akọkọ....?

O wipe, “Eyi dara.”

Mo wipe, “Lẹhin naa kini idi ti Peteru fi sọ wipe, ko si onilaja miran laarin Ọlọrun ati eniyan ṣugbọn ọkunrin naa Kristi Jesu, ẹ si ni ẹgbẹrun marun-un awọn obinrin ti wọn ti kú ati gbogbo awọn nkan miran ti ẹ sọ di onilaja? Wayi o kini ohun ti o ṣẹlẹ?” Ohun niyi. Wọn kò ni idahun fun eyi. Eyi jẹ otitọ.

97 Bayi lara awọn ẹkọ opomulero wọn, ẹ̀kọ́ èké wọn, awọn ẹgbẹ wolii eke ti ijọ Protẹsitanti wọn ti wà wọn si n kọni ni èyí, ati ẹyin eniyan Protẹsitanti ẹ n jẹ ẹ́. Eyi jẹ otitọ gẹlẹ. Ijọ ẹlẹkọ adamọ ati oriṣiriṣi ìlànà ati oriṣiriṣi ohun miran ti ẹ n lọ ninu rẹ, eyiti ko ba Iwe Mimọ mu rara. O tako Iwe Mimọ, sibẹ o so ara rẹ pọ mọ́ ọ. O jẹ otitọ.

98 Bayi ẹ tẹti silẹ si eyi nipa awọn oniwaasu obinrin. O dara, ohun akọkọ ni, mo fẹ Iwe Timotiu kinni ori keji, ẹsẹ kọkanla. Ẹ tẹti silẹ si bayi ohun ti o sọ nibiyi.

Jẹ ki obinrin ki o maa fi idakẹjẹ ati itẹriba gbogbo kọ́ ẹ̀kọ́

Ṣugbọn emi ko fi aṣẹ fun obinrin lati maa kọni tabi lati paṣẹ lori ọkunrin, bikoṣepe ki o dakẹjẹ

Emi kọ ni mo kọ ọ sibẹ, ojuṣe mi ni pe ki emi ki o sọ ọ fun yin o wà nibẹ. Ṣe ẹ ri? Ṣe ẹ ri?

Jẹ ki obinrin ki o ma fi idakẹjẹ ati itẹriba gbogbo kọ ẹkọ. [Ti o ba lọ si ijọ elétò kan ti o sị se akiyesi wọn, ṣe ẹ ri. Ṣe ẹ ri?]

Ṣugbọn emi ko fi aṣẹ fun obinrin lati maa kọni, tabi lati paṣẹ [Ki o jẹ olusọ-aguntan, diakoni, tabi ohunkohun bi eleyi] lori ọkunrin, bikoṣepe ki o dakẹjẹ.

Nitori Adamu li a kọ dá, lẹhin na, Efa.

99 Ṣe ẹ mọ́.... Bayi tẹti silẹ, obinrin. Ẹyin olootọ, oniwa-ree Kristẹni obinrin ẹ jẹ ohun ti o dara ju ti Ọlọrun le fi fun ọkunrin kan, tabi ki o fun un ni ohun miran ti o yatọ. Bẹẹni, sa, ṣe ẹ ri? Obinrin ko si ninu iṣẹda àkọkọ́ paapa. Obinrin ko ki n ṣe ohun ti Ọlọrun da. O jẹ ohun ti a yọ jade lati ara ọkunrin ti Ọlọrun dá. Nigbati Ọlọrun da ọkunrin o da ni akọ ati abo lapapọ. O sị se ipinya wọn. Ati nigbati ọkunrin ti n gbé ni ori-ilẹ-aye ti o si fun gbogbo ẹranko ni orukọ ti o si ti gbé ni ori-ilẹ-aye fun igba pipẹ, o mu egungun kan lati ìhà Adamu gẹgẹ bi ẹya lati ara rẹ O si fi dá obinrin. “Adamu ni akọkọ dá, ati lẹhin naa Efa.” Bayi ṣe akiyesi.

A ko tan Adamu jẹ, ṣugbọn obinrin naa ni a tàn jẹ, ninu airekọja.

100 Ọlọrun mu ọkunrin, èṣù si mu obinrin. Ẹ wo o taara. Tani ẹni ti o n ṣe nkan wọnyi loni? Ẹ wo ijọ Ọlọrun tootọ, yoo sọ wipe, “Jesu!” Aṣodi-si-Kristi naa yoo wipe, “Maria!” Ẹ wo awọn ẹ̀mí naa, ṣe ẹ ri, awọn niyi. “Mo ki Ọ, Maria, ìyá Ọlọrun, alabukun fun ọ ninu awọn obinrin, gbadura fun awa ẹlẹṣẹ bayi ati ni ọjọ ikú wa. Amin. ”Maria gbadura fun .... Oo, o jẹ ohun iyalẹnu! Ṣe ẹ ri, bayi ni o ṣe lọ. Obinrin ohun ti èṣù ṣiṣẹ lara rẹ. Kristi ohun ti a n jọsin fun, ati Ẹni naa kan ṣoṣo. Ohun niyi, ohun niyi.

101 Adamu ni a kọkọ dá, ati lẹhin naa Efa. A ko tan Adamu jẹ. Bawo ni a o ṣe ni olusọ-aguntan obinrin, diakoni? A ko tan Adamu jẹ, ṣugbọn a tan obinrin naa jẹ. Nitootọ oun ni.... oun ko ronu pe oun wa ninu ìkùnà, ṣugbọn o wa nibẹ. Obinrin naa, ẹniti a tan jẹ, o wà ninu arekọja. Nitoripe wọn ni.... Ni gbogbo igba ti a ba n ṣe isinku ni ojú-pópó, obinrin ni o fà á. Ni gbogbo ìgbà ti ọmọ-ọwọ ba kigbe sita, obinrin ni o fa a. Ni gbogbo igba ti ẹnikan ba kú, obinrin ni o fa a. Gbogbo irun funfun, obinrin ni o fà á. Ohun gbogbo, ati ikú, obinrin ni o fa a. Ati lẹhin naa ẹ fi ṣe olórí ijọ: Olusọ-aguntan, oo, nigbamiran bisọbu. Ki oju ki o ti yin.

102 Bayi ẹ jẹ ki n mu yin lọ sinu ohun miran, ni iṣẹju kan. Bayi ẹ jẹ ki a ṣi Iwe Kọrinti kinni ori kẹrinla ẹsẹ keji-le-lọ́gbọ̀n nibẹ, ki ẹ si ri ohun ti Pọọlu sọ nibiyi, ati lẹhin naa a o lọ sinu awọn omiran ni iṣẹju kan. Ati lẹhin naa a ko fẹ da yin duro pupọ, ki o ma ba rẹ̀ yin ẹ ko si ni anfani lati pada wá. Eyi dara, mo fẹ́ ka.... Ẹni melo ni o gbagbọ pe Pọọlu jẹ olukọni ti a mísí? Bayi, ranti, Pọọlu kọ eyi si Timoti pẹlu. Ṣe ẹ ri? Bayi, Kọrinti kinni ori kẹrinla ẹsẹ keji-le-lọgbọn. Ẹ jẹ ki a bẹrẹ si ni ka lati ibiyi, ori kẹrinla ẹsẹ kẹrin-le-lọgbọn, mo gbagbọ.

Jẹ ki awọn obinrin yin dakẹ ninu ijọ....

Ṣe ẹ gbọ ohun ti o sọ?

Jẹ ki awọn obinrin yin dakẹ ninu Ijọ nitori a ko fifun wọn lati sọrọ, ṣugbọn jẹ ki wọn wa labẹ itẹriba....

Ṣe ẹ ri ohun ti o maa n tọka Bibeli kika ninu ẹsẹ yi? Ti o ba ni, ẹ fi si ibi ẹsẹ yi, ki ẹ si ri i yoo gbe yin pada si Iwe Jẹnẹsisi ori kẹta ẹsẹ kẹrin-din-logun: nigbati Ọlọrun sọ fun Efa, nitoripe o tẹti si sapẹnti dipo ọkọ rẹ pe yoo ma dari rẹ ni gbogbo ọjọ aye rẹ. Bawo ni obinrin yoo ṣe wa ti yoo si maa dari ọkunrin, o le jẹ olusọ-aguntan tabi diakoni, nigbati Bibeli sọ wipe, “Jẹ ki wọn wa lábẹ́ itẹriba” gẹgẹ bi o ti ṣe wa ni ibẹrẹ nigbati Ọlọrun.... . .? Ọlọrun ko le yi pada. Iwọ ko le mu ki ọrọ naa sọ ohun kan nibiyi ki o si sọ ohun miran nibo-miran. Oun ko le ṣe eleyi. O jẹ bakanna ni gbogbo igba. Nitori naa ni atetekọṣe, nibẹ ni....

103 Ṣaaju ki a to pari eleyi, ti mo ba ri àyè, mo fẹ ṣalaye ọrọ igbeyawo ati ikọnísílẹ̀ fun yin. Emi kò tị se eleyi ninu ijọ yi fun yin ri. Ṣugbọn ṣe akiyesi majẹmu onipameji yi. Ọkan sọ wipe o le ṣegbeyawo, ekeji si sọ wipe ko le ṣe igbeyàwó, ọkan si sọ eleyi, sọ tọun, tabi sọ omiran. Kàn duro ni iṣẹju kan ki o si ri ohun ti Bibeli sọ nigbati a bá dé ibẹ. Ṣe ẹ ri? O dara. Bayi ṣe akiyesi nibiyi.

104 Jẹ ki awọn obinrin yin dákẹ ninu ijọ.... nitori a ko fifun wọn lati sọrọ, ṣugbọn jẹ ki wọn wa lábẹ́ itẹriba, gẹgẹ bi ofin pẹlu ti wí.

Lẹhin naa, ninu Majẹmu Laelae wọn ko fi aye gba wọn lati sọrọ, nitoripe Pọọlu sọ nibiyi pe wọn ko fi aye gbà wọn. Ṣe eyi jẹ otitọ? “Jẹ ki awọn obinrin yin dakẹ, o jẹ itẹriba.” Bayi ti o ba fẹ fi sinu atọka ti Bibeli kika nibiyi, mu lọ sinu Iwe Jẹnẹsisi ori kẹta ẹsẹ kẹrin-din-logun, ṣe ẹ ri. O dara. “labẹ gẹgẹ bi ofin pẹlu ti wi.”

Ati bi wọn ba si fẹ.... kọ ohunkohun, ki wọn ki o bèrè lọwọ ọkọ wọn ni ile, nitori ohun itiju ni fun awọn obinrin lati maa sọrọ ninu ijọ.

Kini?....

105 Bayi ẹ wo àmìn ibéèrè lori ọkọọkan ninu Bibeli yin, lori iyẹn “Kini.” Kini o fa a ti Pọọlu fi sọ eleyi ti o si fi ṣe huwa ni ọ̀nà yi? Bayi, ti o ba le ri lẹta ti awọn ara Kọrinti kọ si Pọọlu. Nisisiyi, o le ri wọn ni eyikeyi ile-ikàwe ti o dara, ṣe ẹ ri, ti awọn ara Kọrinti kọ si Pọọlu. Wọn kọ wọn wọn si sọ fun un, lẹhin ti a ti yi awọn obinrin kan

pada.... Wọn ni awọn orişa obinrin nibẹ eyiti a n pe ni Diana, o si wa ni Efesu pẹlu. Awọn ara Kọrinti si n bọ ohun kanna, nitori o jẹ isin awọn keferi.

Wọn si ri okuta kan ni ori pápá ni ọjọ kan, irisi rẹ si jọ ti ara obinrin. Wọn wipe, “obinrin ni Ọlọrun, o si sọ aworan`ere rẹ silẹ fun wa.” Tẹmpili wọn si ju tẹmpili Solomọni lọ, wọn wipe, awọn akọ-itan-silẹ. Oo, a fi okuta marbili tẹ ẹ ninu pẹlu wura, nigbati a tẹ Tẹmpili Solomoni ninu pẹlu kedari wura. Ṣe ẹ ri. O dara ju u lọ. Ati ohun lẹhin naa, ti Ọlọrun ba jẹ obinrin, kini idi dajudaju, Oun yoo ni alufa obinrin. Dajudaju, ti Ọlọrun ba jẹ obinrin, lẹhin naa obinrin oniwaasu dara. Ṣugbọn ọkunrin ni Ọlọrun, Bibeli sọ wipe O jẹ ọkunrin. Ọkunrin ni O jẹ. Ṣe ẹ ri? Ti Ọlọrun ba jẹ ọkunrin, lẹhin naa ọkunrin ni o gbọdọ jẹ.

106 Bayi ṣe akiyesi nibiyi. “Kini?”

Nisisiyi, lara awọn alufa obinrin, nigbati a yi wọn pada lati ibọrisa si Kristẹni, wọn ro wipe awọn si le di ipo wọn mu gẹgẹ bi oniwaasu, wọn kan wa sibẹ. Ti wọn ba waasu nibẹ nipa Diana, wọn yoo wa sibiyi wọn yoo si waasu nipa Kristi.

O wipe, “Kini”? Lọdọ yin ni Ọrọ Ọlọrun ti jade ni? Ẹ tẹti si eleyi. Arakunrin, bawo ni awọn ojişẹ-Ọlọrun yoo ṣe ṣe eyi? Ẹsẹ kẹrin-din-logoji:

Kini? Lọdọ yin li Ọrọ Ọlọrun ti jade ni? tabi ẹyin nikan li o tọ wa?

Bi ẹnikẹni ba ro ara rẹ pe oun jẹ wolii, tabi oun jẹ ẹniti o li ẹmi [Ko nilo lati jẹ wolii kan, ko kan jẹ ẹniti o maa n ronu nipa tị̀ èmí] jẹ ki nkan wọnyi, ti mo kọ si yin ki o ye e daju pe ofin Oluwa ni wọn. [ṣe o gba eyi gbọ́?]

Ṣugbọn bi ẹnikẹni.... ba jẹ òpè, ẹ jẹ ki o jẹ òpè.

Bayi a sọ eleyi taara gẹgẹ bi mo ti ṣe mọ lati sọ ọ to. Ṣe ẹ ri i? O wipe, “Bi ẹnikẹni ba ro ara rẹ pe oun jẹ ẹniti o li ẹmi, tabi oun jẹ wolii, jẹ ki nkan wọnyi ti mo kọ si yin ki o ye e daju pe ofin Oluwa ni wọn.” Ṣugbọn o sọ wipe, “bi ẹnikẹni ba jẹ òpè, ẹ jẹ ki o jẹ òpè.” Ṣe ẹ ri i? Ohun kan ti o le ṣe. Ti wọn ba nifẹ lati tẹsiwaju ninu rẹ, o ni lati fi wọn silẹ; nitoripe o ti ri bi wọn ti ṣe bẹrẹ

107 Ati awọn obinrin kan sọ fun mi wipe, o wipe “Oo, Pọọlu jẹ akorira obinrin atijọ kan.”

Ko ki n ṣe akorira obinrin! Ṣe o mọ. Pọọlu jẹ aposteli, ati si awọn ijọ Keferi. Wo ibiyi. Ṣe o mọ ẹniti Pọọlu jẹ....“ Ẹni melo ni o gbagbọ pe ohun ti Pọọlu waasu niyi? Ṣe ohun ti o sọ nibiyi niyi? Pọọlu si sọ wipe....

Iwọ yoo sọ wipe, “O dara, duro fun iṣẹju kan bayi, Arakunrin Branham. Fun iṣẹju kan! Nisisiyi, bisọpu wa sọ wipe eyi dara. Oludari gbogbo ijọ lapapọ sọ wipe o dara. Bişọpu ijọ isọkan sọ wipe o dara.”

Emi ko bikita ohun ti wọn sọ, o jẹ èké! Mo si sọ fun yin pe a o jẹ ki eyi rinlẹ daada. Awọn wolii eke yoo sọ bakanaa. Nitori Bibeli sọ wipe, “Bi ẹnikẹni ba ro ara rẹ pe oun jẹ wolii, tabi oun jẹ ẹniti o li ẹmi, jẹ ki nkan wọnyi ti mo kọ si yin ki o ye e daju pe ofin Oluwa ni wọn.” Ati tị̀ emi rẹ ko ba jẹri gbe Ọrọ naa, o jẹ wolii eke ni íbẹ̀rẹ. O san ki n jẹ akorira obinrin ju pe ki n jẹ olufẹ obinrin, ki n lọ pẹlu irú nkan yi, ki n si duro pẹlu irú nkan bi eleyi ninu ijọ Ọlọrun eyiti o ṣe lodi si aṣẹ Ọlọrun. Paulu si sọ wipe (ẹ mu iwe Galatia ori kinni ẹsẹ kẹjọ), Pọọlu sọ wipe, “Ṣugbọn bi o ṣe awa ni, tabi angẹli kan lati ọrun wa, li o ba wasu ihinrere miran fun yin ju eyiti a ti wasu fun yin lọ, jẹ ki o di ẹni ifibu.” Nisisiyi kini ohun ti iwọ yoo ṣe nipa eyi?

108 Bayi iwọ yoo sọ wipe, “Kini ohun ti a o ṣe nibiti o ti sọ wipe, ”Awọn ọmọkunrin yin ati awọn ọmọbinrin yin yoo sọtẹlẹ: Ninu Iwe Joẹli, ati ayọka ti Peteru sọ ni ọjọ Pentikọsti?“ Eyi jẹ otitọ gẹlẹ.

Ṣe o mọ, ninu Iwe Majẹmu Laelae, pe ọna kan ṣoṣo, ati ọ̀nà kan ṣoṣo nisisiyi, ti ẹnikẹni le fi wa sinu Majẹmu naa nipasẹ, lati ọdọ.... Abrahamu ni ẹni naa ti a ṣe ileri fun, ati edidi ileri naa jẹ nipasẹ ìkọlà. Ẹni melo ni o mọ eyi? Ọlọrun ni o n fi idi eyi mulẹ.

109 Gẹgẹ bi arakunrin kan lati ijọ Onitẹbomi, o wipe “Arakunrin Branham, kini idi, awa ara ijọ-Onitẹbọmi ti gba Ẹmi-Mimọ.”

Mo wipe, “Nigba wo ni ẹ gbà á?”

O wipe, “Ni wakati ti a gbagbọ.”

Mo wipe, “Paulu sọ wipe, ”Ṣe ẹ ti gba Ẹmi Mimọ lati igba ti ẹ ti gbagbọ?“ Mo wipe ”Nisisiyi, ẹyin ara ijọ Onitẹbọmi ẹ wa ki ẹ si gba diẹ lara eyi, a o si sọrọ diẹ nipa ààbò ainipẹkun pẹlu rẹ.“ Mo wipe, ”Ṣugbọn.... o dara, nibo ni ẹ ti ri iru nkan bi eleyi?“ Ṣe ẹ ri? O wipe, ”Ṣe ẹyin ti gba A lati igba ti ẹ ti gbagbọ? Wọn jẹ onigbagbọ, ti wọn si ti pariwo, ti wọn si ti ni ayọ̀ ati gbogbo nkan miran sibẹ wọn ko ti gba Ẹmi Mimọ, Pọọlu

sọ wipe, “wọn ko ti gba A.” Ṣe ẹ ri?

“Ẹyin ha gba Ẹmi Mimọ naa nigbati ẹyin gbagbọ?”

Wọn si wipe, Awa ko gbọ́ rara bi Ẹmi Mimọ kan wa

O wipe, “Njẹ baptisimu wo li a ha baptisi yin si?”

Wọn wipe “A tị se iribọmi fun wa.” Ṣugbọn ni ọna to kuna, ṣe ẹ ri, nitori a ni lati tun baptisimu ṣe fun wọn lẹẹkan si. Gbogbo rẹ dara.

110 Bayi, ṣe akiyesi eyi nisisiyi, pe awọn oniwaasu obinrin wọnyi, nigbati wọn ba wọle, wọn maa n gbèrò lati gba gbogbo aṣẹ, ṣugbọn a ko fi aye gbà a rara lati ọdọ Ọlọrun lati ṣe eyi. Ati pe. . . nigbati a ṣi wa lori akori naa nisisiyi, obinrin naa, ṣe ẹ ri, ninu rẹ. Bayi, o sọ wipe, “Bi ẹnikẹni ba ro ara rẹ pe oun jẹ ẹniti o li ẹmi, tabi oun jẹ wolii, jẹ ki nkan wọnyi ti mo kọ si yin ki o ye e daju pe ofin Oluwa ni wọn, ṣugbọn bi ẹnikan ba jẹ ope, ẹ jẹ ki o jẹ ope.” Idi niyi ti ile-ijọsin yi ko ṣe duro ki o si gbọwọ le obinrin oniwaasu, awọn diakoni obinrin, tabi fun obinrin ki o ṣe ohunkohun gẹgẹ bi didi-ipo mu ninu ijọ yi, idi ni wipe Iwe-Mimọ yi wa nibiyi, o si fi ara han gbangba niwaju wa.

111 Bayi, Bibeli sọ wipe, “Awọn ọmọkunrin yin ati awọn ọmọbinrin yin yoo sọ tẹlẹ.” Nisisiyi, kini ohun ti ọrọ isọtẹlẹ tumọ si? Ẹ wo itumọ eleyi, o tumọsi “Sọ ohunkan, labẹ ìmisi,” tabi “ki o sọ asọtẹlẹ nipa ohunkan ti o n bọ.” O jẹ ọrọ ti o ni ọpọlọpọ itumọ.

Gẹgẹ bi i sọ-di-mimọ o tumọ si “ki a fọ ọ, ki a si ya a sọtọ fun iṣẹ isin,” ṣe ẹ ri. O jẹ ọrọ ti o ni ọpọlọpọ itumọ, eyiti o ju ẹyọkan lọ. Gẹgẹ bi a ti ṣe orisirisi iru rẹ ni ede-oyinbo nibiyi.

Gẹgẹ bi igba ti a ba sọ ọ̀rọ̀ pe (san-wó). O dara, kini ọrọ naa (San-wó tumọ si? Iwọ yoo sọ wipe, “O dara, o tumọ si o ti san-wo ọkọ̀ rẹ.” “Rara, ko san-wo, ohun ti o fẹ sọ ni wipe (ó gbẹ́ ihò).” Rara, ko fẹ sọ eleyi, ohun ti o fẹ sọ ni wipe (kò gbadun rẹ),“ Tabi.... Ṣe o ri? Ẹyọ, ọrọ kan, o ni lati mọ ohun ti o n sọrọ nipa rẹ̀. Ṣe ẹ ri?

Bi o tị se ri niyi pẹlu ọrọ naa, ọrọ ti o ni ọpọlọpọ itumọ, nibo “Awọn ọmọkunrin ati awọn ọmọbinrin yin yoo maa sọtẹlẹ” Bayi, ọna kan ṣoṣo ti Ọlọrun....

112 Ọmọ ijọ Onitẹbọmi yi sọ wipe, “O dara, a ti gba Ẹmi Mimọ.”

Mo wipe, “Nigba naa....”

“Nigbati a gba A gbọ́.”

Mo wipe “Nisisiyi, ṣe ẹ ri....”

O wipe, “Ọlọrun fun Abrahamu ni....” O wipe, “Abrahamu gba Ọlọrun gbọ.” Bi o ti ṣe kọ ọ niyi. O wipe, “Abrahamu gba Ọlọrun gbọ, a si ka a si ododo fun.” Ẹni melo ni o mọ pe eleyi jẹ otitọ? Bayi wo bi o tị se rọrun fun Satani lati yọ fi eleyi sinu arakunrin kan. Ṣe ẹ ri, bi o tị se rọrun. Nisisiyi, Iwe Mimọ niyi.

Arakunrin, Emi n sọ fun yin, ni ibi ori-oke nibiyi, o gbọdọ ni ìtàmi-òroró ki o to wọ inu eleyi. O gbọdọ wá ibi ikọkọ ki o si gbadura. Awọn eniyan so wipe, “Kilode ti iwọ ko fi jade lọ ki o si ri awọn eniyan?” Arakunrin, Ti iwọ ba fẹ ba awọn eniyan sọrọ tabi ki o kọ́ wọn, o dara pe ki o wà ni iwọ nikan pẹlu Ọlọrun fun igba diẹ ṣaaju ki o to wọ ibi aga-iwaasu. Dajudaju, ṣe ẹ ri, nitoripe Satani jẹ alákèrekè, alakereke pupọ

113 O wipe bayi, ṣe akiyesi, o wipe “Abrahamu gba Ọlọrun gbọ, a si ka a si ododo fun.” Eyi jẹ otitọ. O wipe, “Bayi, kini ohun miran ti Abrahamu yoo ṣe ju pe ki o gbagbọ lọ?”

Mo wipe, “Ohun yi nikan ni o le ṣe.”

O wipe, “Melo melo ni iwọ yoo ṣe tabi ẹlomiran yoo ṣe ju pe ki o gbagbọ lọ.”

Mo wipe, “Ohun gbogbo ti a le ṣe niyi. Ṣugbọn wo o arakunrin, nigba naa Ọlọrun ka a si fun un tabi o mọ igbagbọ Abrahamu. O fun ni edidi naa, àmì ti ikọla gẹgẹ bi edidi ti majẹmu naa. Ṣe ẹ ri, o fun un.... O wipe, ”Bayi, Abrahamu, mo ti ri igbagbọ rẹ, nitorina emi yoo fun ọ ni ami kan nisisiyi pe Emi ti gba ọ. Nitorina o kọ Abrahamu ni ila, eyi si jẹ edidi fun majẹmu naa.“

Ati ni ọjọ oni.... obinrin ko le si ninu majẹmu naa - ayafi obinrin ti o ni ọkọ. Ṣe iwadi. A ko le kọ obinrin ni ila; nitorina o gbọdọ wọle, nitori oun ati ọkọ rẹ jẹ ọkan. Wọn ko ki n ṣe meji mọ, wọn jẹ ọ̀kan. Ẹni melo ni o mọ eleyi? Iwe Mimọ sọ bẹ ẹ. Nitorina oun nigbati o ba ti ni ọkọ, lẹhin naa yoo di ọkan. Yoo si lọ sibẹ yoo si wo ibẹ ninu Iwe Timoti. O sọ ohun kanna, O wipe, “Ṣugbọn a o gba a la nipa ibimọ rẹ bi wọn ba duro ninu

igbagbọ ati ifẹ, ati iwa mimọ pẹlu iwa airekọja."

114 Bayi, ṣugbọn lẹhin naa, ikọla ti Majẹmu Laelae wa ninu ara, ṣugbọn ninu Majẹmu Tuntun, Joẹli sọ wipe "Emi yoo tú Ẹmi mi jade sori gbogbo eniyan, awọn ọmọkunrin yin ati awon ọmọbinrin yin yoo maa sọtẹlẹ." Bayi, ọrọ ti a n pe ni isọtẹlẹ ko tumọ si "Kọni," Isọtẹlẹ tumọ si boya "sọ ìrírì labẹ ìmísì," tabi "ki o sọ ohun kan ti o fẹ ṣẹlẹ." A si mọ wipe awọn wolii obinrin wa ni Majẹmu Laelae. Wọn ko le sọrọ sita ninu gbọngan, wọn ko le sọrọ sita ninu ile-ijọsin, ninu apejọpọ, gẹgẹ bi olukọ. Ṣugbọn, ṣe ẹ ri, Anna ati ọpọlọpọ ninu wọn ninu Tẹmpili, wọn jẹ wolii obinrin; ati Miriamu jẹ wolii obinrin tabi ohunkan bi eleyi. O ni Ẹmi yi ninu rẹ, eyi jẹ otitọ, ṣugbọn o ni iwọn ibiti o le de ninu gbọngan.

Awọn obinrin le jẹ wolii obinrin loni, gẹlẹ; ṣugbọn ko ki n ṣe olukọni, ati bẹẹbẹẹ lọ, lẹhin aga-iwaasu nibiyi. Ti o bạ se eleyi, iwọ yoo jẹ ki Bibeli tako ara rẹ. Bibeli ko le sọ ohunkan nibiyi, ki o si sọ ohun miran nibomiran. O gbọdọ sọ ohun kanna ni gbogbo igba tabi ko ki n ṣe Ọrọ Ọlọrun. Ṣe ẹ ri? Nitorina, "Awọn ọmọ yin ọkunrin ari awọn ọmọ yin obinrin yoo sọtẹlẹ; eyiti o tumọ si pe wọn yoo ṣe ọkan ninu mejeeji "sọtẹlẹ" tabi "ṣe ijẹri." Bayi, ẹ wo itumọ eleyi; ki ẹ si mu itumọ-ede Bibeli ki ẹ si ri boya eleyi ko jẹ otitọ bí. "Awọn ọmọkunrin yin ati awọn ọmọbinrin yin yoo sọtẹlẹ."

115 Bayi, Bibeli pẹlu sọ nipa obinrin kan ti o dibọn.... tabi ti o sọ wipe òun.... Eleyi yoo ṣiṣẹ papọ fun ijọ Aguda, yoo si ṣiṣẹ papọ pẹlu fun akori yi ti a n sọrọ nipa rẹ bayi. Ẹ jẹ ki a ṣi sinu Iwe Ifihan, ẹ jẹ ki a lọ si ori keji ẹsẹ ogun, nigbati a wa nibẹ ti a si sunmọ ọ, ki ẹ le ṣe akiyesi nibiyi ki ẹ si ri bi ohun yi ti jẹ ti èṣu to, nipa sisọrọ ni opin ọjọ yi ohun ti yoo ṣẹlẹ, bi awọn nkan yi i.... Ohun ti obinrin yi i yoo jẹ. Ranti, ijọ Aguda jẹ obinrin kan. A ṣẹṣẹ kà á ni, ṣe bẹ ẹ kọ? Ẹ tẹti si eleyi nisisiyi, bi o ti ṣe sọ. (Iwe Ifihan ori keji ẹsẹ ogun), "Ṣugbọn...." O n ba ijọ Tiatira yi sọrọ, ṣe ẹ ri. "Ṣugbọn...." Eyiti o jẹ ijọ ti o wà ni ààrin igba ijọ nibẹ, o la igba òkunkùn kọjá.

Ṣugbọn eyi ni mo ri wi si ọ, nitoriti iwọ fi aye silẹ fun obinrin ni Jesebẹli ti o pe ara rẹ ni wolii, o si n kọ awọn iranṣẹ mi o si n tan wọn lati maa ṣe agbere, ati lati maa jẹ ohun ti a pa rubọ sii oriṣa.

116 Bayi, ti o ba ṣe akiyesi kankan, wo awọn igba ijọ wọnyi, lẹhin naa a o pari. Ati ni owurọ a o mu nkan miran. Ṣe akiyesi. Ni abẹ ọpa fitila wura ti àgọ́ awọn Juu, ni inu rẹ lọhun, àkàrà-ìfihàn ati bẹẹbẹẹ lọ, awọn ọpa fitila meje wà. Gbogbo yin ni ẹ mọ eleyi, ṣe ẹ ri. Awọn igba ijọ meje ni o wa. Eyi sọrọ nipa awọn igba ijọ meje ti wọn jọra wọn. Bayi ti o bạ se akiyesi ninu Iwe Ifihan ori kinni, a ri Jesu ti o duro ni aarin awọn ìgbà ijọ meje, ọpa fitila wura - nigbati o yipada o si ri ẹnikan ti o dabi eyi ti a wọ ọ ni aṣọ pẹlu ohun.... Bawo ni o ṣe ri, o dabi iyawo ti o duro ni aarin awọn ọpa fitílà ti a yọ sita.

Wayi o, ninu Majẹmu Laelae, wọn yoo mu fitila kan wọn yoo si tan ina si i, wọn yoo si mu fitila miran wọn yoo si tan ina si i lati ara fitila àkọ́kọ́, wọn yoo si tan ina si omiran lati ara ekeji, wọn yoo si tan ina si ẹkẹta lati ara ekeji bi eleyi, titi ti wọn yoo fi tan ina si gbogbo ọpa fitila mejeje.

117 Ti o bạ se akiyesi lati ibẹrẹ, nigbati Ọlọrun bẹrẹ si n ṣe awọn nkan pẹlu Juu, ti wọn si la igba wura kọja, ati lẹhin naa igba okunkun ti o buru julọ ti Ọlọrun n ba awọn Juu lo, Ọlọrun wa pẹlu Juu, o jẹ ni igba ijọba Ahabu. Ti o ba si ṣe akiyesi, ti mo n ka awọn igba ijọ wọnyi nibẹ, o pada sinu rẹ lẹẹkan si. O wipe, nisisiyi, ni awọn nkan diẹ sẹyin, o wipe, bayi ni igba okunkun ẹgbẹrun kan ati ọgọrun-marun-un ọdún nibẹ.... tabi ni akoko Ahabu, ni akọkọ, awọn Juu, igba okunkun ti o buru julọ ti wọn ni ni igba ti Ahabu fẹ Jesebẹli ti o si mu ibọriṣa wa si Israẹli, ti o si mu ki gbogbo eniyan ṣe ijọsin tẹle Ahabu, ati tẹle Ọlọrun Jesebẹli. Ṣe ẹ ranti, wọn mú.... wọn kọ awọn ère oriṣa, wọn si wó awọn pẹpẹ Ọlọrun. Elisha si kigbe sita, o si jẹ oun nikan, Ọlọrun si ni ọgọrun meje ti wọn ko ti fi oribalẹ fun Balaamu rara. Ṣe ẹ ranti eyi? Eleyi jẹ apẹẹrẹ ijọ naa ti a ti yan ti wọn jade wá. Ṣe ẹ ri nibẹ, ẹ wo bi o tị se ri.

118 Bayi, ninu ijọ yi, ti o ba ṣe akiyesi ijọ akọkọ, ijọ akọkọ, ijọ Efesu, jẹ ijọ ti o tobi. O wipe, "O nì ìye, sibẹ." Ati ti o bạ se akiyesi ijọ kọọkan, iná wọn bẹrẹ si ni jó silẹ, jó silẹ, jo silẹ, titi ti o fi de Tiatira. Lẹhin naa ẹgbẹrun kan ati ọgọrun marun-un ọdun. Lẹhin naa o jade sita ni apa keji, "ina diẹ si wa. O fun eyiti a ni tẹlẹ ni agbara, ki a ma a ba yọ ọpa fitila rẹ kuro." O si bẹrẹ si ni lọ siwaju lẹhin naa titi ti o fi de igba ijọ Filadelfia, ati lẹhin naa o lọ si igba ijọ Laodikea.

119 Bayi, eyi ni ẹwà naa. Oo, akiika, mo kan fẹran eyi, Arakunrin Smith. Ṣe ẹ ri, ẹ wo eleyi. Nisisiyi, ninu igba ijọ yi, bi a tị se n lọ ninu rẹ.... Ṣe akiyesi rẹ bayi. Igba ijọ akọkọ jẹ Efesu, igba Ijọ Efesu. Bayi, ọkọọkan awọn ijọ wọnyi, titi ti o fi de ẹgbẹrun kan ati ọgọrun marun-un ọdun, ti o bạ se akiyesi.... Ẹ ka a nisisiyi nigbati ẹ ba de ile ni aṣalẹ yi, ti ẹ ba ni àkokò, tabi ni owurọ kùtùkùtù ṣaaju ki ẹ to wa si ile ijọsin, ni ori kinni, ori keji ati ori kẹta Iwe Ifihan. Ẹ o ri wipe, ọkọọkan awọn igba ijọ wọnyi, O wipe, "Ẹ ni okun kekere ẹ kò si sẹ́ orukọ Mi titi ti o fi dé ẹgbẹrun kan ati ọgọrun marun-un ọdun ti Tiatira, ìgbà òkúnkùn. Lẹhin naa o jade sita ni ibo miran, o si sọ wipe, "Iwọ ni orukọ kan pe iwọ n bẹ laaye, ṣugbọn iwọ ku."

120 Ati awọn wọnyi.... ko si ẹyọkan ninu awọn igba ijọ ti o ṣẹ́kù, ti wọn tabi igba ijọ Filadefia, ti wọn tún pada jẹ orukọ naa mọ́ lẹẹkansi. Wọn ko gba orukọ naa, nitori o lọ kuro ni akoko naa. Nisisiyi, Oo bi a ti ṣe le fi ṣe

akawe awọn ẹ̀kọ́ eke ti o n lọ lọwọ bayi, ninu ibẹ; o fi han pe ìyá ni, Ijọ Aguda naa iya gbogbo rẹ, bi o ti ṣe ri, “Iya Babiloni Ijinlẹ.” Eyi si jẹ.... wò, igba ijọ yi nigbati o jade wá, o ni imọlẹ kekere kan. O si bẹrẹ si ni jó lọ sílẹ̀, jo lọ silẹ lẹhinnaa o si lọ si inu ijọ ti a fi ọgbọn eniyan gbé kalẹ ni ibiyi, ẹgbẹrun kan ati ọgọrun marun-un ọdun. O si jade wa bayi: Ko ki n ṣe bi i ijọ Jesu Kristi Oluwa, ṣugbọn gẹgẹ bi ijọ Aguda. Bawo ni Luther ti ṣe jade wa? Gẹgẹ bi i ijọ Luther. Bawo ni ijọ Onitẹbọmi tị se jade wa? Gẹgẹ bi ijọ Onitẹbọmi. Ko ki n ṣe ni orukọ Rẹ, ko ki n ṣe ni orukọ Rẹ, orukọ miran: “Iwọ ni orukọ kan.” “Nitori ko si orukọ miran ni abẹ ọrun eyiti a le fi gba yin la, bikoṣe ni orukọ Jesu Kristi.” “O ni orukọ kan pe o n bẹ laaye, ṣugbọn iwọ kú,” eyi ni ohun ti o wa pẹlu ijọ ẹlẹkọ adamọ naa.

121 Oo, mo jẹ ọmọ ijọ Presibiteriani - iwọ si ti kú! “Oo, mo jẹ ọmọ ijọ Onitẹbọmi” - O si ti kú! O wa laaye nikan bi o ti ṣe wà laaye nigbati o wa sinu Kristi Jesu. Eyi jẹ otitọ. Ati baptisimu rẹ; omi, iribọmi èké, ti a fi omi wọn ọ lori, a da omi, dipo ki a ri ọ bọmi; ti a si n lo orukọ “Baba, Ọmọ ati Ẹmi Mimọ” dipo orukọ Jesu Kristi Oluwa. Gbogbo awọn nkan eke wọnyi ti wọn n jade wá, Bibeli n sọ otitọ, ti o n sọ nipa rẹ ni ọna ti o lagbara bi o tị se le lagbara to. Ati nibiyi a fi aye gbà wọn, “O dara, ijọ mi gba a gbọ ni ọna yi.” Ṣugbọn Bibeli sọ bayi. Ṣe ẹ ri? Ko si iru nkan bayi, ko si ìrú nkan bẹ ẹ.

122 Ko si ibikibi ninu Bibeli ti wọn ti yọ ahọn wọn jade ki wọn si gba ara mimọ Oluwa, ti alufa si mu ọti-waini ti o si pe e ni Ẹmi Mimọ. Ko si ibikibi ninu Bibeli ti wọn ti gba ọwọ́ ti wọn si fun ni ni ọwọ-idapọ ki wọn si pe e ni Ẹmi Mimọ. Ko si ẹnikankan ti o dide ki o si sọ wipe, “Nisisiyi, emi jẹ onigbagbọ,” ki o si gba Ẹmi Mimọ. Ti wọn bạ se bẹ ẹ, bayi ni Iṣe Awọn Apọsteli ori keji ti ṣe ka, “Ati nigbati ọjọ Pentikọsti si de, ni ojù ọ̀na ni alufa Romu kan wà, o si ni kọ́là ni ọrun rẹ ti a yípo. O rin jade o si wipe, ”Gbogbo yin ẹ yọ ahọ́n yin sita nisisiyi ki ẹ si gba ara mimọ Oluwa, ounjẹ-alẹ Oluwa akọkọ. Ṣe eleyi ko ha ki n ṣe ọ̀nà kan ti o yẹ ki a fi ka Iwe Iṣe Awọn aposteli ori keji?

123 O dara, ẹyin ara Protestanti ẹ ṣe ohun buburu. Ẹ wa si ibẹ ki ẹ si sọ wipe, “Bayi nigbati a lọ ba ẹyin ara ijọ Metọdisti, ẹ fun wọn ni ọwọ́ idapọ, ẹ si fi wọn si àyẹ̀wò oṣù mẹta.” Nibo ni ẹ ti ka eleyi ninu Iwe Iṣe Awọn Aposteli ori keji? Ṣe ẹ ri? Ibiti ẹ ti n ri eleyi? Ṣe ẹ ri?

O wipe, “Nigbati gbogbo wọn wa ni oju kan ti wọn si wa ni iṣọkan....!” Kò si bisọbu ki wọn tọ se eyi, ko si Alufa ki wọn to ṣe eyi, ṣugbọn “ìró kan wa lati ọ̀run bi i iro iji lile. O si kún gbogbo ile naa nibiti wọn joko.” Bi wọn tị se gba a niyi. Bẹẹni, sa, gẹgẹ bi iro iji lile ti o n bọ lati inu Ògo - ko ki n ṣe lati ọ̀na tabi lati awọn ijọ ẹlẹkọ adamọ kan. “Iwọ ni orukọ kan pe o n bẹ laaye, ṣugbọn iwọ ku.”

124 Ṣe ẹ ri, awọn ẹkọ kẹkọ yi ati ijọ ẹlẹkọ adamọ yin ti pagi-dina Ọlọrun kuro ni oju ọna bi eleyi titi ti, “A gbagbọ ninu eyi, a si gbagbọ pe ọjọ iṣẹ-iyanu ti kọja lọ,” Wolii eke ni o maa n sọ eleyi. Wolii eke ni o ma sọ fun ọ pe o le bọ ọwọ́ ki o si gba Ẹmi-Mimọ. Wolii eke ni o maa sọ fun ọ pe iwọ ti gba Ẹmi Mimọ ni kete ti o ba gbagbọ. Wolii eke ni o maa sọ fun ọ pe o gbọdọ da nkan si ọ lori tabi ki a fi omi wọn ọ lori dipo iribọmi. Wolii eke ni yoo sọ fun ọ pe ki a ṣe iribọmi fun ọ ni orukọ Baba, Ọmọ ati Ẹmi Mimọ, nigbati ko si Ayọka kankan fún u ninu Bibeli. Eyi jẹ otitọ. Ko si ayọka kankan ninu Bibeli ti o sọ fun ọ pe ki o ṣe iribọmi, ko si ibikibi ti a tị se iribọmi, yàtọ si orukọ Jesu Kristi nikan (Awọn ọmọ ẹyin Johanu, wọn si tun ni lati padawa ṣe iribọmi naa lẹẹkan si ni orukọ Jesu Kristi Oluwa ki wọn ba lee gba Ẹmi Mimọ). Eleyi jẹ otitọ.

Bayi, eleyi ko ki n ṣe ẹkọ ijọ ti a n pe ni Jesu Nikan. Mo mọ ẹkọ ijọ ti a n pe ni Jesu Nikan, eleyi ko ki n ṣe e. Eleyi kan jẹ ẹkọ Bibeli. Eyi jẹ otitọ.

Ṣugbọn bayi ni o ṣe ri, kini ohun ti o ṣe pẹlu rẹ? Iyá yin niyi. Iya awọn ẹkọ kẹkọ naa niyi.

125 Wayi iwọ wo inu Bibeli ki o si sọ fun mi ibiti a ti fọ́n omi si ẹnikẹni lori. Ijọ Metọdisti, Presibitarian, Ijọ Aguda, sọ ibikan ti a ti fọn omi si ori ẹnikẹni ninu Bibeli. Sọ fun mi ibiti a ti da omi si ẹnikẹni lori, ninu Bibeli, fun iwẹnumọ ẹṣẹ. Sọ ibikan, ṣe iwọ le e rii? Ti o ba ri i, wa si ọ̀dọ̀ mi, emi yoo si rin lọ si oju-popo yi pẹlu àmì kan ni ẹyin mi maa si sọ wipe, “Wolii eke kan” - Emi ti kuna. Tabi ti o ba ri ibikan ninu gbogbo Bibeli nibiti a ti se iribọmi fun ẹnikan ni orukọ Baba, Ọmọ ati Ẹmi Mimọ, ọ̀nà ti ida ọgọ́rin ninu yin ti ṣe iribọmi. Wa ibikan ninu Iwe-Mimọ nibiti a ti ṣe iribọmi fun ẹnikan ni ọ̀nà yi, emi yoo si fi àmì si ẹyin mi, “Wolii eke,” emi yoo si rin lọ si oju-popo pẹlu rẹ bi eleyi. Ki o si fi hàn fun mi nibiti a ti ṣe iribọmi fun ẹnikan, ninu ijọ tuntun, wọn ko nilo lati wa ki a si tún iribọmi ṣe fun wọn lẹẹkan si orukọ Jesu nikan, ṣugbọn ni orukọ Jesu Kristi Oluwa. Eleyi jẹ otitọ. Ẹ gbe eyi yẹwo ti ko ba ki n ṣe otitọ.

126 Ati nibiyi, kini ohun ti o jẹ́? O jẹ ìyá awọn agbere. Kini ohun ti o sọ ọ di Agbe..... Kini o sọ ọdi agbere? Ẹkọ opomulero rẹ. Kini o sọ wọn di agbèrè kan? Ẹkọ opomulero rẹ!

Idi niyi ti a ko fi fara-da ijọ ẹlẹkọ adamọ wọn ati ẹkọ adamọ wọn. A duro ni mimọ pẹlu Bibeli. Emi ko mọ bi o ti ṣe n gbe nipasẹ rẹ to, ṣugbọn o n kọni ni ẹkọ rẹ lọnakọna. Eyi jẹ otitọ. Eyi ku si ọ lọwọ. Emi ko le fi ipá mu ọ pe ki o gbe nipasẹ rẹ, emi kan le sọ fun ọ ohun ti otitọ jẹ. Idi niyi ti a ko fi jẹ ijọ ẹlẹkọ adamọ! Emi ko fẹ ki a ba ara wa jẹ ki a si lọ sinu iru nkan bi eleyi, mo ni lati fi awọn ẹkọ kẹkọ silẹ. O sàn fun mi ki n ba awọn

eniyan Oluwa péréte ti a ti kọ̀ silẹ. O san fun mi ki n duro ni mimọ ati ni aini-abawọn niwaju Ọrọ naa ati Ọlọrun, ki n si duro nibẹ! - Ki n si duro nibẹ ko si ẹ̀jẹ̀ ẹnikẹni ninu aṣọ mi. Idi niyi ti a fi duro si Agọ ijọsin Branham. Idi niyi ti a ko fi jẹ ijọ Assẹmbili. Idi niyi ti a ko fi jẹ Ijọ Isọkan. Idi niyi ti a ko fi jẹ ijọ ti a n pe ni Jesu Nikan. Idi niyi ti a ko fi jẹ ijọ Mẹtodisi. Idi niyi ti a ko fi jẹ ijọ Onitẹbọmi. O kan jẹ agọ ijọsin kekere nibiyi. A ko ni ijọ ẹlẹkọ adamọ kankan rara. A wa ni ominira, ninu Kristi. Idi niyi ti a fi duro ni ọ̀nà ti a fi duro. Ọlọrun si ti bukun fun wa, Ọlọrun si ti ran wa lọwọ.

127 Nisisiyi, a le sọ fun yin idi ti a fi n gba ara Oluwa, idi ti a fi n ṣe ìwẹsẹ̀, idi ti a ko fi àyè gba ki awọn ọmọ-ijọ ti a mọ pe wọn wa ninu ẹ̀sẹ̀ gba a. Idi niyi ti eleyi fi to bi i ọsẹ meji tabi mẹta ti mo fi n lọ lati ọ̀dọ̀ ọmọ-ijọ kan lọ si ekeji, nibiti ẹ ti n ni ariyanjiyan kekere ni aarin yin pẹlu. Mo n lọ kaakiri, ẹnikan ko ni bá ẹnikeji rẹ sọrọ, iwọ yoo pade ọmonikeji loju-popo iwọ yoo si yi ori rẹ pada, ki oju ki o ti ọ! Ẹniti o ti o mu ago ibukun Ọlọrun, ni ori-pẹpẹ nibiyi, a si pe ọ ni arakunrin ati arabinrin, ati lẹhin naa ẹ o gbe ẹ̀rọ-tẹlifónù ẹ o si sọrọ ibajẹ nipa ẹnikeji rẹ - ko tọ ki a pè ọ ni Kristẹni nigbati o ba ri bi eleyi. Eyi jẹ otitọ. Ẹ mu awọn ẹ̀rọ-tẹlifónù kuro. Ti o ko ba le sọrọ ti o dara nipa ẹnikan, nigbanaa maṣe sọ̀rọ̀ kankan rara. Ranti, Ọlọrun yoo mu ọ wa si idajọ. Niwọn igbati ti iru ẹmi bayi ba si wa ninu rẹ, iwọ mọ̀ pe o ko tọ́ pẹlu Olọrun.

Ti iwọ ko ba ni ìmọ̀lara....

128 Ti eniyan kan ba kuna; iwọ lọ ba a, ki o si ba làjà. Ti iwọ ko ba le ba a laja mu ẹnikan lọwọ pẹlu rẹ. Idi niyi ti Ọlọrun ko fi le e ba ijọ Rẹ wí, nitoripe ẹ ko ṣe e ni ọ̀nà ti o tọ́. Dipo ti ẹ fi n lọ sori ẹ̀rọ-ibanisọrọ ti ẹ si n sọrọ nipa eleyi, ati awọn ohun ti o n ṣẹlẹ, ti ẹ si da ẹgbẹ kereje silẹ ati bẹẹbẹ lọ bi eleyi, dipo ti ẹ fi n ṣe eleyi, kilode ti ẹ ko fi ṣe ohun ti Bibeli sọ? Ti a ba mu awọn arakunrin kan ninu iṣubu kan, lọ ba a! Ki o si ri ti iwọ ko ba le mu iru ẹni bẹẹ pa da bọ si po. “O dara, bayi o ṣe eleyi si mi....” emi ko bikita ohun ti o ṣe, lọ ba a lọnakọna. Maṣe sọ wipe ohun ni yoo wa ba ọ. Iwọ ni yoo lọ si ọdọ rẹ ti o bą se ohun ti o kuna. Iwọ yoo sọ wipe, “O dara oun ni o wa ninu ìkùnà, oun ni o yẹ ki o wa ba mi.” Eleyi kọ ni ohun ti Bibeli sọ. Bibeli sọ wipe iwọ ni ki o lọ ba a. Ti o ba kuna, iwọ ni yoo lọ ba a.

Ati lẹhin naa ti ko ba tẹti si ọ, lẹhin naa mu ẹnikan pẹlu rẹ fun ẹ̀rí.

Ati ti ko ba ri ẹ̀rí naa lẹhin naa, sọ ọ. “Bayi emi yoo mu olusọ-aguntan.” Nigba naa iwọ sọ ọ fun un, sọ wipe, “Emi yoo sọ ọ fun ijọ. Ati laarin ọgbọn ọjọ si akoko ti a wa yi, ti ẹyin arakunrin ko ba yanju eyi laarin ara yin.... Arakunrin yi nifẹ lati ba yin laja. Ẹyin ko ṣe eleyi. Ti ẹyin ko ba si ba a laja laarin ọgbọn ọjọ lẹhin naa kini ohun ti yoo ṣẹlẹ? Iwọ ko ki n ṣe ọkan ninu wa.”

129 Bibeli sọ wipe, “Ti ko ba si gbọ ti ijọ, lẹhin naa ki o di keferi ati agbowo ode si ọ.” Ṣe ẹ ri, niwọn igbati arakunrin ba wa ni abẹ́ abo ijọ, ẹjẹ Kristi n dabo bo ọ. Idi niyi ti ijọ ko fi tẹsiwaju ni ọna ti o yẹ. Bayi, eyi ni ẹkọ opomulero ti Onitẹbọmi..... ti ijọ Onitẹbọmi, tabi ijọ Agọ-ijọsin Branham nibiyi.... ti o ba ṣe eyi! Ṣe ẹ ri, kini idi ti....

130 Iwọ de ibiyi, fun apẹrẹ, ọkunrin meji, bi i Ọgbẹẹni Leo ati emi, o dara, o gbọ ti emi ati emi sọ, “o dara, o ṣe ohun ti ko dara si mi!” Eyi ko ṣe iyatọ kankan. O yẹ ki emi lọ ba a. O jẹ ara ijọ yi i. O ti di Kristẹni. O n gba ara Oluwa nibiyi ni ori-ila pẹlu mi. A si ti jijọ ṣe iribọmi ni orukọ Jesu Oluwa, ẹ rin bi arakunrin niwaju ara yin; lẹhin naa ohunkan yoo ṣẹlẹ.

Ko ki n ṣe eniyan... ida aadọrun ninu ọgọrun igba ni o jẹ wipe èṣù ni o wọ aarin awọn eniyan naa, èṣù ni. Ati niwọn igbati ẹ ba gba èṣù laaye ki o ṣe eyi, o n ṣe arakunrin rẹ ni ibi. Eyi jẹ otitọ.

131 O dara, nkan kan ṣẹlẹ si Leo ati emi, ẹ jẹ ki a yanju rẹ laarin ara wa. Ti iwọ ba ri wipe nkan kan wa, o jẹ ojuṣe rẹ lati wa si ọdọ wa, ki o si sọ wipe, “Ẹyin ọmọkunrin mejeji yi ẹ wa si ibiyi ki ẹ si jijọ laja. A o yanju nkan yi.” Bayi, lẹhin naa ti o ba wa si ibẹ, ti o si wa ri lẹhin naa, ibiyi ni a wà, emi sọ wipe, “o dara, ohun akọkọ, awa.... a ko ri i bakanna,” lẹhin naa iwọ yoo wá si ile-ijọsin bi eleyi.

Ati lẹhin naa ti.... niwọn igbati ẹ ko bą se ohunkohun nipa rẹ, bi-o-tìlẹ́jẹ-wipe ẹjẹ Jesu Kristi ṣe àbò fun awa mejeji. Ṣe ẹ ri? Ṣugbọn lẹhin naa àrùn jẹjẹrẹ atijọ yi yoo bẹrẹ arun jẹjẹrẹ omiran, ati gbogbo rẹ pata yoo wą se aisan, gbogbo ijọ. Lẹhin naa ẹ o de ibikan ẹ o si wọ inu ile-ijọsin, gbogbo rẹ yoo si tutu; ẹ ni lati jẹ ki olutọju kọkọrọ ile-ijọsin wa fọ́ gbogbo ỳìnỳiń ti o wa ni ẹnu̟-onà ki awọn ọmọ-ijọ to ráyèè wọlé. Bayi, ẹ mọ pe eyi jẹ otitọ. O si tutu: Ẹnikan joko ti ọ, ṣe ẹ mọ, ko si ni sọ ohunkohun. “A maa n jẹ ẹni ẹmi nigbakan ri.” O dara, kini ohun ti o ṣẹlẹ? Ẹ sáré daada, kini ohun ti o ṣẹlẹ? Ṣe ẹ ri? Ẹṣẹ yin ni o ya yin kuro! Ọlọrun yoo da yin lẹjọ nitori rẹ, arakunrin!

Bayi emi yoo yanju nkan yi.

132 Ko si ohunkohun ti o kuna pẹlu mi, ko si ohunkohun ti o kuna pẹlu Leo - èṣù ni o wọ aarin wa. Eyi jẹ otitọ. Ẹ yanju rẹ. Iwọ lọ ba a. Lẹhin naa ti ko ba tẹti silẹ (tabi ti emi ko ba tẹti silẹ, eyikeyi ọna bi o ba ti ṣe ri) lẹhin naa sọ fun ijọ. Ti ko ba wa ba ijọ làjà laarin ọgbọn ọjọ, lẹhin naa o ti kuro labẹ àabo Jesu. A ti tu silẹ. Eyi

jẹ otitọ gẹlẹ. Lẹhin naa ṣe akiyesi ohun ti yoo ṣẹlẹ. Jẹ ki Ọlọrun ṣe ijiya lẹhin naa. Ẹ ti yọ ọwọ yin kuro. Ẹ ti ṣe iwọn ti o dara ju ti ẹ le ṣe. Lẹhin naa ẹ jẹ ki Ọlọrun fọwọ kàn án fun ìgbà diẹ. Oun yoo fi le èṣù lọ́wọ́. Yoo wa lẹhin naa. Ti ko ba wa, a o ge ọjọ aye rẹ kúrú.

133 Iwọ ranti ninu Bibeli nibiti arakunrin kan wa ti ko mu ohun gbogbo tọ pẹlu Ọlọrun? Ẹni melo ni o ranti iṣẹlẹ yi? O n ba ìyáwo baba rẹ lopọ, o si nira fun wọn lati tọ ọ sọ́nà. Paulu sọ wipe, "Ẹ tu silẹ fun èṣù - fun iparun...." Ẹ ṣe àwárí rẹ, ninu Korinti keji, a mú u tọ.

134 Mo ni arakunrin kan, ọrẹ mi ti o dara, mo fẹ pe orukọ rẹ nibiyi. O jẹ arakunrin oniwaasu. Ati arakunrin oniwaasu yi, orukọ rẹ ni Arakunrin Rasmussen. Ọpọlọpọ ninu awọn oniwaasu ti o joko nibiyi ni aṣalẹ yi, orukọ rẹ wa ninu iwe yin. O jẹ apejọpọ ti o gba orisirisi ẹgbẹ́ Kristẹni láyè - eyiti o wa ni ilu Chicago. O si wo. O ni ọmọkunrin kan, ojiṣẹ Ọlọrun, o si lọ o si fẹ́ ọmọbinrin Katoliki kan. O si bẹrẹ bi eleyi, o si lọ lati ṣe èyí, tọun, ati omiran, ati gbogbo nkan - O si bọ sinu awọn wahala. Baba rẹ si lọ ba, o wipe, "Bayi wo ibiyi, ọmọ, ṣe iwọ yoo ba baba rẹ laja?" O pe ijọ wọn ni awọn ti ó gba ẹsin ni ọna òdì, baba rẹ. O wipe, "Wo ibiyi, ṣe iwọ yoo mu nkan yi í tọ́ pẹlu ijọ yi?"

O wipe, "Nisisiyi, baba, iwọ ni baba mi, emi ko si fẹ wọ inu wahala kankan pẹlu rẹ."

135 Eyi dara, o lọ o si mu ọkan ninu awọn diakoni o si lọ si ile rẹ. O wipe "Wesley, mo fẹ ba ọ sọrọ." O wipe, "Ṣe iwọ yoo mu nkan yi tọ́ pẹlu ijọ?" O si fun un ni idahun kukuru meji bi eleyi. O wipe, "Ranti, Wesley, Emi ni olusọ̀-guntan ijọ naa. Emi ni baba rẹ, ṣugbọn emi yoo ṣe ohun ti Oluwa sọ fun mi pe ki n ṣe! Emi fun ọ ni ọgbọ̀n ọjọ lati mu ohun tọ́ pẹlu ijọ naa, tabi a o le ọ kuro ninu niwaju Ọlọrun. Ọmọ mi ni o jẹ, Olugbala mi si niyi: o wipe, "Mo nifẹ rẹ. O si mọ wipe mo nifẹ rẹ. Wesley, emi yoo kú fun ọ bayi, ṣugbọn o ni lati wa gẹlẹ pẹlu Ọrọ Ọlọrun, ṣe ẹ ri." O wipe, Emi jẹ olusọ-aguntan, mo si jẹ Olusọ-aguntan agbo naa; ti iwọ ba si jẹ ọmọ mi tabi ohunkohun ti o le jẹ, o gbọdọ wa ni ibamu pẹlu Ọrọ Ọlọrun. Ti iwọ ko ba ṣe èyí, lẹhin naa emi ko kun oju-oṣùwọn lati jẹ Olusọ-aguntan Rẹ.

Akiika, Olusọ-aguntan ti o jẹ olootọ niyi. Ọkunrin niyi. Ṣe iwọ ko ro bẹ ẹ? Ọkunrin làdá o sọ fun ọmọ rẹ ọkunrin pe, o si ba a ninu jẹ, o wipe. Ṣugbọn o wipe, "Kini idi, tani ẹni ti iwọ fẹ ba ninu jẹ, ṣe ọkunrin naa tabi Olugbala rẹ?"

136 Nitori naa o sọ wipe, "Lẹhin naa o tẹsiwaju."

O si sọ wipe, "Oun ko ni ṣe eyi. Mo si sọ fun ijọ, mo si sọ wipe, "Ọmọ mi ọkunrin Wesley, o kọ lati gbọ temi ninu ọ̀ràn yi. O kọ lati gbọ ti awọn diakoni. Ẹ si jẹ ẹlẹ́ri si eyi, Arakunrin lagbaja ati arakunrin tamẹdo? [Bẹẹni, emi niyi,] O dara, ni agogo mẹjọ ni ọjọ isinmi ti o n bọ̀ ọ̀sẹ̀ mẹrin si igba ti a wa yi. Ti ko ba mu eleyi tọ pẹlu ijọ yi, a o tú Wesley ọmọ mi silẹ fun èṣù fun iparun tị eran-ara rẹ. Ẹjẹ yi, ẹjẹ Jesu Kristi ati ti ijọ yi, ko ni dáàbò bo o mọ."

137 Alẹ ọjọ naa si de, o duro si ibi aga-iwaasu, o wipe, "O ṣi ni iṣẹju meji si i." Akoko naa si de, o wipe, "Bayi gẹgẹ bi ọmọ mi Wesley Rasmussen, sọ fun apejọpọ yi ati si Ọ, Ọlọrun Olodumare, a ti ṣe gbogbo ohun ti a le ṣe. Gẹgẹ bi Ọrọ Rẹ ati ofin Ọmọ Rẹ, Olugbala wa, ti ṣe fi silẹ fun wa, awa nisisiyi.... mo tú ọmọkunrin mi, ati ijọ yi pẹlu mi, silẹ fun èṣù fun iparun ẹran ara rẹ, pe ki a le gba ọkan rẹ la." Ohun ti o sọ nikan niyi. Ko si ohunkohun ti o ṣẹlẹ fun bi ọ̀sẹ̀ kan tabi meji, boya oṣu kan tabi meji.

138 Ni alẹ ọjọ kan Wesley ṣe aisan. Ati nigbati o ṣe aisan, o bẹrẹ si ni ṣe aisan si. O pe dọkita. Dọkita goke wa o si yẹ ẹ́ wo. O ni aisan iba ti o to iwọn ọgọrun ati marun-un, wọn ko ri idi fun eyi. O kan n tubọ ṣe aisan si ni. Dọkita sọ wipe, "Ọmọkunrin, emi ko mọ ohun ti o ṣẹlẹ si ọ." Ohun ko mọ ohun ti yoo ṣe. O wipe, "A o pe akọ́ṣẹ́-mọṣẹ́." Wọn pe akọṣẹ-mọṣẹ kan, akọṣẹ-mọṣẹ naa si wa sibẹ̀. Wọn mu u lọ si ile-iwosan, wọn si se ayẹwo ara rẹ, ati ohun gbogbo ti o kù, o wipe, "Emi ko le sọ fun ọ, ọmọkunrin naa fẹ dabi ẹnipe o fẹ ku." Iyawo rẹ duro nibẹ, o si n kigbe ati ohun gbogbo bi eleyi. Ati awọn ọmọ rẹ duro yika ibùsùn, ati onikálùkù bi eleyi. O wipe, "O n ku lọ, gbogbo rẹ niyi." O wipe, "Onka mimi rẹ ati bi o tị se n mi n lọ silẹ ni gbogbo igba."

O wipe, "pe baba; Oo, bẹẹni! Ọna ti o yẹ ki a gba fi ṣe e niyi. Ohun niyi. "Pe baba." Baba rẹ si sare lọ si ibẹ ni ile-iwosan ni kiakia lati lọ ri i. O wipe "Baba, emi ko le e ṣe e nisisiyi, ṣugbọn Ọlọrun yoo gbọ awọn ọ̀rọ̀ mi. Emi yoo mu ohun gbogbo tọ́. Emi yoo mu tọ, bẹẹni, Emi yoo ṣe e." Bẹẹni, sa, arakunrin. Nibẹ ni mimi rẹ bẹrẹ si ni pada bọ sipo.

Ati ni ọjọ isinmi ti o tẹ le e, o duro niwaju ijọ, o wipe, "Emi ti dẹṣẹ niwaju Ọlọrun ati ni iwaju ijọ yii. Mo kọ lati gbọ ọrọ Olusọ-aguntan. Mo kọ lati gbọ ti diakoni nibiyi." O si sọ wipe, mo bere pe ki ijọ ko forijimi fun ibi yi ti mo ṣe." Bi eleyi. O wipe, "Ọlọrun ti da ẹmi mi si." Mo si sọ fun ọ, o mu igbe-aye rẹ tọ gẹlẹ. Ohun ti o yẹ ki ẹ ṣe niyi, wo o. Ṣe ẹ ri? Iwọ.... Ti iwọ ba le ṣe e ni ọna ti Ọlọrun! Ṣe ẹ ri?

139 Bayi, ṣe ẹ ri, ọna ti a gbà lati ṣe e, a ni ipade igbimọ, a si sọ wipe, "o dara, nisisiyi, ṣe a le pá a mọ...." Emi ko sọ wipe agọ-ijọsin, ṣugbọn ohun ti mo fẹ sọ ni awa eniyan ijọ Protẹsitanti, a ni ipade igbimọ. "Ati kini

iwọ ro nipa Jones? Kini ẹyin ro pe a le ṣe pẹlu rẹ? Mo ro pe yoo ṣe daradara ni jijẹ ọmọ ẹgbẹ ijọ Mẹtodisi ju bi o tị se si wa lọ.” Bayi ni o ti ṣe ri. Eyi kuna! Idi niyi ti a ko fi gbọdọ tẹle aṣa wọn. Ati awọn bisọbu, a ni lati pe e, tabi awọn (kini ẹ n pe awọn olori ijọ agbegbe ninu ijọ ẹlẹkọ adamọ yi?) Olori awọn ijọ Presibi ti o wa ni agbegbe, pe e ki o wa wo ìhuwàsí ọkunrin yi.

Bibeli sọ fun wa ohun ti a o ṣe. Idi niyi ti a ko fi lọ ninu ìwà-ìbàjẹ́ awọn ijọ ẹlẹkọ adamọ wọn. A duro ni ominira kuro ninu nkan yi. Amin. Ẹ maṣe binu si mi, ṣe ẹyin binu? Ẹ maṣe ṣe eyi. O ṣé e ṣé e ki emi gba ọpọlọpọ ibeere ti o dara ni alẹ ọla, ṣugbọn a o .... Eyi jẹ otitọ. Ṣe ẹ ri.

140 Ranti.... rara, mo sọ eleyi nisisiyi. Ẹyin eniyan ti ẹ wa nibiyi lati awọn ijọ ẹlẹkọ adamọ miran, ijọ ẹlẹkọ adamọ yin.... Arakunrin, emi ko sọ wipe ẹ ko ki n ṣe Kristẹni. Emi ko sọ wipe ijọ ẹlẹkọ adamọ yin ko ni awọn ẹgbẹgbẹrun awọn Kristẹni ti wọn nifẹ ninu ile-ijọsin yin. Emi n gbiyanju lati sọ idi ti a ko fi jẹ ijọ ẹlẹkọ adamọ. “Nitori emi ko kan le duro fun eyi. Rara, sa, o daju pe emi ko lee. Wọn maa n gbiyanju lati sọ ohun ti iwọ yoo ṣe fun ọ. Ti Ọlọrun ba pe mi lati waasu Ihinrere, lẹhin naa emi yoo waasu rẹ ni ọna ti Ọlọrun sọ fun mi pe ki n ṣe e. Bi wọn tị se kọ ọ niyi ninu Bibeli. Ti ko ba wa ni ibamu pẹlu eyi, lẹhin naa o jẹ wipe ohun..... Ọlọrun yoo dami lẹjọ fun eyi. Ṣugbọn ti mo ba ri ìkookò ti o n bọ, tabi ti awọn ọ̀tá ba n bọ, ti mo ba kùnà lati kìlọ̀ fún wọn, lẹhin naa Ọlọrun yoo bèrè lọwọ mi. Ṣugbọn ti mo ba kilọ fun ọ, lẹhin naa o ku si ọ lọwọ nigba naa. Ṣe ẹ ri?

141 Ranti, “ni opin ọjọ́, igba ewu yoo dé. Awọn eniyan yoo jẹ olufẹ ti ara wọn, ahalẹ̀, agberaga, asọrọ-buburu.” Ṣe ẹ ri, asọrọ-buburu: Oo, awọn ẹgbẹ ti ko loye. Ọjọ iṣe-iyanu ti kọjá. Ko si irú nkan bi eleyi.“ O jẹ wolii atijọ. ”Nisisiyi, a mọ pe awọn obinrin wa ti ni óye gẹgẹ bi awọn ọkunrin wa ti ni òye.“ Emi kò sọ pe ko ri bẹẹ rara, ṣugbọn Bibeli Ọlọrun sọ wipe ẹ maṣe mu wọn wa si ibi àga iwaasu. Eleyi tó fún mi, ṣe ẹ ri, eyi jẹ otitọ. O dara, ṣe ẹ ri? O si sọ wipe, ”O dara, nisisiyi, awọn ijọ ẹlẹkọ adamọ wa, a ni awọn eniyan pupọ ti wọn dara gẹgẹ bi ẹ ti ni i ni agọ-ijọsin nibẹ.“ Emi ko sọ eleyi rara, ṣugbọn Bibeli sọ lodi si ijọ ẹlẹkọ adamọ. Eyi jẹ otitọ. Ati nitorina, nisisiyi, emi ko sọ wipe ẹ ko ni awọn ọmọ ijọ ti o dara ninu ijọ yin. Eyi jẹ ohun iyanu. Wọn jẹ awọn eniyan ti o dara. Lara awọn eniyan ti o dara julọ, mo maa ń pade wọn, ni gbogbo awọn ijọ aguda ati gbogbo awọn ijọ. Gbogbo wọn, mo maa n pade awọn ọmọ ijọ ti o dara.

142 Bayi, ọna ti a o gba lati fi mu eyi wa bayi, ẹyin ọrẹ, ti Oluwa ba fẹ́, ninu awọn ọpọlọpọ ẹ̀kọ́ ti o n bọ yi - boya emi yoo jẹ ki ẹ mọ ni owurọ ọla boya a o ṣe é ni ọ̀san tabi a kò ni ṣe e, ṣe ẹ ri, lati le mu u jade. Idi ti a fi n gbiyanju lati ṣe eyi, mo fẹ mu wa si oju kan bayi. Nisisiyi, ti o ba fẹ́ mu ẹnikan wa pẹlu rẹ, a ki ọ kaabọ gẹlẹ pe ki o ṣe bẹ. Ṣugbọn ranti nisisiyi, maṣe lọ pẹlu igbiyanju lati wa aṣiṣe, tabi ki o wa sibiyi.... emi kàn n ba awọn ọmọ-ijọ mi sọrọ, ṣe ẹ ri. Emi ko ki n kọni lẹkọ ni ita ayafi ninu apejọpọ mi nibiyi; nitoripe ojuṣe awọn ọkunrin miran niyi, oun ni olusọ aguntan agbo naa. emi kan jẹ ti....

[Alafo wa ninu ohùn ti a gbà silẹ.]

143 ..... a pada si Jẹnẹsisi. Yoo mu ohun gbogbo tọ́ yoo si wa ri ibiti o wa. Bayi, a n pada si Jẹnẹsisi lati ṣe awari idi ti ọmọ àlè ko fi ni le wọ apejọpọ ijọ Oluwa fun iran mẹrinla. Bi o ti ṣe.... Eyi yoo jẹ fun irinwo ọdun ki ẹ̀ṣẹ̀ naa to le parẹ́. A o ṣe àwári bi a o ṣe bẹ aiṣododo awọn obi wò lara awọn ọmọ ati ọmọ, ati bi eleyi ṣe bẹ̀rẹ̀ ni Jẹnẹsisi, ati bẹẹbẹẹ lọ.

144 Lẹhin naa ẹ o ri bi (a o pada sẹyin) pe Ọlọrun, ṣaaju ipinlẹṣẹ aye ṣaaju ki a to da ẹya ẹda ti o kere julọ ni ibẹrẹ, ṣaaju ki a to da ìwọ̀n ina ti o kere julọ. Ọlọrun mọ gbogbo ẹda kọọkan ati ohun gbogbo ti yoo wa lori ilẹ aye. Ṣe ẹnikẹni wa nibi....? O ko le e salaye ohun ti ọrọ naa jẹ́, ki o si fọ ọ silẹ, ki o si tumọ ọrọ naa ti a n pe ni aìlópin jẹ́. Gẹgẹ bi o tị se yi oju ẹrọ yiya fọto rẹ si “ailopin.” O dabi “lati ibẹ lọ.” Gbogbo rẹ niyi, ṣe e ri, ninu ọ̀kan ailopin wa, a ko le loye ohun ti ọkàn ailopin wa yoo gbà. Ṣe ẹ ri, a ko le ṣe eyi. Iwọ ko le ṣe èyí, ṣe ẹ ri? Ṣugbọn ti iwọ ba kan le loye, duro ninu Ẹmi, iwọ le ni imọlara rẹ nibẹ, ati lẹhin naa lọ sinu iwe mimọ, iwọ yoo si ri nisisiyi, ṣe ẹ ri, ṣaaju ki a to fi ipinlẹ aye sọlẹ....

145 Bayi, Bibeli sọ wipe Jesu Kristi ni ọdọ Aguntan Ọlọrun (Bayi tẹti silẹ daada, ti awọn miran ninu yin ko ba ni si ni ibiyi lati gbọ opin rẹ.) Bibeli sọ wipe Jesu Kristi ni ọdọ-Aguntan Ọlọrun ti a pa lati ipilẹṣẹ aye. Ṣe eyi jẹ otitọ? Nigba wo ni a pa A? Lati ipilẹṣẹ.... o jẹ ayé. Ti o ba jẹ wipe a dá eyi lati ara awọn ohun ti a fi da aye ti o kere julọ eyiti o ti fọ́ ti o fa oorun papọ ṣaaju ki o to di eyi, lẹhin naa ṣaaju ki a to ni ẹya ti o kere julọ ti a fi da aye ti o kọ́kọ wa ninu oorun (ti eleyi ba jẹ ẹya ina ti o kere julọ ti o kọkọ wà ṣaaju oorun), eyiti yoo jẹ ọgọrun bilioni trilioni trilioni trilioni awọn ọdun sẹyin, ṣaaju ki ẹyọ ina ti o kere julọ ki o to wa, a pa Kristi. Nigbati ọkan nla Ọlọrun duro lori ohun kan, o jẹ iṣẹ ti a ti ṣe pari. Nigbati Ọlọrun sọ wipe, “Ẹ jẹ ki,” O jẹ iṣẹ aṣepari. Ti yoo ba gba ọgọrun bilioni ọdun lati ṣe eyi, o jẹ iṣẹ ti a ṣe pari tẹlẹ ni kete ti O ba ti sọ ọ. Ati nigbati a pa ọdọ-Aguntan naa lati ipilẹṣẹ aye, Bibeli kannaa, Ẹmi kannaa, ti a kọ silẹ o si sọ wipe, “A ti kọ orukọ wa sinu iwe Iye Ọdọ Aguntan ṣaaju ipilẹṣẹ aye.”

Nitorina ọkunrin ti o kọrin naa “Orukọ Titun kan wa ti a kọ silẹ ninu Ogo,” O ni itumọ ti o dara, ṣugbọn ko ba Iwe Mimọ mu. Sẹ ẹ ri? A kọ orukọ yi silẹ ninu Ogo nigbati aye.... nigbati ṣaaju ki aye to bẹrẹ. Nigbati a pa Ọdọ-Aguntan naa, a kọ orukọ wa silẹ ninu Iwe-Iye ọdọ Aguntan.

146 Ẹ jẹ ki n wa ayọka Iwe-Mimo kekere kan fun yin. Ṣe ẹyin yoo duro diẹ fún iṣeju kan? Eleyi wa si ọkan mi bayi. Mo ro wipe emi le lọ sinu rẹ. Ko dami loju. Ati nisisiyi mo tọrọ gafara pe emi da yin duro fun akoko pipẹ́, ṣugbọn mo ti sọ fun yin pe yoo di ọ̀gànjọ́-òru, ko si buru tó bẹ́ ẹ̀. Ṣugbọn mo nifẹ lati sọ eleyi, ẹsẹ Iwe Mimọ kan pere fun u. Ẹ ṣi pẹlu mi nisisiyi sinu Iwe Romu, mo si fẹ ki ẹ ka eleyi pẹlu mi. Bayi, ẹ jẹ ki a ri i, Iwe Romu, ti emi ba le ri i, O wa nibiyi. Bayi ẹ jẹ ki a ka Iwe Romu ori kẹ́jọ, ẹ jẹ ki a bẹrẹ lati ẹsẹ keji-din-lọgbọn ori kẹjọ ti Iwe Romu. Mo si fẹ ki ẹ ka a pẹlu ọkàn adura pẹlu mi nisisiyi. Ẹ tẹti si ibiyi ohun ti Ọlọrun sọ nikan bayi.

Awa si mọ pe ohun gbogbo li o n siṣẹ pọ si rere fun awọn ti o fẹ Ọlọrun, ani fun awọn ẹniti.... a pe gẹgẹ bi ipinnu Rẹ.

Nitori awọn ẹniti o ti mọ̀, tẹ́lẹ̀.... [Ṣe ẹyin n kà pẹlu mi?]

Nitori Oun.... awọn ẹniti o ti mọ̀ tẹlẹ, li o si ti yan tẹlẹ lati ri bi aworan ọmọ rẹ, ki oun le jẹ akọkọ laarin awọn arakunrin pupọ.

Awọn ti o si ti yan tẹlẹ, awọn li o si ti pè: awọn ẹniti o si ti pè, awọn li o si ti dalare: awọn ẹniti o si ti dalare, awọn li o si ti ṣe logo.

147 Lati ipilẹṣẹ ayé nigbati Ọlọrun wo ilẹ.... Bayi, Ọlọrun ko ṣeto iṣẹ rẹ bayi, yoo wipe, “O dara, nisisiyi, Emi yoo ṣe.... Oo, kini ohun ti a o ṣe bayi?” Ṣe ẹ ri? Kosi ohunkohun....

Ranti, aiṣododo, ẹṣẹ, jẹ ododo ti a yipada. èṣù ko le dá ohun kan. Ṣe gbogbo wa ni eyi yé? Eyi jẹ ẹkọ opomulero ti ijọ. Èṣù ko le da ohun kan. O le yi ohun ti Ọlọrun dá pada. Nisisiyi, kini, iyipada kuro ninu ojulowo? Nibiyi, gbogbo yin ni ẹ jọ àgbàlagbà, o fẹrẹ jẹ gbogbo yin. Ẹ tẹti silẹ si eyi. A jẹ awọn ẹni ti o ti ṣe igbeyawo. Ẹyin ọkunrin ti ẹ ti ṣe igbeyawo ati ẹyin obinrin ti ẹ ti ni ọkọ ẹ le jijọ gbe papọ gẹgẹ bi ọkọ ati aya, awọn obinrin yi si ri bakanna bi ìgbà ti wọn ko ti.... wọn si jẹ wundia niwọn igbati ẹ ba duro ti ọkọ yin. Eyi jẹ otitọ. Bayi, eleyi ba ofin mu, gbogbo rẹ si dára. Ọlọrun fi aṣẹ si i lati ṣe eyi. Obinrin miran le e ṣe ohun kannaa gẹgẹ bi ìyàwo rẹ. Ọkan ninu wọn, o jẹ ododo niwaju Ọlọrun; ati`iṣe kannaa pẹlu obinrin miran, a o da o lẹjọ si ikú niwaju Ọlọrun. Kini ohun yi? O jẹ òdodo ti a yi? O jẹ òdodo ti a yi padà, ṣe ẹ ri, ododo ti a yi padà.

148 Bayi, èṣù ko le da ohun kan, ṣugbọn o le yi ohun ti Ọlọrun ti da pada.

Iru irọ́ wo ni eyi? O jẹ otitọ ti a yi pada. Ẹnikan sọ wipe, Oo, “O jẹ alẹ́ ọjọ Abamẹta, agogo mẹsan owurọ, bẹẹni. Bill Branham wa ni ilu Jeffersonville.” Eyi jẹ otitọ. “Ni ile ọti ti Anthony, o ti mu ọti yó.” Irọ́ ni eyi jẹ́. Kini ohun ti o jẹ? Mo wa ni ilu Jeffersonvilee, eyi jẹ otitọ. O jẹ ododo ti a yipada si irọ́. Ṣe ẹ ri itumọ ohun ti mo n sọ? Ṣe ẹ ri, irọ maa n yi otitọ pada. O jẹ ohun ti o sọ ibiti mo wa. Nisisiyi, ti o ba sọ wipe, “ni ile ijọsin, mo si n waasu,” eyi jẹ otitọ. Eyi si jẹ ododo o sọ otitọ. “Ni ile ọti, n mu ọti.” Irọ ni. A ti yi i pada, ṣe ẹ ri, otitọ ti a yi pada. Ṣe ẹ ri itumọ ohun ti mo n sọ? Gbogbo aiṣododo ni ododo ti a yi pada.

149 Iku, kini ohun ti o jẹ? Iye ti a yi pada. Aisan? Ìlera ti a yi pada. O yẹ ki o jẹ ọkunrin ti o dara ti o si lagbara. Eyi dara, ti o ba n ṣe aisan, kini ohun ti o jẹ́? A ti yi ilera rẹ pada. Ṣe ẹ ri, ohun ti o wà nipa rẹ niyi. Kini ohun ti o jẹ? O jẹ ọdọ obinrin ti o lẹwà ti o si lagbara, ọkunrin ti o lẹ́wà, nisisiyi ara rẹ ti n wunjọ o si ti n darugbo. Kini ohun ti o ṣẹlẹ? Iye ti a yipada, ṣe ẹ ri? O si ni lati pada wa, ibukun ni fun orukọ Oluwa! - Ọlọrun ti ṣe ileri pe Oun yoo mu u pada. O si daju gẹgẹ bi i pe.... gẹgẹ bi pe o wà, Ọlọrun yoo mu u pada wa lẹẹkan si. O ti̩ se ileri rẹ O si ti bura pe Oun yoo ṣe e. Ohun ti o fun wa ni....

150 Bayi, bawo ni, iru eniyan wo ni o yẹ ki a jẹ? Bayi ṣe akiyesi bi awọn nkan wọnyi ṣe ṣẹlẹ? Wayi o, gbogbo awọn ti O ti mọ̀ tẹ́lẹ̀, ni O ti pè; awọn ti O pè, ni O ti da ni àre. Nigba wo ni? Ṣaaju ipilẹṣẹ ayé, ṣaaju ki aye to bẹ̀rẹ̀. Nisisiyi, ti a ba le ka Iwe Mimọ ti a ba si le ṣe ayẹwo rẹ daada, a o lo ọpọlọpọ akoko lori rẹ, ṣugbọn a ko fẹ ṣe èyí. Ṣugbọn gbogbo awọn aiṣododo wọnyi nibiyi jẹ ododo ti a yi pada si aiṣododo. Ohun ti èṣù n ṣe niyi. Bayi, nigbati o ba de ọjọ—ori ti o ti le jiyin funrara rẹ (o mọ ọtun yatọ si òsì), ti ọ si mọ ohun ti ko dara ati eyiti o dara, o yẹ ki o yago kuro ninu iṣẹ buburu rẹ. Nitoripe, a bi ọ sinu ẹṣẹ, a mọ ọ́ ninu aiṣododo, o wa sinu aye o n pa irọ. A bi ọ nitootọ nipasẹ ibalopọ laarin baba ati iya, ati lẹhin naa a gbọdọ tùn ọ bi ki o le gba ibi tuntun lati le e wọ ọ̀run. Nitoripe irú`ibí ti o ni....

Ṣe ẹ ri ibi ti awọn ẹlẹri Jehofa ti kuna lọna jinjin si ibiyi, lati ronu pe ibi tuntun jẹ ajinde ti ara? Ṣe ẹ ri, ko le e jẹ bẹ́ ẹ̀. Ṣe ẹ ri? O ni lati jẹ ohunkan.....

151 O wa ni`ipele`akoko, ohun kan ti o si jẹ aìkú ni ohun kan ti kò ni bẹẹrẹ ti ko si ni òpin. Ohunkohun ti o jẹ ayeraye kò ni ibẹẹrẹ, bẹẹni ko si ni opin laelae. Ṣe ẹ ri i. Nitori naa ti o ba jẹ ipa ti Ọlọrun, ẹmi ti o wa ninu rẹ ko ni ibẹrẹ ko si ni opin laelae, o si jẹ ẹni aiku pẹlu ẹmi naa ti o wà ninu rẹ. Ṣe o ri?

Gẹgẹ bi ifẹ àgápò (ojulowo) lẹhin naa yoo wa si ifẹ filio (ifẹ ará), ati lẹhin naa si ifẹ ara, yoo kan maa lọ si ilẹ, si lọ si ilẹ si, yoo di eyiti a yi pada lọ si ilẹ si titi ti yoo fi di ẹ̀gbin ti a kojọ papọ. Kini idi, ọna kan ṣoṣo....

Jesu wa ni àkàbà kanna sọkalẹ lati mú ati lati mu pada si ipo ti o ga julọ lati ipo ti o lọ silẹ julọ - lati ikú si ìyè, lati aisan lọ sinu ilera, lati aiṣododo lọ sinu ododo. Ṣe ẹ ri? O wa lati ibi ti o ga julọ lọ si ibi ti o lọlẹ julọ, ki oun ohun ti o rẹlẹ julọ wa si ibi ti o ga julọ. O di emi ki emi nipasẹ oore-ọfẹ Rẹ ki emi le di Oun, ajogun papọ si itẹ ogo. Ṣe ẹ ri itumọ ohun ti mo n sọ? Awọn nkan wọnyi.

Bayi, wo o, ṣaaju ki aye to bẹrẹ ninu ẹyà-ti o-pọwọ-le-ẹya-ti-o-kere-julọ-ti a fi ṣẹda aye ni ọpọlọpọ ọdun sẹyin, nigbati Ọlọrun ti ri ohun ti yoo ṣẹlẹ, nibẹ lọhun O ri ọ, O ri mi, O ri gbogbo ohun ti n fò kọọkan, gbogbo ẹyẹ kọọkan, gbogbo ọpọlọ kọọkan, gbogbo kokoro to dabi yànmùyánmu kọọkan - Ohun gbogbo ti yoo wà ni ori-ilẹ ayé, O ri wọn nibẹ. Dajudaju o ri i.

152 Bayi, ko sọ wipe, "Emi yoo ràn Ọmọ Mi wa ki O si kú, ati bóyá ẹnikan yoo káànú Rẹ̀. Yoo si jẹ ikaanu ti o lagbara, boya ẹnikan yoo ni ìgbàlà."

O mọ ẹniti yoo ni igbala tẹ́lẹ̀. Bẹẹni, sà. O wipe, "Esau ni mo korira, Jakọbu ni mo si fẹran," Ṣaaju ki ọkọọkan wọn to ni ànfaní lati fi idi iru ẹniti wọn jẹ múlẹ̀: nitoripe o mọ iru ẹni ti wọn jẹ́. O mọ̀. O mọ ohun gbogbo. O mọ ohun ti iwọ yoo ṣe, ṣaaju ki a to bi ọ, nigbati ayé bẹ̀rẹ̀.

153 Bayi wo o. Gẹgẹ bi o ti mọ, mo jẹ ẹniti o maa n gbe ibọn. Mo fẹran ibọn. Ati awọn obinrin kan ni ilu Texas, mo gbagbọ pe ilu Texas ni, ra ibọn Swift kan fun mi, ibọn ti o ni onka ami-idanu-duro eji, eji ati òdo (.220) ti Swift. Mo ti n pòǹgbẹ lati ni ọkan, mo fẹ ṣe iwadi rẹ̀. Yiyan rẹ jẹ eyiti o ni agbara o si kéré. O ni ọta-ibọn meji-le-logun, o si ni ẹyọ ọta-ibọn meji-din-laadọta, o si le e dari eyi .... Bayi, ile-iṣẹ naa sọ wipe, "Maṣe ṣe e, o léwu púpọ̀," Ṣugbọn o le dari ọta-ìbọn naa to bi i ẹsẹ bàtà ẹgbẹrun marun-un ọta-ibọn ni iṣeju kan ki o si tun le e di i mu. Ẹgbẹrun marun ẹsẹ̀ bàta ni iṣeju kan eyi jẹ ibusọ maili ni iṣeju kan. Ni itumọ ọrọ miran, ẹyẹ aṣa ti o joko ni onka ibusọ ọgọrun meji ọpa, o le yinbọn si ẹyẹ aṣa naa ki o si ri ti ìyẹ́ rẹ fò ṣaaju ki ìbọn naa to dún. Ṣe ẹ ri?

Ṣugbọn ti o ba mu ibi pẹlẹbẹ ìtayín yẹn ki o si fi mu ẹtu-ibọn, ki o si da pupọ sinu rẹ, eyiti yoo to fun itayin naa lati gbà duro; o si le e ta ibọn si ori itanyin; ki o si ta ibọn si ẹlẹdẹ-ori-ilẹ ti o joko ni opin ilé ti o wa nibiyi - yoo joko yoo si maa wo ọ. Kini ohun ti o ṣẹlẹ? Ọta-ibọn naa ti parẹ́, o n sáré lọ pẹlu agbara. O si le mu beba kan si aarin ibiyi ati ibẹyẹn, o ko ni ri ohun ti o ti jẹra kankan ki o jabọ si ori bébà yi. Yoo kan yipada. Ko ḳi n ṣe si éerú, eeru ti ilẹ̀ ríru; ṣugbọn yoo lọ siwaju ju eleyi lọ. Yoo pada si èròja ohun-olóró ti a fi ṣe èrò-ìjà kọ́pà ati lẹẹdi eyiti o wa ninu rẹ tẹlẹ. Yoo pada si bi o ti ṣe ri ni ọgọrun bilioni ọdun sẹyin. Bayi, ibọn kekere niyi, meji-din-ni-ọgọta ẹyọ ọta-ibọn, mo si di i mu ni ọwọ mi; ati ni iṣeju ti o tẹle o yipada si ohun ti o jẹ́ ni ọgọrun milioni ọdun sẹyin. Ti aye ba si le duro fun ọgọrun milioni ọdun miran, yoo yipada si ọta-ibọn kan, a o si mu u pada wa, si bi o ti se wa ni ero-ija kọ́pà.

154 Bayi wo ohun ti Ọlọrun ṣe, lẹhin naa iwọ yoo nifẹ Rẹ; lẹhin naa iwọ yoo lọ si ìlé, ati ni owurọ, iwọ yoo pẹ́ ki o to sùn, iwọ yoo si fẹran Rẹ ju ti tẹlẹ lọ. Bayi, Ọlọrun jẹ agbaṣẹse kan. Ẹni melo ni o mọ eyi? O maa n kọ ilé. O dara, ẹ feti silẹ daada. Bayi, Ọlọrun ni ibẹrẹ, wọn wipe.... Bayi iwọ yoo mu oye awọn amoye nipa ọjọ ori dani pẹlu rẹ. Ọlọrun, ni ọgọrun bilioni ọdun sẹyin, nigbati o fẹ dá aye, o dara, o kan bẹrẹ. Nisisiyi O ni .... ipinnu yi ninu ọkàn Rẹ.

155 Bayi, iwọ yoo sọ wipe, "Ti o ba jẹ wipe O tobi to bẹ ẹ gẹ, Arakunrin Branham, bawo ni o ṣe gba èṣù laye lati da ẹṣẹ?" O dara, o mọ ṣaaju ki a to da èṣù pe yoo jẹ èṣù. Ogo! Mo ni imọlara ẹsin bayi. Oo, Akiika! O mọ ṣaaju ki a to da èṣù pe yoo jẹ èṣù. Iwọ yoo bẹrẹ bayi, "Kini ohun ti o ṣẹlẹ?" Iwọ yoo sọ wipe, "Kini idi ti o fi gba a laye pe ki o jẹ èṣù?" Ki a le fi idi rẹ mulẹ pe Oun ni Ọlọrun. Idi niyi ti O fi ṣe èyí. Kilode ṣe aiṣododo kankan wa? Kini idi....

156 Ewo ni àkọ́kọ́, Olugbala tabi ẹlẹṣẹ? Ewo ni akọkọ? Olugbala. Ewo ni akọkọ, oluwosan tabi alaisan? Kilode ti a fi fi aye gba a pe ki a jẹ ẹlẹṣẹ? Nitoripe ninu ẹ̀dá Rẹ o jẹ Olugbala. Ti ko ba si ẹlẹṣẹ rárá? A ko lee mọ Ọ si Olugbala rara. Hallelujah! O maa n jẹ ki ohun gbogbo ṣẹlẹ fun ogo Rẹ "Ṣe amọkòkò le sọ fun...." tabi, "Ṣe ìkòkò le sọ fún amọkoko, pe bayi ni o ṣe mọ mi?" Tani ẹniti o jẹ oludari? Tani ẹniti o ni amọ̀? Ọwọ tani o wà nibẹ? Paulu sọ wipe, "Iwọ òpè ọkunrin, ṣe ko ha sọ wipe o gbe Farao dide nitori idi èyi. Dajudaju. O mọ eyi ṣaaju ki ayé tó wà. O mọ ohun ti ẹnikọọkan yoo jẹ. O si gba ẹṣẹ laaye ki Oun le jẹ Olugbala. O gba aisan laaye ki Oun lee jẹ Olùwòsàn. O gba ikorira laaye ki Oun lee jẹ ifẹ! Dajudaju O ṣe bẹ ẹ. Oun ni Ọlọrun, awọn nkan wọnyi si jẹ iṣe Rẹ; O si gbọdọ ni ohun kan ti yoo lò lati le fi iṣe Rẹ hàn.

Bawo ni iwọ yoo ṣe mọ̀ pe aṣalẹ wa, bawo ni iwọ yoo ṣe mọ pe ohun kan.... . . Ti o ba jẹ wipe owurọ nikan ni o wà, bawo ni iwọ yoo ṣe mọ pe aṣalẹ wa? Aṣalẹ wa ki a ba le fi idi owurọ mulẹ. Dajudaju o wa. Amin. Ṣe ẹ ri ohun ti o ṣe?

157 Ṣugbọn nigbati O wà ni ibẹrẹ ṣaaju ipinlẹṣẹ aye, ṣaaju ki O to mu oorun ògbólògbó naa ti O si jẹ ki o yipo yika irawọ ogbologbo yi ti a n gbe ninu rẹ bayi, aye yi, ti O si tún Un ṣe nipasẹ oorun, ti O si gbe e kalẹ ni ẹgbẹ oorun.... wipe, eyi ni oorun. O mọ ọ́ ni ẹ̀gbẹ́ yi O si fi kọ́ si oke fun ọgọrun bilioni ọdun. Kini ohun ti O n

ṣe? Awọn afẹfẹ gasii. O jẹ ki wọn yipo ni apakan, O da ohun miran. Kini ohun ti O n da nibẹ? O n da awọn ohun ero-ja káṣiọmù. Kini ohun ti O n ṣe? O n dá iwọ ati emi. Kini ohun ti O n ṣe? Gẹgẹ bi i agbaṣẹse naa ti o n to awọn igi-ikọle oniwọn meji-si-mẹrin, ati meji-si-mẹjọ rẹ, awọn paanu-ikọle rẹ, awọn ohun-ikọle Rẹ, o mọ onka iye ile ti Oun yoo kọ́.

A da wa lati ara èròjà mẹrin-din-logun ti o jade wa lati inu-ayé, O si n da gbogbo wa, O si n fi ipinlẹ wa sọlẹ ṣaaju ki aye to di.....`Irísí rẹ le ri bi i ẹyin nigba naa, emi kò mọ̀ bi irisi rẹ ti ṣe ri. Kini ohun ti o n dá wura ati kọ́pà, ati idẹ ati omi, ati oriṣiriṣi nkan bi i eleyi? Nitori o jẹ agbaṣẹse. O jẹ akọle kan, o n fi idi ohun gbogbo sọlẹ̀, o gé ohun gbogbo O si fi wọn si ipo wọn. Nigbati o jẹ ki a dá ohun gbogbo, o kan jẹ ilẹ-riru nla ti o ni agbara. O jẹ ki awọn ilẹ-ki o ru jade sita fun bi i ọgọrun miliọni ọdún, lati le mu èròjà Kalsiọmu jade wa, kini ohun naa? O jẹ èròjà kan lara rẹ.

158 Ati lẹhinaa, ṣaaju ki iye kankan to wa lori ìlẹ̀ ayé, àgọ́-ara wa ti wa nibi. Hallelujah! Ṣaaju ki íkán omi kan to kan si ori-ilẹ ayé, a ti wa nibi. Nigbati Adamu n rin soke, rin silẹ ninu ọgba Edeni, mo wa nibiyi. Amin. Bẹẹni, Sa! Oo, Ogo! Nigbati awọn kerubu, awọn irawọ owurọ kọrin papọ ti awọn ọmọ Ọlọrun kigbe fun ayọ̀, mo wa nibẹ mo kan n duro ki ìmì-ìyè ki o wá. Mo wa nibẹ. O da mi nibiyi, agọ-ara mi wa nibẹ. Bẹẹni, sà. Ti ko ba ri bẹẹ, nibo ni O ti wá? Huh? Bawo ni o ṣe de ibiyi? Wọn jẹ ti Ọlọrun wọn si duro nibẹ. Ọlọrun ni O da a. A da wa lati ara eroja mẹrin-din-logun: eroja epo pẹtrol, eroja potasi, ati ina-oju-ọrun, ati awọn ohun miran. Ṣe ẹ ri, a ti wa nibiyi tẹlẹ.

159 Lẹhin naa kini ohun ti o ṣẹlẹ? Nigba naa ni Ọlọrun sọ fun Ẹmi Mimọ (a o lo àmi lati fi ṣalaye rẹ). “Iwọ lọ ki o si fi ifẹ hàn si aye - nitoripe Emi jẹ ifẹ Iwọ si jẹ ipa lara Mi, nitorina, iwọ lọ ki o si fi ifẹ hàn fun aye.” Ati Emi Mimọ nla naa, bi a ti ṣe ro, o jade wa sibẹ. A n fi àmì ṣalaye rẹ bayi, ko ki n ṣe ni ọ̀nà yi. Nitoripe, Ẹmi Mimọ ati Ọlọrun n ṣiṣẹ kannaa, wọn jẹ ohun kannaa ipa kannaa - ẹnikan, ẹ foriji mi. Ẹ jẹ ki a sọ wipe O na iyẹ Rẹ si ori-ilẹ aye, o bẹrẹ si ni fi ohùn-ifẹ Rẹ pe. Kini ohùn-ifẹ jẹ́? Gẹgẹ bi agbebọ adiyẹ ṣe maa n ṣe si awọn ọmọ rẹ̀, o n fi ifẹ pe wọn, o n fi ifẹ hàn si wọn, “kuu, kuu, kuu,” Oo.

160 “O Iyè, jade wá!” O kigbe. O wò yiká. Mo fẹ ẹwa ninu aye yi. Jade wa, imọlẹ!“ Ẹmi Mimọ n fo kaakiri. Nigbati o ṣe eyi. Mo wo mo si ri ohun kan n bọ̀ wá, oke naa bẹrẹ si ni là, nibẹ ni awọn eroja kalṣiọmu ti n tù jade sita da silẹ, o si dara papọ mọ eroja potasi. Kini ohun ti o fẹ mu jade? ”Ìyè, jade wa!“ Ododo Ajinde kekere kan, gbe ori rẹ jade lati abẹ apata kan. ”Wá nibiyi, Baba, wo èyí.“

“Eleyi dara, tẹsiwaju lati maa fi ohùn-ìfẹ́ pè.” O fi ohun-ifẹ pe awọn ododo, O mu gbogbo awọn ohun eweko jade wá, O mu gbogbo awọn igbe-aye ẹranko jade wá, awọn ẹyẹ fò jade lati inu eruku. Lẹhin igba diẹ, ọ̀kunrin ati obinrin jade wa - ọkunrin kan jade wa, ọkunrin naa si jẹ akọ ati abo. Ko ki n ṣe eniyan kan ti o ni ẹ̀yà ara ibimọ ti ọkunrin ati obinrin lapapọ bayi. Akọ ati abo wa ninu rẹ̀.

161 `Ẹmí obinrin wà.

Nigbati o ba mu ọkunrin kan ti ko ni igboya bi i ọkunrin, o le jẹ ẹni ti o dara, ẹniti ara rẹ pé daradara, ṣugbọn ohun kan kuna. Ati nigbati o ba mú obinrin kan ti o fẹ gé irun rẹ̀ ti o si fẹ wọ aṣọ-iwọlẹ̀kẹ iṣe, ti o si fẹ jade sita ti o si fẹ, “ibukun fun Ọlọrun, mo sọ fun ọ....” - Ohun kan ti kuna. Obinrin maa n ni ẹ̀mí obinrin, ati ọkunrin maa n ni ẹ̀mí ọkunrin. A mọ eleyi. Nisisiyi o mọ eleyi. Njẹ obinrin ti o n gbiyanju lati jẹ.... ti o n hùwà bii ọkunrin njẹ o dara?

162 Kini idi, mo sọ ni ọjọ kan, mo jẹ ẹniti o n ṣiṣẹ nibiti wọn ti n ṣere lori pápá nibiyi, mo si joko lori ọkọ akérò mo si lọ si ibẹ mo si n gbá obinrin naa ni ẹsẹ̀, pẹlu ọwọ mi, mo n ba sọrọ - emi ko si mọ pe obinrin ni. O wọ fila awọn ti o ṣiṣẹ ajórin o si fi awò-oju nla si ojú bi eleyi, mo si joko sẹyin bi eleyi, o si n sọrọ nipa ohunkan tabi omiran nipa ohunkan ti o ṣẹlẹ. O wipe, “Ṣe ẹ mọ, o si wipe, ”ni alẹ ana [irisi rẹ ko dara rara bi o ti ṣe buru to, o n mu siga kan],“ O wipe, ”ni alẹ àná, mo sọ fun ọ, eniyan naa yọ̀ ṣubú kuro lati ori ohun naa; o si wipe, 'Ay', wa yọ ṣeré lori ibiyi,“ O wipe, ”Emi kò ti rẹrin to bi eleyi ni aye mi.“

Emi naa si n rẹrin, ṣe ẹ mọ̀, bi eleyi. Mo wipe, “Ọmọkunrin, eyi jẹ ọkan, ṣe kò ri bẹ ẹ bi?” Ti o joko nibẹ ti o si n sọrọ bi eleyi. Ti ko ba si mu ohun yi kúrò ki o si gbọn ori rẹ. O si ni ohun-ìnulẹ̀ kan nibẹ ti o fi hàn pe obinrin ni. Emi ko ti ri ara mi gẹgẹ bi alaiye to bi eleyi ri ni aye mi. Mo wipe, “Ṣe obinrin ni ọ bi?

O wipe, “Kilode, dájúdájú!”

Mo wipe, “forijimi.”

Emi ko ti ri iru eleyi ri. Bayi, eyi jẹ otitọ.

163 Mo ti ri ami kan ni ọjọ kan ti o mu ìnú mi dùn. O ni àmì nla kan, o wipe “Omidan-binrin ẹ ṣetan lati wọ aṣọ.” Mo rò, “Ogo ni fun Ọlọrun fun èyí.” Ṣe ẹ ri? Ṣugbọn, mo wa ri wipe, o jẹ iru aṣọ kan ti wọn ti rán sílẹ̀, ṣe ẹ mọ̀. Mo rò pe wọn yoo wọ aṣọ. Emi pẹlu ṣe bẹ ẹ. Wipe, “Awọn omidan-binrin ti ṣetan lati wọ aṣọ.” Mo

wipe, "Ẹ yin Ọlọrun logo nitori wọn. Eyi dara. Mo dupẹ lọwọ Oluwa fún eleyi. Ṣugbọn, ṣe ẹ ri, o kan jẹ iru awọn aṣọ kan ti wọn ti rán silẹ, ohunkan. O jẹ ohun kan ti o pani-lẹrin, ṣe ko ha ri bẹẹ̀, ni orilẹ-ede yi? O dara.

164 Lẹhin naa nigbati Adamu jade wa, lẹhin naa Ádámù wà ni oun nikan, nitori naa o mu ìhà kan lati ẹgbẹ rẹ O si fi dá Efa - ohun kan ti a mu jade lati ara rẹ. O ti mu ẹmi obinrin ti o wa ninu Adamu kuro O si fi sinu obinrin naa, ẹmi ifẹ; ẹmi obinrin, oninure, oniwa-pẹlẹ. O si fi ẹmi ọkunrin silẹ sinu Adamu. Bayi, ti ohunkohun ba yatọ si eleyi, adamọdi kan ti wa ni ibikan niyẹn. Bayi, lẹhin naa awọn mejeji yoo di ara kan.

165 Ati ẹ jẹ ki a mu eré itage kekere kan, lẹhin naa a o parí, oun niyi, nibiyi Adamu ni o mu Efa ni ọwọ wọn si jijọ rin jade. Mo kan nifẹ itan ifẹ́ yi. Wọn si rin jade, ṣe o mọ, Efa si wipe, "Oo, olufẹ, ṣe o tumọ si pe iwọ ni....

"Bẹẹni, emi ni mo sọ ọ ni orukọ."

"O dara, kini orukọ ti o pe eleyi?"

"A n pe ni ẹṣin."

"Uu - huu. Kini ohun yi?

"Màálù niyẹn."

"Ṣe iwọ ni o sọ ọ ni orukọ"?"

"Bẹẹni, Un -huu."

"Kini ohun ti o n pe ìyẹn, iyẹn.... awọn meji ti o joko nibẹ ti wọn gbé ori wọn papọ̀?"

"Ẹyẹ ìfẹ́ niyẹn."

Oo, mo ri o ye mi." Wọn si jijọ n lọ bi eleyi. Kini ohun ti o wa nibiyi?"

"Mo pe eleyi ni ohun kan," ati eleyi ni ibiyi."

Ati, "Oo, mo ri i. Un-huu, eleyi lẹ́wà." Kiniun si bú jade, "kini orukọ ti o pe iyẹn?"

"Kiniun niyẹn."

"Kini eleyi?"

"Àmọtẹ́kùn ni."

Ati ohun gbogbo bi eleyi.... "Oo, o ye mi." Gẹgẹ bi ọmọ olóǹgbo, ṣe ẹ mọ, wọn n rin irin gbẹ̀fẹ́ kaakiri.

166 Nitorina lẹhin igba diẹ, o wo yika, o wipe, :Olufẹ, wo ibẹyẹn, oorun ti fẹ wọ̀. Akoko ti to lati lọ si ile-ijọsin." Ṣe ẹ mọ, ohun kan maa n wa nigbati oorun ba wọ̀. Iwọ yoo nifẹ lati jọsin. Ti iwọ ko ba lọ si ile-ijọsin ni aṣalẹ ọjọ kan, o maa n nifẹ lati lọ sinu iyara ki o si ka Bibeli. Awọn melo ni o maa nifẹ lati ṣe eleyi, wa ya ara rẹ sotọ ni iwọ nikan? Ṣe ẹ ri? O maa n wa ninu eniyan lati ṣe eyi. O yẹ ki o ṣe eyi. "Akoko tó lati lọ si ile-ijọsin."

Nisisiyi, wọn ko sọ wipe, "Bayi, duro ni iṣẹju kan. Bayi, nisisiyi ọgbẹẹni Jones jẹ́ ti Ijọ Assembili, awa si jẹ ti...." Rara, ko si irú ohun bayi ni ìgbà naa, nitorina wọn kan n tẹsiwaju lọ si oke.... Wọn ko ni ile-ijọsin, ijoko ti o dara lati joko lé bi eleyi. Wọn kan n goke lọ labẹ ile-ijọsin nla ti o tobi eyiti o wa ni abẹ igi, wọn si kunlẹ.

167 Ọwọn iná olobiripo naa si duro ni apa kan ni oke awọn koriko, ṣe e ri. Mo le gbọ ohun kan ti o sọrọ lati oke ti o si sọ wipe, "Ṣe awọn ọmọ mi ti gbadun ara wọn ni orilẹ-aye ni awọn ọjọ ti Oluwa Ọlọrun wọn ti fi fun wọn?"

"Bẹẹni, Oluwa, a gbadun ara wa ni óní. Ṣe bẹẹni olufẹ?"

"Bẹẹni, bẹẹni, olufẹ, awa ti gbadun ara wa. Oluwa, a mọ riri Rẹ. Bayi mo fẹ dubulẹ ki n si sùn," ṣe ẹ ri? O si na apá nla rẹ sita, obinrin naa si sùn si ibi apa rẹ̀, O si jẹ ki amọtẹkun sùn ati kiniun si sùn pẹlu, ati ohun gbogbo si dubulẹ lati sun - gbogbo rẹ si wa ni idakẹjẹ.

Nitorina Ọlọrun sọkalẹ wa O si mu sọkalẹ, Oo, ẹgbẹ awọn angẹli, Gaburẹli, Ẹda Rẹ ọ̀run. Nitorina wọn sọkalẹ wa wọn si rọra yọkẹlẹ sinu iyara- ibusun, ṣe ẹ ri, wọn wo yika. Gaburiẹli sọ wipe, "Wa nibiyi, Baba. Wa nibiyi, wo ibiyi. Ibiyi ni o wa. Nibiyi, ibiyi ni awọn ọmọ rẹ wa ti wọn dubulẹ si."

168 Awọn melo nibiyi ni wọn ti lọ si ẹgbẹ́ ibùsùn (ẹyin iya, iwọ ati baba lapapọ), ti ẹ o si wo awọn ọmọ-kunrin yin kekere, ọmọbinrin yin kekere, ẹ o si ran ara yin leti. "Ṣe ko ha dabi pe [ni ọ̀nà yi ati ni ọna yẹn]?" Ṣe ẹ tị se eleyi ri? Kini idi, ni ọpọlọpọ ìgbà ni mo maa n lọ ti n o si sọ fun Meda, sọrọ nipa Josefu - oun yoo si sọ wipe,

“Bill, o ni iwaju ori gẹgẹ bi tirẹ.”

“Bẹẹni, ṣugbọn, Meda, O ni oju ti o tobi gẹgẹ bi iwọ naa.” Kini idi? O jẹ ara wa.... O jẹ èrè igbeyawo wa.

Bayi, Baba si sọ wipe, O le sọrọ yi nipa èyí, sọ wipe, “Ṣe ẹ mọ........” Gabrẹli si sọ wi pe, “Ṣe o mọ̀, O jọ Ọ.” Bayi ni Ọlọrun ṣe rí. Wo ara rẹ, bi Ọlọrun ṣe ri niyi. O jọ Ọ. Ọmọ Rẹ̀ ni o jẹ́. Ẹni melo ni o mọ èyí?

169 Bayi ṣe akiyesi. Irú iyè ti o kere julọ wo ni a ni? Ọpọlọ. Iru iyè ti o ga julọ wo ni a ni? Eniyan. Dajudaju kini eyiti o ga julọ? O kan n wa lati eyiti o kere julọ lọ si òkè: Lati ọpọlọ lọ si eyi o si lọ si tọun, o si lọ si ẹyẹ, o si lọ si.... Oo, titi lọ bi eleyi, titi o fi de irú iyè ti o ga jùlọ, titi o fi de eyiti o ga julọ patapata ti o le ga tó, lẹhin naa a wa da a ni aworan Ọlọrun.

Ohun niyi. A ko si da obinrin naa ni aworan Ọlọrun, ṣugbọn ni aworan ọkunrin. Ṣe ẹ ri? Bayi, nisisiyi, awọn niyi wọn wa nibẹ. Ọlọrun si wo wọn, o wipe, “Bẹẹni, wọn dara lati wò.”

170 Kini ohun yi, arakunrin? Wọn ko nilo lati kú. Wọn jẹ eroja Kaṣiomu akọkọ, eroja potaṣi akọkọ ati ohun gbogbo, wọn bẹrẹ bi eleyi. Ṣe eyi ko dara bi? Ṣugbọn ẹ̀sẹ̀ wa o si ba gbogbo ohun didara yi jẹ. Bayi, ti Ọlọrun.... kini idi ti Ọlọrun fi fi àyè gba ki o ṣe eyi? Kini idi ti O fi fi aye gbà ki o ri bi eleyi, gẹgẹ bi a ti ṣe n sọ ni aipẹ yi? O fi àyè gba a ki o ba le fi idi rẹ mulẹ pe Oun jẹ Olugbala. O ṣe eyi, O jẹ ki aisan ki o wa ki O le fi idi rẹ mulẹ pe Oun jẹ Oluwosan. O jẹ ki ikú ki o ṣẹlẹ ki O le fi idi rẹ mulẹ pe Oun ni iye. Ṣe ẹ ri? O fi aye gba pe ki awọn ohun buburu yi ṣẹlẹ ki O le fi idi rẹ mulẹ pe Oun jẹ ẹniti o dara, Ohun ti o jẹ.

171 Iwọ yoo sọrọ nipa kikọ orin ìtàn irapada! Kini idi, arakunrin, nigbati Jesu ba dé, ijọ yi i yoo duro ni ọjọ kan ni ori ilẹ aye yi yoo si kọ awọn orin ìtàn irapada - nigbati Angẹli yoo tẹ ori wọn ba, ti wọn ko mọ nipa ohun ti a n sọ. Kini ìdí, wọn ko sọnu ri. Wọn ko mọ ohun ti a là kọja. A mọ ohun ti o tumọ si nigbati eniyan ba sọnù ti a si ri i. Oo, ẹ jẹ ki a kigbe iyìn Rẹ! Ko ki n ṣe Olugbala fun wọn. Wọn ko nilo igbala. Ko ki n ṣe Oluwosan fun wọn. Rara. Ogo! Ko ki n ṣe iyè fun wọn, dajudaju bẹẹkọ́; wọn kò kú sinu ẹṣẹ ati irekọja. Awa ni a jẹ eyi, ṣugbọn a ti sọ wa di alaaye. Ibiyi ni a wa. Kini àwa yoo sọ ti adé ko ba si ni ori wa? “O jẹ Ẹni-ọ̀wọ̀ lagbaja ati lagbaja?” Oo, rara, rara, rara, rara. Ogo ni fún Un. Ohun nìyí. Ibiyi ni a wà. “Lẹhin naa a o sọ itan bi a ti ṣe jagun-ṣẹ́gun, gbogbo rẹ yoo ye wa dara si nigboṣe.”

172 Lẹhin naa, nibẹ ninu rẹ, lẹhin naa kini ohun ti o ṣẹlẹ? Ṣe Ọlọrun kan sọ wipe, “O dara, Emi le pa gbogbo awọn eroja potaṣi ati kalṣiọmu mi run. Gbogbo rẹ ni o ti parun?” Rara, rara, o mọ pe yoo ri bẹ.“ Bayi, nisisiyi ti Ẹmi Mimọ ba jẹ ki n jẹ ẹniti mo jẹ, ti mo si n jẹ ounjẹ ti mo si n fi sinu ara mi ti mo si dagba de ibiti emi wa nisisiyi, Emi.... sibẹ a da mi ni aworan kan. Gbogbo aworan ti Ọlọrun ni, ṣaaju ipilẹṣẹ ayé, gbogbo rẹ ni o wa fi ara han. Ṣe ẹ ri? O jade wa lati inu obinrin, gẹgẹ bi O tị se sọ wipe yoo ri; ni igba ti o tẹle o jade wa lati ọdọ Ọlọrun. o wa nigba naa lati ipasẹ eniyan. Ṣe ẹ ri? O wá nigba naa lati ipasẹ ifẹ ìbálòpọ̀, o wa nigba yi lati ipasẹ Ọrọ ti Ọlọrun sọ. Ṣe ẹ ri?

Ati nibẹ, bayi, ko si ohunkohun ti o le ṣe ohun buburu si mi. Rara, sa. Ko si ohunkohun ti o le ṣe ohun buburu kankan si wa. Paulu sọ wipe, “Ko si ohun ìgbà isisiyi, ohun ìgbà ti n bọ̀, aisan, ikú, ko si ohun ti yoo le yà wa kuro ninu ifẹ Ọlọrun ti o wa ninu Kristi.” Ko si ohunkohun ti yoo yà wá.

173 Gẹgẹ bi itan kekere ti mo sọ. O ku ẹyọ irun marun-un ti emi yoo fi di apari patapata. Mo si n ya irun diẹ tó ṣẹ́kù nibiyi ni ọjọ kan, iyawo mi sọ wipe “Billy, o ma ti fẹrẹ di apari.”

O wipe, “Nibo ni wọn wa?”

Mo wipe, “Nibo ni wọn wa tẹlẹ ki n to ri wọn? Ṣe ẹ ri, ibikibi ti wọn wà ki n to gbà wọn.” Nisisiyi, igba kan wa, ọgọrun ọdun ṣeyin awọn irun wọnyi ko si nibẹ rara, ṣugbọn wọn wa ninu erùpẹ̀. Ṣe eyi jẹ otitọ? Lẹhin naa fun bi i aadọta ọdun sẹyin, wọn bẹrẹ si ni wá si ori mi. Nibo ni wọn ti wá? Lati inu erùpẹ̀. Ati nisisiyi wọn n pada si ibiti wọn wa tẹ́lẹ̀. Ṣe eyi jẹ otitọ? Wọn ko si mọ, wọn si tun wà, ati nisisiyi wọn ko si si mọ. Kini ohun naa? Tani o da wọn bi wọn ti ṣe wa? Ọlọrun! “Oun niyi.” O fi aworan kan hàn, o wipe, “Bi mo ti ṣe fẹ́ ko ri niyi.”

174 “Oo ikú, oró rẹ da” Isa-òkú, iṣẹgun rẹ da?“ O le sin mi ni ọkan ninu awọn ọjọ́ wọnyi lati ibiyi, emi ko mọ, ṣugbọn, arakunrin, emi ko ni kú, emi yoo sọ eleyi fun yin. Rara, Sa. ”Oo, a o jinde, hallelujah, a o jinde. Ni owurọ ọjọ ajinde naa, nigbati a ba já ẹ̀wọ̀n iku, a o jinde, hallelujah, a o jinde!“ Ko si ohunkohun ti yoo di mi lọwọ lati ma jinde. Ko si bi èṣù ti ṣe le pọ tó ni ọrun-apadi, ti yoo di mi lọwọ lati ma jinde. Ko si ohunkohun bi o ti ṣe le pọ̀ tó ni ibikibi ti yoo di mi lọwọ lai ma jinde, mo ni ileri Ọlọrun, mo ni Ẹmi Mimọ. Mo ni Zoe, iye ayeraye ti Ọlọrun, ti o ni sinmi nibiyi. Ara kíkú ogbologbo yi jade wa lati ibẹ, Ọlọrun mu mi jade lati ilẹ.

175 Ti O ba mu mi jade lati inu ilẹ, nigbati mo dagba ti mo si.... Gbogbo igba ti mo ba gbọ agogo ile-ijọsin, ohunkan yoo ba mi sọ̀rọ̀, ọmọkunrin kekere ti ko lagbara kan. Angẹli kan sọrọ lati inu igbó, o wipe, “Maṣe mu ọti tabi mu siga, Mo ni iṣẹ kan fun ọ lati ṣe. Maṣe ba ara rẹ jẹ, kíkó obinrin, ati awọn nkan. Iwọ.... Mo ni iṣẹ

kan fun ọ lati ṣe nigbati o ba dàgbà.”

“Tani Ọ? Tani Ọ?”

“Ẹyin yoo mọ nipa eyi si ti akoko ba tó.” Lẹhin igbà diẹ, O wa si ibiyi, O duro ni apakan ni apa oke ni ibi iribọmi, O fi ara Rẹ han, O jẹwọ ara Rẹ. O dahun. Mo ri I ti O duro ni apakan ni apa oke nibi gbogbo, nigbakugba.

176 Bawo ni iwọ yoo ṣe lọ.... Ti O bą se mi bi mo ti ṣe ri bayi làí bere ìyàn kankan lọwọ mi rara? Emi ko pada lọ ki n si sọ wipe, “Nisisiyi, Charlie Branham, iwọ ni ki o fẹ Ella Harvey, ki o si bi mi jade si ori-ilẹ-ayé.” Rara, sa, emi ko ni iyan kankan nipa eyi rara. Ọlọrun ni o ṣe eyi. Ti O ba si da mi bi mo ti ṣe ri bayi, laisi ìyàn t̀emi, bawo ni yoo wa ti ṣe ri nigbati Ẹmi Mimọ naa bą se alabojuto mi ti mo si sọ wipe, “Bẹẹni. Oluwa, iwọ ni Ẹlẹda mi! Mo fẹran Rẹ, mo si tẹwọ gbà Ọ gẹgẹ bi Olugbala mi.” Bawo ni iwọ yoo ṣe dè mi mọ aye yi? Iwọ ko le ṣe eyi rara, arakunrin, o ko lee ṣé e.

177 Ọlọrun ko da ikọọkan ninu eroja kalṣiọmu tabi potaṣi tabi ohunkohun miran ti ko ni wulo “Gbogbo awọn ti Baba ti fi fun Mi [ṣaaju ipilẹṣẹ aye], ni yoo wa si Ọdọ Mi!” Oo! O dabi ẹnipe ki n kigbe, nitootọ mo ni imọlara rẹ. “Gbogbo awọn ti Baba ti fi fun mi ni yoo wá si ọdọ Mi, ki yoo si ọkan ninu wọn ti yoo ṣègbé, ṣugbọn Emi yoo jí wọn dide ni igba ajinde.” Mo gbọ ti O pè, mo si wa si ọdọ Rẹ. Bawo ni wọn yoo ṣe fi mi pamọ sinu erupẹ ayé? Ko si awọn agbé-òkú ni aye yi bi wọn ti ṣe le e pọ̀ tó ti o le da erupẹ si mi loju pẹlu ṣófẹ́li, lati le fi mi pamọ sinu erupẹ aye. Emi yoo ji dide ni ọjọ kan emi yoo si duro gẹgẹ bi i aworan Rẹ, ti a fọ̀ pẹlu ẹ̀jẹ̀ Rẹ, ti a bi pẹlu Ẹmi Rẹ! Hallelujah! Mu gbogbo ijọ ẹlẹkọ Adamọ ti o ba fẹ, Emi yoo mu Jesu. Amin!

178 Ọkunrin ádójú-tòfò kan wa si ọdọ mi, Ọgbẹẹni Wilbur Snyder, ọrẹ mi ti o dara. O wipe, “Billy, emi fẹ ta ilana adojutofo kan fun ọ.”

Mo wipe, “Emi ti ni ọkan.” (Iyawo mi wo yika o fẹ́rẹ̀ sọ wipe, “Kilode ti o fi n parọ, ọmọkunrin?”)

Ọgbẹẹni naa sọ wipe, “Ṣe o ni adòjú-tòfò?”

Mo sọ wipe, “Bẹẹni Sa.”

O wipe, “Inu Ile-iṣe wo ni o wa? Kini ohun naa?”

Mo wipe, o damiloju, Jesu Jẹ temi! Oo, itọwo adun`ọrun leyi jẹ, mo di ajogun igbala kikun, Ẹjẹ Rẹ wẹ mi, a tun mi bi.“

O wipe, “Eyi dara, Billy, ṣugbọn ko ni le ṣe isinku fun ọ.”

“Ṣugbọn,” mo wipe “Yoo ji mi dide.” Hallelujah! Emi ko damu ọkan mi bi emi yoo ṣe de ibẹ, eyiti o jẹ mi logun ni lati jade kuro nibẹ.

179 Nitorina, mo ni adojutofo ti o sọ fun mi pe, “Emi yoo mu gbogbo Awọn ti Baba ti fi fun Mi, Jẹ Temi.” Emi ko bikita ohun ti Baba mi ti ṣe, ohun ti Mama mi ti ṣe, ohunkohun ti gbogbo rẹ le e jẹ,“ Gbogbo Awọn ti Baba ti fifun mi ni yoo wa si ọdọ Mi, ko si si ẹniti o le wa ayafi ti Baba Mi ba kọkọ fa a.” Hallelujah! Kini lati igba wo ni o ti mọ wọn? Mo ti mọ wọn ṣaaju ipinlẹṣẹ aye, nigbati mo pa ọdọ Aguntan naa, Mo pa a pẹlu Rẹ.“ Amin. ”Mo yan ijọ naa tẹlẹ.“

Awọn wo ni a yàn tẹlẹ? Ijọ naa. Bawo ni iwọ yoo ṣe di ti ara ijọ naa? “Nipa Ẹmi kan ni a baptisi wa sinu ara kan.” O mọ ṣaaju ipinlẹṣẹ aye pe a o wa nibẹ. Ati awọn ti o ti mọ tẹlẹ, ni o ti pe̍. Awọn ti o ti pe̍, ni O ti da lare. Awọn ti o ti da láre, ni o tị se logo.

180 Ninu iwe Ọlọrun O wipe Oun yoo pade mi ni ibẹ̀. Ko si gbogbo èṣù ti o jade lati ọrun ti wọn lagbara to lati le fi pamọ si ibo miran, ṣugbọn yoo pa Á mọ́ titi yoo fi jade wa sibẹ, nitori Ọlọrun ti sọ ọ tẹlẹ, eyi si ti yanju gbogbo rẹ. Ti o ba jẹ wipe ọgọrun bilioni ọdun ṣaaju ki a to da aye, awọn irawọ owurọ kọrin papọ ati awọn ọmọ Ọlọrun si kigbe fun ayọ - ṣaaju ki ipilẹṣẹ aye ki o to wà, ṣe ẹ ri, ṣaaju ki ohun kan to wa.... ati awọn angẹli ati ti ohun gbogbo kun fun ayọ, ti wọn n yọ nipa rẹ, ṣaaju ki ipinlẹ ayé to wà - bawo ni èṣù yoo ṣe fi mi sinu erupẹ ayé? Ko le ṣe e. Otitọ ni.

181 Ẹ jẹ ki a ri, bayi, àkoko ijọba Awarawa ni mo ni nibiyi. O ku ogún iṣẹju ki agogo mọkanla lù, eyiti o jẹ wipe o ku ogún iṣẹju péré ki agogo mẹwa lù. Ṣe eyi jẹ otitọ, Arakunrin Wood? Eyi jẹ otitọ, o ku ogún iṣeju ki agogo mẹwa lù. Ṣe inu gbogbo wa dùn?

Oo, Mo fẹ lati de ile mi,

Mo fẹ lati de ìlè,

Ile mi ọrun dara o lẹwa,

Mo fẹ lati de bẹ,

Oo, mo fe lati de ibẹ,

Mo fẹ lati de ibẹ,

Ile mi ọrun dara o, lẹwa,

Mo si fẹ lati de ibẹ,

182 Ṣe o fẹran awọn orin atijọ bi eleyi? Ọkan wa ti o jẹ atijọ́ ti a maa n kọ nipa rẹ, ohun kan nipa "Oore-ọfẹ ati anu ni o wa mi ri, nibẹ ni Irawọ Owurọ ti tàn." Kini ohun naa, Arabinrin Gertie? Ẹ jẹ ki a ri i. Kini o jẹ, Arakunrin Neville? Ṣe ẹ ri, ohunkan "oore-ọfẹ ati aanu wa mi ri, nibẹ ni Irawọ Owurọ tan imọlẹ yi mi ka." Uu-huu bẹẹni. "Ni ibi agbelebu." Tẹ duru fun wa si orin naa, arabinrin. Ohun ni "Nibi Agbelebu." Wa si ibiyi. Oo, mo nifẹ eyi. Ẹni melo ni o nifẹ awọn orin ti o ni imisi? O le fo soke ki o fo silẹ ki o si ni awọn orin taka-sufe ti o ba fẹ́. Fun mi ni èyí, ibiyi ni oore-ọfẹ ati anu wá mi rí. Ohun niyi. O dara, ẹ jẹ ki a kọọ bayi.

Nibi Agbelebu Rẹ,

Jesu jọ pa mi mọ

Nibi Isun iyebiye

Ti o n san fun iwosan wa

Nibi Agbelebu

Jesu n o maa ṣogo

Titi ọkan mi yoo sinmi

Ni ikọja odo.

[Arakunrin Branham bẹrẹ si ni kọrin naa sinu "Nibi Agbelebu"] Oo, bawo ni o ṣe ni ẹwa tó! Ronu nipa rẹ̀! Ti ko ba si Olugbala nkọ? Ti ko ba pe ọ nkọ? Ti ko ba ti mọ ọ tẹlẹ nkọ, o wa nita nibiyi pẹlu awọn iyoku ti o wa ninu aye ni aṣalẹ yi? Ṣe o nifẹ Rẹ? Oo, akiika! Maṣe gbagbe awọn isin ni owurọ, bayi, ni agogo mẹsan àbọ́.

Nibi Agbelebu

Jesu n o maa ṣogo

Titi ọkan mi yoo sinmi

Ni ikọja odo

183 Bayi, tẹ duru fun wa si orin yi "Aye wa nibi Isun naa." Orin atijọ ti o dara yi, "Aỳe wa ni ibi Isun Naa." Awọn melo ni o mọ ọ? "Aỳe wa, àyè wa, bẹẹni, aỳe wa, àyè wa ni ibi Isun Naa." Ati ti o ba ṣe eleyi nisisiyi, ni idakẹjẹ, kan nawọ́ ni ẹ̀gbẹ́ ọdọ rẹ, bọ ọwọ pẹlu arakunrin naa. Ṣe o mọ̀, àyè wa bayi fun gbogbo awọn ara ijọ Mẹtọdisi, aỳe wa fun gbogbo awọn ara ijọ Baptisi, àyè wà fun awọn ara ijọ Pentikọsi. Àyè wa fun gbogbo wa nisisiyi, ni ibi orisun naa. Awọn melo ni o mọ orin atijọ naa? Oo, dajudaju ẹ mọ. Diẹ lara ẹyin ara atijọ nisisiyi, eleyi jẹ orin atijọ ti ilu Kentucky bayi.

Àyè wa, aỳe wa (ẹ jẹ ki a bọwọ), bẹẹni, àyè wà,

Aye wa fun ọ nibi orisun naa,

Àyè wà, àyè wa, bẹẹni,

àyè wa,

Àyè wa fun ọ ni ibi orisun naa.

Oo, àyè wa, aye wa,

Ọ̀pọ̀ àyè ni o wa

Aye wa fun ọ ni ibi orisun naa.

Oo, aye wa, aye wa, bẹẹni, aye wa.

Aye wa n fun ọ ni ibi orisun naa.

184 Bayi, mo ni ohun iyalẹnu kan fun yin. Gbogbo awọn iwaasu ti a ṣẹṣẹ waasu ati awọn Ìwé ati ohun gbogbo ni a o ta ni ẹyin ile-ijọsin, ni ọ̀sẹ̀ to n bọ, nigbati awọn ipade ba bẹrẹ. Awọn ohun ti a gba silẹ yi ati ohun gbogbo, gbogbo rẹ ni a kọ silẹ ni ẹda iwe-kika daradara. Tabili kan yoo wa ni ẹyin lọhun ni ẹyin ninu ọkan ninu awọn iyàrá, ati awọn ohun ti a kọ silẹ ni ẹda iwe-kika, awọn iwaasu ti a ṣẹṣẹ waasu, ati awọn ohun ti a kọ silẹ ti o dara ti a ti kọkọ kọ silẹ ninu awọn iwe tuntun awọn ẹdà rẹ tuntun, gbogbo rẹ ni a o kó sita ni ẹyin ile-ijọsin ni alẹ Ọjọ-rú. Gẹgẹ bi a ti se n reti akoko ti o dara ninu Oluwa. Wa pẹlu adura, bayi. Nisisiyi, ẹ pe awọn eniyan yin ti o n ṣe aisan ati awọn ti a pọ́n loju, ẹ kọ lẹta si wọn ki ẹ si mu wọn wá, a o si.... Ọlọrun yoo rìn pẹlu agbara. Awa yoo si mọ pe Oun yoo ṣe e nisisiyi.

185 Ati nisisiyi, mo ti lọ si ọdọ gbogbo awọn ti mo mọ pe wọn ni ohun kekere kan. Ti ko ba si ohunkohun ni oju ọna yi bayi, ṣe ẹ ranti, mo ti sọ eleyi fun yin tẹlẹ ni ọjọ ti o ti pẹ, gbogbo rẹ ni a o yanju. Mo si mọ pe ẹ mọ pẹ èmí ti o yatọ wà nibiyi yatọ si eyiti o ti wa tẹlẹ. Ṣe ẹ ri? Eyi jẹ otitọ. Nisisiyi, maṣe jẹ ki o pada lọ mọ. Mo paṣẹ fun yin niwaju Jesu Kristi maṣe jẹ ki o lọ. Duro nibiyi pẹlu rẹ, ṣe ẹ ri, ẹ mu ohun gbogbo tọ gẹlẹ ki ẹ si tẹ̀ siwaju. Arakunrin ni ẹ jẹ́. Ko ki n ṣe arakunrin rẹ rara tabi arabinrin rẹ ni o ṣe ohun ti o kuna, o jẹ ẹmi èṣù yẹn ni o wọle wa. Ṣe ẹ ri, o lọ.... Ẹ si ni ikaanu fun arakunrn tabi arabinrin naa, ki ẹ si mọ pe Satani ni o wọ aarin yin. Ti o ba si ni imọlara ti o yatọ nipa rẹ, mu eleyi kuro ninu rẹ ni kiakia, ṣe ẹ ri, nitori jẹjẹrẹ rẹ yoo jẹ ọ run. Bẹẹni, yoo ṣe eyi, nitori naa yago fun un, kan ranti.

Àyè wa, àyè wa,

Ọpọlọpọ àyè

Àyè wa fun awọn ara ijọ Metọdisi àyè wa, fun awọn ara ijọ Baptisi àyè wa fun awọn ara ijọ Presibiteriani, àyè wa fun gbogbo eniyan;

Àyè wa, àyè wa, bẹẹni, àyè wa,

Aye wa n ibi`Isun naa fun ọ.

186 Ẹni melo ni o ranti orin atijọ akọjade wa, pe, "Mu orukọ Jesu pẹlu rẹ, ọmọ banujẹ ati ègbé, yoo si fi itunu fun ọ, mu lọ si ibi gbogbo?" O wu mi pe ki ẹyin duro si ọ̀dọ̀ wa, Arakunrin Jeffries, iwọ ati Arabinrin Jeffries, ati awọn ọmọkunrin nibẹ, ati gbogbo wọn. Ati lẹhin naa, "A o wọlẹ ni orukọ Jesu, A o wọlẹ l'Ẹsẹ Re, [Oo, Akiika!] A o de Ọba wa l'ade, Nigba t'ajo wa ba pari. Mu orukọ Jesu pẹlu rẹ. Mu bi`as`a loni; Oo, Bi idanwo ba si yi ọ ka, fi orukọ naa gbadura." Oo, mo nifẹ eyi, orukọ Jesu naa ti O jẹ iyanu. Bayi, ẹ jẹ ki a dide duro nisisiyi, nigbati a o kọrin naa bayi. O dara.

Mu Orukọ Jesu pẹlu rẹ

Ọmọ banujẹ ati egbe

Yoo si fi itunu fun ọ

Mu lọ si ibi gbogbo

Orukọ... iyebiye....

Ireti aye, Ayọ Ọrun,

Orukọ... iyebiye....

(Orukọ iyebiye)

Iyebiye!

Ireti aye, Ayọ Ọrun.

187 O yatọ diẹ bayi. Ẹ jẹ ki a tẹ ori wa ba nisisiyi, ati ni ìdákẹ́jẹ́ ẹ jẹ ki a gbe`ọkan ninu awọn ọwọ́ wa soke, ki a si sọ wipe;

A o wolẹ ni Orukọ Jesu,

A o wolẹ l'Ẹsẹ Rẹ

A o de Ọba wa lade,

Nigba t'ajo wa ba pari.

Orukọ.... iyebiye.... (Orukọ iyebiye),

Iyebiye! (O ni o tị se dun to)

Ireti aye, Ayọ Ọrun!

Orukọ.... Iyebiye (bẹẹni, orukọ Iyebiye),

Iyebiye! (O bi o ti ṣe dùn tó!)

Ireti aye, Aye ọrun!

Pẹlu ori wa ni títẹ̀ba sibẹ, ẹ jẹ ki a sọ wipe....

[Arakunrin Branham kọ orin naa ni akọsinu, “Mu Orukọ Jesu pẹlu Rẹ.”]

Ìwàásù lati ẹnu

William Marrion Branham

"... Ati ni ọjọ́ ohùn angẹli keje ..." Ifihan 10:7

www.messagehub.info